**COURSE GUIDE**

# YOR 241
# PHONOLOGY OF YORUBA I

**Course Team** Dr. Clement Odoje (Course Developer/Writer) University of Ibadan
Prof. Oye Taiwo (Course Editor) University of Ibadan
To be determined (Programme Leader)
To be determined (Course Coordinator)

**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA**

© 2021 by NOUN Press
National Open University of Nigeria
Headquarters
University Village
Plot 91, Cadastral Zone
Nnamdi Azikiwe Expressway
Jabi, Abuja

Lagos Office
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island, Lagos

e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

All rights reserved. No part of this book may be reproduced, in any form or by any means, without permission in writing from the publisher.

Printed 2021, 2023

ISBN: 978-978-058-208-1

**AKÒÓNÚ**

Ìfáárà ………………………………………………………… iv
Èrèdí Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ …………………………………………….. iv
Àfojúsùn Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ………………………………………… iv
Jíjẹ Àǹfààní Ìwé Yìí …………………………………………. v
Èròjà Fún Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ………………………………………… v
Ìwé Ìtọ́kasí àti ìwé tí a Ṣàmúlò ………………………………. vi
Ìgbéléwọ̀n ……………………………………………………. vi

# ÌFÁÁRÀ

Bàbá àgbàlagbà kan pàdé ọmọ tí ó ti ilẹ̀ òkèrè wá. Ọmọ náà lọ lo sáà ọludé rẹ̀ ní abúlé ni. Nínú ìtàkurọ̀sọ wọn, èdè tí bàbá náà pè kò yé ọmọ yìí. Ẹ gbọ́ ohun tí bàbá náà wí: *Mọdé yìí, ṣèbí iwọ lọmọ Làísì. Bóo bá délé, wí fún bàá rẹ, kọ́ mọ́ gbàgbé n mo fi lọ̀ ọ́, pé ààkà tó fi ránṣẹ́ ò ká mi lẹ́nu. Ṣó yé ọ?* Ọmọ náà fèsì pé kò yé òun. Bàbá bá ni ọmọ ò gbọ́ Yorùbá. Ọmọ ní mo gbọ́ Yorùbá dáadáa. N gbọ́, ṣé ọmọ náà ò gbọ́ Yorùbá?

Èyí ó wù kí èrò rẹ jẹ́, bí a bá wo ìpèdè bàbá náà, bí ó tilẹ̀ yàtọ̀ sí ohun tí a rò pé ó yẹ kí ó jẹ́ síbẹ̀ ìpèdè náà yé wa. Nígbà tí a bá ń ṣe afọ̀ geere, orísìírísìí nǹkan ni ó máa ń ṣẹlẹ̀ sí ìró ìfọ̀ ṣùgbọ́n àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà ní ààtò tí ó bá òfin èdè mu tó bẹ́ẹ̀ tí ìtumọ̀ o fi gbọdọ̀ sọnù.

Ẹ̀kọ́ nípa ètò ìró gan-an ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí dálé lórí. Ohun kan tí ó sì ṣe pàtàkì fún onímọ̀ ẹ̀dá èdè ni láti wo ààtò ìró bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn elédè kìí tilẹ̀ bìkítà nípa rẹ̀ ṣùgbọ́n wọ́n mọ bí àwọn ìró inú èdè wọn ṣe ń ṣiṣẹ́ àti pé ìró kan yàyọ̀ sí èkejì. Gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ń sọ èdè Yorùbá tàbí tí ó ń kọ́ nípa rẹ̀, gbogbo wa la mọ̀ pé ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni wọ́n ni ègé ìró mẹ́ta mẹ́ta: *gbá, wá, sá,* àti *rá*. Ó fi ojú hàn pé ègé ìró [gb], [w], [s] àti [r] ni ó fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ fún àwọn ọ̀rọ̀ náà. Ó sì ṣe é ṣe kí a rí ọ̀rọ̀ bí i [ìbàdàn] àti [ìbàdọ̀n] ní ìbi tí ègé ìró [an] àti [ọn] kò ti mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ bá ọ̀rọ̀ méjéèjì. Nítorí náà, ààtò ìró báyìí ni iṣẹ́ yìí dá lé lórí.

Èrò tiwa ni pé, nígbà tí o bá ka ẹ̀kọ́ yìí dé òpin, àkàgbádùn ni gbogbo rẹ̀ yóó jẹ́. Àmọ́ sá o, kìí ṣe adùn rẹ̀ ni a fẹ́ kí ó jẹ ìwọ àti àwa lógun bí kò ṣe ìmọ̀ àmọ̀-dájú nípa ààtò ìró èdè Yorùbá. Ó yẹ kí a fi kún-un pé, lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, wà á lè fi ìyàtọ̀ hàn láàárín ìró aṣèyàtọ̀ àti ìró aláìṣèyàntọ̀, pàtàkì wọn nínú ọ̀rọ̀; Ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn àti sàkáni tí wọ́n ti máa ń wáyé; sílébù, ìhun sílébù àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù. A ó mẹ́nu bà àrànmọ́, ìpajẹ ní sókí.

# ÈRÈDÍ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àwọn èrèdí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a là kalẹ̀ sí ìsàlẹ̀ yìí:

- Sàlàyé àwọn ìgbẹ́sẹ̀ fonọ́lọ́jì tí ó wà ní èdè Yorùbá
- Tọ́kasí àwọn sàkání tí àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yìí ti jẹyọ
- Ní èrò tí ó dájú lórí àwọn ìgbésẹ̀ tí ó ní àlàyé ju ẹyọ kan lọ

# ÀFOJÚSÙN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn wọ̀yí ni àfojúsùn wa: Akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

- Fi àpẹẹrẹ ṣàlàyé fóníìmù kọ́nsónáǹì, fáwẹ́lì àti tóníìmù
- ṣe àdàkọ ìró ní ìlànà àkọtọ́ àti ìlànà àdàkọ IPA

- Ṣàfihàn sílébù, yóó sì le ṣàlàyé ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù
- Tọ́ka sí sàkání tí àrànmọ́ tí máa ń wáyé
- Ṣàfihàn ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn àti ibi tí ìyípadà ohùn ti máa ń wáyé

## JÍJẸ ÀǸFÀÀNÍ ÌWÉ YÌÍ

Láti jẹ àǹfààní ìwé yìí ni ọ̀nà tí yóó ràn ọ́ lọ́wọ́, kí o sì kógo já lẹ́nu ẹ̀kọ́ rẹ, tó bẹ́ẹ̀ tí yóó fi wúlò fún ọ lẹ́yìn tí o bá kọ́ ẹ̀kọ́ náà tán, àwọn nǹkan ń bẹ tí ó yẹ kí o ṣe. Ohun àkọ́kọ́ tí ó yẹ kí o mọ̀ ni pé, o ní láti farabalẹ̀ ka ìwé yìí. Àwọn ìbéèrè wà ní ìbẹ̀rẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan nínú àgbékalẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí láti ran akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́. Kìí ṣe dandan kí o lè dáhùn àwọn ìbéèrè náà. Kìí sì ṣe ìsòro bí o kò bá níran àti gbíyànjú láti fèsì ọ̀kankan nínú wọn. A tò wọ́n jọ síbẹ̀ láti jẹ́ àfojúsùn ohun tí ó yẹ kí o lè ṣe lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ni. Nítorí náà, ìpòǹgbẹ́ fún ìmọ̀ ni wọ́n wà fún. Ṣùgbọ́n, bí o kò bá lè dáhùn àwọn ìbéèrè náà, lẹ́yìn tí o ti ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà tán, ìyẹn túmọ̀ sí pé, ohun tí o kà kò yé ọ. Nítorí náà, o nílò láti tún un ka tàbí wá ìrànlọ́wọ́ lọ sọ́dọ̀ ẹni tí o lè kọ́ ọ. Àmọ́, ohun kan dá mi lójú pé ọ̀nà tí a gbà ṣàlàyé àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí jẹ́ èyí tí ó rọrùn púpọ̀ láti jẹ́ kí àwọn kókó náà yé ènìyàn dáadáa. A ní in lọ́kàn pé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí yóó gbà ọ́ ni ọ̀sẹ̀ mẹ́ẹ̀ẹ́dógún láti kọ́ gbogbo ẹ̀kọ́ inú rẹ̀ tán, lẹ́yìn náà ni wà á wá ṣe ìdánwò. A tún ti ṣe àlàkalẹ̀ bí wà á ṣe ka ìwé yìí lọ́nà tí yóó fi ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ṣe àmúlò àkókò rẹ dáadáa tó bẹ́ẹ̀ tí ìṣẹ́ náà yóó ṣe wọ̀ ọ́ ní akínyẹmi ara rẹ.

## ÈRÒJÀ FÚN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àwọn wọ̀nyí ni èròjà ìdánilẹ́kọ̀ọ́:

- Àtọ́nisọ́nà Ẹ̀kọ́
- Ẹka Ẹ̀kọ́
- Ìwé Àmúlò
- Ìgbéléwọ̀n
- Àlàkalẹ̀ Ìṣẹ́
- Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́

Móòdù mẹ́tà (3) àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ mẹ́ẹ̀ẹ́dógún (15) ni ó wà. Móòdù àkọ́kọ́ dá lórí ègé ìró. Èyí ni yóó ṣe ìpìlẹ̀ fún àwọn ìjíròrò wa lórí àwọn ètò ìró àti ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ní èdè Yorùbá. Nípasẹ̀ Móòdù yìí, yóó jẹ́ kí ó rọ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti olùkàwé yìí lọ́rùn láti mọ ìrú ìgbésẹ̀ Fonọ́lọ́jì tí ó wáyé àti ọ̀gangan ibi/sàkání tí ó ti wáyé. A ó tún mẹ́nu ba ìró aṣèyàtọ̀ àti bí a ṣe máa ń sàwárí wọn. Móòdù kejì yóó dá lórí sílébù, ìhun sílébù àti ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù. Ní Móòdù kẹta ni a ó ti mẹ́nu ba àwọn ìgbésẹ̀ fonọlọ́jì nínú àbùdá afọ̀ geere bi, àrànmọ́, ìsúnkì àti ìparójẹ ní sókí.

**Móòdù Àkọ̀kọ́: Ègé Ìró**
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkínní: ègé ìró
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkejì: ìró kọ́nsónáǹtì
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹta: ìró fáwẹ́lì
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹrin: ìró ohùn
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkarùn-ún: ìró àṣèyàtọ̀
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kẹfà: dída ìró kọ

**Móòdù Kejì: Sílébù**
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkínní: sílébù
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkejì: ìhun sílébù
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹta: ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ àti ọlọ́pọ̀ sílébù

**Móòdù Kẹta: Àbùdá Afọ̀ Geere**
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkínní: ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkejì: àrànmọ́
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹta: ìparójẹ

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ ÀTI ÌWÉ TÍ A ṢÀMÚLÒ

Yàtọ̀ sí ìwé yìí, ìbá dára bí ó bá le nawọ́ mú àwọn ìwé mìíràn fún kíkà. Àwọn ìwé tí a ó là kalẹ̀ ní ìsàlẹ̀ yìí yóó ràn ọ́ lọ́wọ́ nígbà tí o bá fẹ́ ṣe ìṣẹ́ àmúrelé/aṣetiléwá rẹ

Ayo Bamgboṣe (1990) Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá. Ibadan. Uiversity Press Linited.

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá 1: Fonẹ́tîìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ìbàdàn. Universal Akada Book Nigeria Limited.

Francis Oyebade (2001) Ìgbésẹ̀ àti Ìlànà Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlè Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíresọ̀ àti Àṣà* tí Bádé Àjàyí jẹ́ olóòtú fún

## ÌGBÉLÉWỌ̀N

Ìgbéléwọ̀n méjì ni ó wà fún iṣẹ́ yìí, ìṣẹ́ àṣetiléwá àti ìdánwò, àpapọ̀ méjéèjì yóó jẹ́ ọgọ́nrùn-ún. Àpapọ̀ máàkì fún iṣẹ́ àmúrelé yóó jẹ́ ogójì (40%). Máàkì ìdánwò á sì jẹ́ ọgọ́ta (60%). Ìrètí wa ni pé ìmọ̀ rẹ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni yóó ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ṣe àṣeyege nínú àwọn ìgbéléwọ̀n tí ó yẹ fún ọ láti mọ̀ kí o sì kógo ja.

**MAIN COURSE**

## CONTENTS PAGE


| | | |
|---|---|---|
| **Móòdù Àkọ̀kọ̀** | **Ègé Ìró ……………………………………** | **1** |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkínní | Ègé Ìró ………………………………… | 1 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkejì | Ìró Kọ́nsónáǹtì ………………………… | 6 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹta | Ìró Fáwẹ́lì ……………………………… | 11 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkẹrin | Ìró ohùn ……………………………... | 16 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkarùn-ún | ìró Àṣèyàtọ̀ ……………………... | 21 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kẹfà | Dída ìró kọ …………………………….. | 27 |
| **Móòdù Kejì** | **Sílébù ………………………………….** | **32** |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ìkínní | Sílébù ………………………………….. | 32 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ìkejì | Ìhun Sílébù …………………………….. | 34 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ìkẹta | Ọ̀rọ̀ Ẹléyọ àti Ọlọ́pọ̀ Sílébù ……………. | 37 |
| **Móòdù Kẹta** | **Àbùdá Afọ̀ Geere ……………………..** | **44** |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ìkínní | Ìgbésẹ̀ Ajẹmóhùn ……………………… | 44 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ìkejì | Àrànmọ́ ………………………………… | 52 |
| Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ìkẹta | Ìparójẹ ………………………………… | 58 |

# MÓÒDÙ ÀKỌ́KỌ́ ÌDÁNILẸ́KÒỌ́ ÌKÍNNÍÈGÉ ÌRÓ

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ẹ̀ka yìí dá lórí ègé ìró àti gbogbo ohun tí ó rọ̀ mọ́ ọn. Ní ìgbá tí a bá ń sọ̀rọ̀ tàbí fọ̀, ìró ni a máa ń lò. Irú àwọn ìró báyìí ni a máa ń lo lẹ́tà àti àmì láti fi ṣe àkọsílẹ̀ wọn. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ó sì ti wo ìrú àwọn iró ifọ̀ tí a máa ń lò.

## 2.0 ÈRÒNGBÀ ÌDÁNILẸ́KÒỌ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àkẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

- Ki ìró ifọ̀
- Ṣàlàyé ègé ìró
- Dárúkọ èyà ègé ìró àlágbèéká

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

- Ki ìró ifọ̀
- Ṣàlàyé ègé ìró
- Dárúkọ ẹ̀yà ègé ìró alágbèéká

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KÒỌ́

## 3.1 Ìró Ìfọ̀

Ní ìgbàkúùgbà tí ènìyàn bá ń tàkurọ̀sọ, ìró ni a máa ń gbọ́. Ohun kan pàtàkì tí ó ya ènìyàn sọ́tọ̀ sí àwọn ẹ̀dá mìíràn ni ìró èdè/ìfọ̀. Ìró ni ẹni tí ó sọ̀rọ̀ lò láti gbé èrò rẹ̀ jáde, ìró yìí kan náà ni ẹni tí ó gbọ́ ọ gbọ́, tí ó sì fún un ní ìtumọ̀ láti ní òye ohun tí ẹni tí ó ń sọ̀rọ̀ ń sọ.

Ó yẹ kí á mọ̀ pé, kìí ṣe gbogbo ìró tí ènìyàn lè dá pè tàbí gbé jáde ni ìró èdè/ìfọ̀. Àpẹẹrẹ ni bí ọmọdé bá ń sunkún tàbí bí ènìyàn bá yán, àwọn ìró wọ̀nyí kìí ṣe ìró èdè/ìró ìfọ̀. Owólabí (2013:14) ki ìró ifọ̀ báyìí:

*Ìró ifọ̀ ni ègé tí ó kéré jùlọ tí a lè (fi etí) gbọ́ nínú èdè*

Ohun tí ó ṣe pàtàkì nínú oríkì yìí ni: *ègé ìró tí ó kéré julọ,* ohun kejì ni *nínú èdè*. Ìyẹn ni pé ìró tí kò bá ti ní nǹkan ṣe pẹ̀lú èdè, kò lè ṣe é kan mọ́ ìró èdè kan. Àpẹẹrẹ kan tí ènìyàn lè fi sí ọkàn ni àwàdà tí àwọn kan máa ń ṣe nípa ọmọ kan tí ó sunkún pàdé ọlọ́dẹ orí kan. Wèrè yìí bi ọmọ yìí ìdí rẹ̀ tí ó fi ń sunkún, ọmọ náà fẹ̀sì pé olùkọ́ ohun ní òun ò mọ̀wé. Wèrè yìí bá fa ọmọ náà lọ́wọ́ lọ bá olùkọ́, ó bi olùkọ́ bí ó bá lè sípẹ́lì gbogbo ọ̀rọ̀ tí ó wà nínú èdè rẹ̀. Olùkọ́ fi ìdánilójú dáhùn pé bẹ́ẹ̀ ni. Wéré bá pòsé, ó ní kí olùkọ́ sípẹ́lì rẹ̀. Ọ̀rọ̀ bá di wò mí, kí ń wò ọ́.

A ó ṣàkíyèsí pé, olùkọ́ náà kò lè sípẹ́lì **òsé** nítorí pé **òsé** kìí ṣe ègè ìró ìfọ̀, ìdí nìyí tí Owólabí (2013) fi ṣàlàyé pé, yàtọ̀ sí oríkì, ohun mìíràn tí a gbọdọ̀ fi sọ́kàn nípa ìró ifọ̀ ni pé, wọ́n ṣe é dàkọ. Ọ̀nà méjì ni a lè gbà láti da àwọn ìró yìí kọ. Àwọn náà ni lílo lẹ́tà àti lílo àmì. Bí a bá wa lo òsùnwọ̀n dida ìró kọ ti à ń sọ yìí, a jẹ́ pé a lè pín ìró èdè Yorùbá sí ìsọ̀rí méjì gbòòrò. Ìsọ̀rí méjéèjì náà ni ègé ìró àti ègé ìró alágbèéká.

## 3.2 Ègé Ìró

Ègé ìró ni ìró tí a máa ń dà kọ nípa lílo lẹ́tà. Ẹ̀yà méjì sì ni irú àwọn ìró bẹ́ẹ̀ pín sí. Ẹ̀yà kan ni àwọn ìró tí à ń pè ní Kọ́nsónáǹtì. Ẹ̀yà kejì sì ni àwọn ìró tí à ń pè ni fáwẹ̀lì (wo Owólabí 2013:14).

## 3.3 Ègé ìró alágbèéká

Àwọn ìró tí a máa ń dà kọ nípa lílo àmì yàtọ̀ sí lẹ́tà ni a mọ̀ sí ègé ìró alágbèéká. Àpẹẹrẹ irú ìró bẹ́ẹ̀ nínú èdè Yorùbá ni ìró ohùn. Ẹ̀yà mẹ́ta ni wọ́n pín sí: òkè [´], àárín[1] àti ìsàlẹ̀ [`]. A lè sọ gbogbo atótónu wa yìí ni kúkúrú pẹ̀lú atọ́ka igi ìsàlẹ̀ yìí:




## 3.4 Àwọn Ẹ̀yà Ara Ìfọ̀

Ní ìgbà tí a bá ń sọ̀rọ̀, orísìírísìí ẹ̀yà ara wa ni a máa ń lò láti gbé àwọn ìró tí a fi ń fọ̀/sọ̀rọ̀ jáde. Àwọn ẹ̀yà ara àti ibaṣepọ̀ wọn láti gbé àwọn ìró bẹ́ẹ̀ jáde yẹ ní wíwò fínní-fínní. Láti gbé ìró ìfọ̀ jáde, apá kan láti ikùn títí dé orí ni a nílò. Àwọn ẹ̀yà ara yìí ni a fi hàn nínú àwòrán ìsàlẹ̀ yìí:




A ṣe amúlò àwòrán yìí láti http://aienndolhan.blogspot.com/2011/02/reflection-topic-2-introduction-to.html

1. Ẹ̀dọ̀ fóró
2. Kòmóòkun
3. Gògóńgò
4. Káà ọ̀fun
5. Àfàsé
6. Àjà-Ẹnu
7. Káà imú
8. Imú
9. Káà ẹnu
10. Ahán
11. Eyín
12. Ètè
13. Àgbọ̀n

1. **Ẹ̀dọ̀-fóró**: Èyí jẹ́ pàtàkì nínú ẹ̀yà ara ìfọ̀ tí a máa ń lò láti gbé ọ̀gọ̀rọ̀ ìró èdè Yorùbá jáde. Ní ìgbà tí a bá mí sínú, inú ẹ̀dọ̀-fóró yìí ni èémí náà ń lọ. Gbìyànjú láti mí sínú. Kín ni ó ṣẹlẹ̀? Ẹfánhà rẹ ṣe bí ẹni pé ó tóbi sí i, ó wá dà bí ẹni pé àyà rẹ ga sókè. Èémí tí o mí sínú ni ó fà á. Nígbà tí a bá mí sínú, inú ẹ̀dọ̀-fóró wà ni èémi náà ń lọ. Yóó sì tóbi ju bí ó ṣe wà tẹ́lẹ̀ lọ nítorí èémí náà. Ìwọ gbìyànjú láti sọ̀rọ̀ nígbà tí o bá ń mí sínú.

Bí a bá wá mí sóde, ẹ̀dọ̀-fóró yóó padà sí ipò rẹ̀. Èémí tí a mí sóde yìí ni a máa ń lò láti pe púpọ̀ àwọn ìró èdè Yorùbá. Àwọn onímọ̀ sì pe irú èémí bẹ́ẹ̀ ní ***Èémí Àmísóde.*** Èémí àmísóde yìí ni orísùn rẹ̀ jẹ́ ẹ̀dọ̀-fóró. Èémí tí ó ń ti inú ẹ̀dọ̀-fóró bọ̀ yìí ni a sábà máa ń lò láti pe púpọ̀ ìró èdè Yorùbá

2. **Kòmóòkun:** Èémí tí ó tú jáde láti inú ẹ̀dọ̀-fóró yóó gba inú ẹka kòmóòkun wọ inú kòmóòkun. Inú kòmóòkun yìí sì ni èémí náà yóó gbà dé inú gògóńgò
3. **Gògóńgò**: Orí kòmóòkun ni gògóńgò wà. Inú rẹ̀ sì ni àwọn ẹ̀yà ara tí a mọ̀ sí tán-án-ná wà. Àwọn tán-án-ná wọ̀nyí sopọ̀ ní iwájú ṣùgbọ́n wọ́n pínyà lẹ́yìn láti fi àyè gba èémí tí ó ń ti inú ẹ̀dọ̀-fóró bọ̀. Ibi tí èémí ń gbà jáde yìí ni a mọ̀ sí àlàfo tán-án-ná. Àwọn tán-án-ná yìí lè wà ní ipò púpọ̀ ṣùgbọ́n fún ìró pípè, ipò méjì péré ni: ipò ìmí àti ipò ìkùn. Tí àwọn tán-án-ná yìí kò bá sùn lé ara wọn, tí èémí sì ń fi ẹ̀rọ̀wọ́rọ́ jáde láìsí ìdíwọ́ kankan, ipò yìí ni a mọ̀ sí ***ipò ìmí.*** Ṣùgbọ́n tí àwọn tán-án-ná yìí bá sùn lé ara wọn tó bẹ́ẹ̀ tí èémí ń fi agbára jáde tí ó sì mú ẹ̀gbọ̀nrìrì lọ́wọ́, ipò yìí ni a mọ̀ sí ***ipò ìkùn***. Ìró tí a bá pè ní ipò ìmí ni a mọ̀ sí ìró àìkùnyùn nígbà tí ìró tí a bá pè ní ipò ìkùn jẹ́ ìró akùnyùn.
4. **Káà ọ̀fun**: ọ̀kan lára àwọn káà tí ó wà ní òkè tán-án-ná (tí ó wà nínú gògóńgò) ni káà ọ̀fun jẹ́. Káà yìí já pọ̀ mọ́ káà imú àti káà ẹnu. Inú káà yìí ni èémí ẹ̀dọ̀-fóró tí ó ti inú àlàfo-tán-án-ná bọ̀ yóó'gba wọ inú káà imú tàbí káà ẹnu.
5. **Àfàsé**: òkè tán-án-ná náà ni àfàsé wà. Ó sí ṣe é gbé sókè tàbí kí ó wá sí ìsàlẹ̀. Ipò méjéèjì yìí ní ipa púpọ̀ lórí àwọn ìró tí à ń gbé jáde. Bí àfàsé bá gbé sókè tí ó lọ di ọ̀nà tí ó lọ sí imú, tí èémí sì ń gbà ẹnu nìkan jáde, irú ìró tí a bá pè nígbà náà ni à ń pè ní ìró àìránmú. Ṣùgbọ́n tí àfàsé bá wá sí ìsàlẹ̀ tí èémí ń gba imú àti ẹnu jáde, irú ìró tí a bá pè ní ìgbà náà ni a mọ̀ sí ìró aránmú.
6. **Àjà-ẹnu**: ẹ̀yà ara ìfọ̀ yìí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀yà ara ifọ̀ tí ó wà ní káà ẹnu. Ohun ni àárín-ahọ́n máa ń lọ pàde láti pe ìró /j/, /ɟ/
7. **Káà Imú**: Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ saájú, káà ọ̀fun, káà Imú àti káà ẹnu ja ara wọn. Bí àfàsé bá wá sí ìsàlẹ̀ tí èémí sì ń gbá káà imú lọ sí imú láti jáde, irú ìró tí a bá pè ní gbà náà ni a mọ̀ sí ìró aránmú.
8. **Imú:** Inú imú ni èémí ẹ̀dọ̀-fóró tí ó ti gba inú àlàfo tán-án-ná wọ inú káà imú yóó gbà jáde sí ìta.
9. **Káà ẹnu**: Ọ̀pọ̀ ni ẹ̀yà ara ìfọ̀ tí ó wà nínú káà ẹnu lára wọn ni ahọ́n, èrìgì, àjà-ẹnu, eyín àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo àwọn èyà ara ìfọ̀ yìí ni à ń lò lọ́npa kan tàbí lọ́nà mìíràn láti pe ìró jáde. Wọ́n tílẹ̀ pín àwọn ẹ̀yà ara ìfọ̀ láti àfàsé títí dé ètè sí ọ̀wọ́ méjì: afipè akànmọ́lẹ̀ ati àfipè Àsúnsí

## 3.4.1 Ẹ̀yà Àfipè

Gbogbo ẹ̀yà ara tí à ń lò fún pípe ìró ni a mọ̀ sí àfipè. Awọn onímọ̀ pín ẹ̀yà ara àfipè yìí sí méjì: aṣeéfojúrí àti àìṣeéfojúrí. Aṣeéfojúrí ni awọn ẹ̀yà ara àfipè tí a lè fi ojú wa rí wọn. Àpẹẹrẹ ẹ̀yà ara àfipè aṣeéfojúrí ni ètè,

eyín, àjà-ẹnu àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ̀yà àfipè àìṣeéfojúrí ni àwọn ẹ̀yà ara àfipè tí a kò lè fojú rí. Apẹẹrẹ ni ẹ̀dọ̀-fófó, ẹ̀ka kòmóòkun, gògóńgò, tán-án-ná àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

A tún lè pín ẹ̀yà ara àfipè aṣeéfojúrí sí méjì. Àwọn ni àfipè àkànmọ́lẹ̀ àti àfipè àsúnsí.

**Àfipè Àkànmọ́lẹ̀:** èyí ni àwọn ẹ̀yà ara ìfọ̀ tí wọn máa ń dúró gbári, tí ẹ̀yà àra ìfọ̀ mìíràn máa ń lọ bá láti pe ìró. Àpẹẹrẹ ni:

Ètè òkè, èrìgì, àjà-ẹnu, àfàsé, ògiri ọ̀fun
Ó yẹ kí a fi kún un pé ìrísí ètè òkè nígbà mìíràn máa yàtọ̀ sí pé ó kàn dúró gbári. Ó máa ń gbéra díẹ̀ nígbà tí a bá ń kópa nínú pípe àwọn ìró kan. Àpẹẹrẹ ìró bẹ́ẹ̀ ni ìró kọ́nsónáǹtì afèjì-ètè-pè /b/, /m/ ní ibi tí ètè òkè gẹ́gẹ́ bí àfipè akọ̀nmọ́lẹ̀ ti gbéra díẹ̀ láti pàdé ètè ìsàlẹ̀ tí i ṣe àfipè àsúnsí.

**Àfipè Àsúnsí:** èyí ni ẹ̀yà ara ìfọ̀ tí wọ́n máa ń gbéra láti sún mọ́ àfipè àkànmọ́lẹ̀, nígbà mìíràn, wọ́n máa ń fi ara kan àfipè àkànmọ́lẹ̀ láti gbé ìró jáde. Ohun kan tí ó tún ṣe pàtàkì ni pé, bí a bá fẹ́ ṣe àpèjúwe ìró kan, a máa ń lo ọ̀gangan ibi tí àfipè. Àpẹẹrẹ àfipè àsúnsí ni, ètè ìsàlẹ̀, iwájú ahọ́n, àárín àhọ́n, ẹ̀yìn ahọ́n àti òlélé

## 4.0 CONCLUSON

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Nínú ìdánilékọ̀ọ́ yìí, a ṣàlàyé pé, nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀, ìró ni a máa ń gbọ́, ìyẹn ni pé, ojú ni ọ̀rọ̀ wà ṣùgbọ́n etí ni a fi máa ń gbọ́ ọ. Bátánì gbòòrò méjì tí a mẹ́nu bà ni ìró ifọ̀ àti ìtumọ̀. A sọ pé ìró pín sí ọ̀nà méjì: ègé ìró àti ègé ìró alágbèéká. A tún ṣe àlàyé lórí ẹ̀yà ara ìfọ̀ àti ẹ̀yà àfipè.

## 6.0 ÌDÁNRAWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Gbìyànjú láti dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí.

1. Fún ìró ifọ̀ ní oríkì
2. Ṣe àlàyé ègé ìró
3. Dárúkọ ẹ̀yà ègé ìró alágbèéká

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá 1: Fonẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ìbàdàn. Universal Akada Book Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ Ẹ̀KỌ́ KEJÌ

# ÌRÓ KỌ́NSÓNÁǸTÌ

## 1.0 ÌFÁÁRÁ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọja, a sọ̀rọ̀ nípa ègé ìró àti ègè ìró alágbèékà. A sọ pé ègé ìró ni dída ìró kọ nípa lílo lẹ́ta nígbà tí a máa ń lo àmì fún ègé ìró alágbèékà. A pín dída ìró kọ nípa lílo lẹ́tà sí ọ̀nà méjì gbòòrò; àwọn náà ni kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí yóò dá lórí ìró kọ́nsónáǹtì. Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àfojúsùn wa ni pé, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè fún kọ́nsónáǹtì ni oríkì, yóò sì lè lo òsùnwọ̀n tí ó yẹ bí i ibi-ìsẹ́nupe, ọ̀nà ìsẹ́nupè àti irú ìdíwọ́ tí ó wà fún èémi ní òpópónà ajẹmóhùn láti pín kọ́nsónáǹtì sí ìsọ̀rí. A tún ń retí pé akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè fún kọ́nsónáǹtì Yorùbá ni orúkọ olọ́rọ̀ ìperí mẹ́tà

## 2.0 ÈRÒNGBÀ ÌDÀNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní òpin idánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

- Fún kọ́nsónáǹtì ní oríkì
- Pín kọ́nsónáǹtì sí ìsọ̀rí nípa lílo òsùnwọ̀n
- Fún kọ́nsónáǹtì ní orúkọ ọlọ́rọ̀ ìperí mẹ́ta

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

Dáhùn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí:

1. Fún kọ́nsónáǹtì ní oríkì
2. Pín kọ́nsónáǹtì sí ìsọ̀rí
3. Fún àwọn kọ́nsónáǹtì wọ̀nyí ní orúkọ ọlọ́rọ̀ òperí mẹ́ta [b], [gb], [l], [k]

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ọ̀kan nínú ìgbésẹ̀ dída ìró kọ nípa lílo lẹ́ta ni kọ́nsónáǹtì jẹ́. Owólabí (2013:15) ki kọ́nsónáǹtì báyìí:

*Kọ́nsónáǹtì* ni *ìró tí a pè nígbà tí ìdíwọ́ wà fún èémí ni ibì kan ní òpópónà ajẹmóhùn*

Ìlànà Fónẹ́tíìkì ni Owólabí gùnlé láti fún kọ́nsónáǹtì ní oríkì òkè yìí. Ó sì yẹ kí á mẹ́nu ba irú ìdíwọ́ tí ó lè bá èémí ní òpópónà ajẹmóhùn. Irú ìdíwọ́ bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ èyí tí yóò mú kí èémí sé pátápátá tàbí kí àlàfo díẹ̀ wà fún èémí láti gbà kọjá pẹ̀lú ariwo tí a lè gbọ́ ketekete. Bí ó bá rí bẹ́ẹ̀, a ó rí pé ìró [w] àti ìró [j] kò bẹ́gbẹ́ mu. Ìdí ni pé ìrú ìdíwọ́ tí a ṣàlàyé sókè yìí kọ́ ni ó

sẹlẹ̀ nígbà tí a ń pè wọ́n, àwọn afipe tí a lò kan súnmọ́ ara wọn, kìí jẹ́ pé wọ́n kan ara wọn.

Bí a bá gùn lé oríkí Kọ́nsónáǹtì ní ìlànà fonọ́lọ́jì, a lè sọ pé kọ́nsónáǹtì jẹ́ apàálà sílébù (wo Crystal 2008). Oríkì yìí sì fàyè gba ìró [w] àti [j] dáadáa. Nítorí náà, a lè sọ pé ìró kọ́nsónáǹtì ni ìró tí a pè nígbà tí ìdíwọ́ wà fún èémí ní ibìkan ní òpópónà ajẹmóhùn tí a sì le lò gẹ́gẹ́ bí apàlà sílébù. Èyí fi àyè gbà gbogbo ìró kọ́nsónáǹtì Yorùbá

Nítorí náà Kọ́nsónáǹtì èdè Yorùbá ní ìlànà àkọtọ́ ni ìwọ̀nyí:
b d f g gb h j k l m n p r s ṣ t w y

àmọ́ bí a bá fẹ́ kọ wọ́n ní ìlànà àdàkọ IPA, bí wọn yóó ṣe rí nìyí:
b d f gb h dʒ k l m n kp r s ʃ t w j

Àpẹẹrẹ àwọn kọ́nsónáǹtì náà ní ìlànà àkọtọ́ àti ìlànà àdàkọ IPA pẹ̀lú ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn tí wọ́n ti jẹyọ.

| Àdàkọ | ọ̀rọ̀ |
|---|---|
| [b] | bí, bɔ, abɛ |
| [d] | dá, dé, èdè |
| [f] | fɛ́, fɔ, ɛ̀fɔ́ |
| [g] | gɔ, ga, àgɔ́ |
| [gb] | gbá, gbó, àgbà |
| [h] | he, há, ahá |
| [dʒ] | dʒó, dʒɔ, adʒá |
| [k] | ké, ká, ikú |
| [l] | lɔ, là, àlá |
| [m] | mo, mú ɔmɔ |
| [n] | nu, nà, ɔ̀nà |
| [kp] | kpɛ́, kpukpá, ɔ̀kpá |
| [r] | rá, rɛ́, ara |
| [s] | sá, sũ̀, àsè |
| [ʃ] | ʃé, ʃɔ, aʃɔ |
| [t] | tɛ, tà, ata |
| [w] | wé, wɔ́, àwɔ̃̀ |
| [j] | jã̀, jɔ, ajɔ̀ |

## 3.1 Àbùdá Pàtàkì gẹ́gẹ́ bí Òsùnwọ̀n fún Ìsàpèjúwe Ìró Kọ̀nsónáǹtì

Nígbà tí a bá ń ṣe àpèjúwe ìró kọ́nsónáǹtì èdè Yorùbá, àwọn nǹkan wọ̀nyí wà lára àbùdá pàtàkì tí ó yẹ kí á tẹ̀lé gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe jẹ mọ́ gbígbé ìró kọ́nsónáǹtì kọ̀ọ̀kan jade:

**Orísun èémí tí a lò**:
Èémí tí asẹ̀dá rẹ̀ jẹ́ ẹ̀dọ̀ fóró (èémí ẹ̀dọ̀ fóró) ni a máa ń lò fún gbígbé gbogbo ìró kọ́nsónáǹtì èdè Yorùbá jade àyàfi méjì nínú wọ́n (kp àti gb) tí a máa ń gbé jade nípa lílo àpapọ̀ èémi ẹ̀dọ̀ fóró àti èémí tí asẹ̀dá rẹ̀ wà ní ẹnu. (wo Owoláni 2013:29)

**Irú èémí tí a lò**:
Èémí àmísóde ni a lò fún gbogbo ìró èdè Yorùbá àyàfi kọ́nsónáǹtì ***kp*** àti ***gb*** tí a lo àpapọ̀ èémi àmísóde àti èémí àmísínú.

**Ipò tí tán-án-ná wà**:
Àlàfo tán-ná-ná lè wà ní ipò méjì: ipò ìmí tàbí ipò ìkùn. Tí tán-án-ná bá wà ní ipò ìmí, ìyẹn ni pé, alàfo tán-án-ná wà ní sísí sílẹ̀ tí èémí sì ń fi ẹ̀rọ̀wọ́ jáde, àwọn kọ́nsónáǹtì tí a pè nígbà náà ni à ń pè ní kọ́nsónáǹtì àìkùnyùn àpẹẹrẹ wọn sì ni ***t k kp f s h*** abbl. Ṣùgbọ́n nígbà tí àlàfo tán-án-ná bá wà ní dídí tí èémí sì ń fi tagbára tagbára kọjá ní àlàfo tán-an-ná tó bẹ́ẹ̀ tí tán-án-ná ń gbàn rìrì tí a sì ń gbọ́ ìró ìkùn, irú àwọn kọ́nsónáǹtì bẹ́ẹ̀ ni à ń pè ní kọ́nsónáǹtì akùnyùn, àpẹẹrẹ wọn ni ***b d m n l j w*** abbl.

**Ipò tí àfàsé wà**:
Àfàsé lè gbé sókè láti dí ọ̀nà tí ó lọ sí imú tàbí kí ó wá sílẹ̀ láti jẹ́ kí ọ̀nà sí imú sí sílẹ̀. Tí ọ̀nà imú bá sí sílẹ̀, àwọn kọ́nsónáǹtì tí a pè nígbà náà ni à ń pè ní aránmú bíi: ***m n ŋ ɲ ɱ***abbl ṣùgbọ́n ní ìgba tí ọná sí imú na dí tí èémí sì ń gba ẹni nikan jáde, irú ìró tí a bá pè ní gbà náà ni a mọ̀ sí àìránmúpè. Àpẹẹrẹ ni ***b l s t*** abbl.

**Àfipè tí a lò**:
(Afipè àsúnsí àti àkànmọ́lẹ̀) fún pípa kọ́nsónáǹtì kọ̀ọ̀kan àpapọ̀ àfipè àsúnsí àti àkànmọ̀lẹ̀ ni a máa ń lò. Láti pe ìró b, a nílò àpapọ̀ àfipè àsúnsí ètè ìsàlẹ̀ àti àfipè àkànmọ̀lè ètè òkè. Bẹ́ẹ̀ náà ni a ó ṣe bí a bá fẹ́ pe ìró f, a nílò àpapọ̀ àfipè àsúnsí ètè ìsàlẹ̀ àti àfipè àkànmọ́lẹ̀ eyín òkè abbl.

**Irú ìdíwọ́ tí ó wà fún èémí tí a lò**
Irú àwọn ìdíwọ́ tí ó lè wà fún èémi ni ibì kan ní òpópónà ajẹmóhùn ni a là kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àlàyé Owólabí (2013)

- ọ̀nà èémí sé pátápátá ni ibi kan ni ẹnu (ASÉNUPÈ)
- ọ̀nà èémí lè máa ṣe pátápátá, ṣùgbọ́n kí àlàfo díẹ̀ wà fún èémí láti kọjá pẹ̀lú ariwo tí ènìyàn lè gbọ́ ketekete (ÀFÚNNUPÈ)
- àlàfo tí ó tó fún èémí láti gbà kọjá láì jẹ́ pé ariwo kankan tí a gbọ wà (ÀSÉÈSÉTÁN)

Bí a bá tẹ̀lé àbùdá òkè yìí a lè ṣe àpèjúwe gbogbo ìró kọ́nsónáǹtì èdè Yorùbá ṣùgbọ́n a kò ní ṣe àpèjúwe wọn nítorí pé àyè kò lè gbà wá láti ṣe bẹ́ẹ̀. A ó kan fi àpẹẹrẹ méjì hàn ọ́ kí o sì gbìyànjú láti ṣe àpèjúwe àwọn tí ó kù fún ra rẹ.

Kọ́nsónáǹtì [b] nínú ọ̀rọ̀ bíi **b**ù**b**á

1. èémi ẹ̀dọ̀ fóró ni a lò
2. èémi ẹ̀dọ̀ fóró tí a lò jẹ́ èémí àmísóde
3. àlàfo tán-án-ná wà ní ipò ìkùn
4. afàsé gbé sókè lái dí ọ̀nà sí imú
5. àfipè asúnsí ni ètè ìsàlẹ̀ tí ó sùn pàdé àfipè àkànmọ́lẹ̀ ètè òkè
6. Ọ̀nà èémí ṣé pátápátá
7. Kọ́nsónáǹtì [gb] nínú ọ̀rọ̀ bíi **gb**an**gb**a
8. Àpapọ̀ èémí ẹ̀dọ̀-fóró àti èémí tí aṣẹ̀dá rẹ̀ wà ní ẹnu ni a lò
9. Èémí ẹ̀dọ̀-fóró jẹ́ èémí-àmísóde, ṣùgbọ́n èémí tí aṣẹ̀dá rẹ̀ wà ní ẹnu jẹ́ èémí-àmísínú.
10. Àlàfo tán-án-ná wà ní ipò ìkùn
11. Àfàsé gbé sókè láti dí ọ̀nà sí imú
12. Afipè àsúnsí ni ètè ìsàlẹ̀ àti ẹ̀yìn-ahọ́n. Àfipè àkànmọ́lẹ̀ sì ni ètè òkè àti àfàsé
13. Ọ̀nà èémí sé pátápátá

Ní báyìí, èrò mi ni pé, ó yẹ kí o lè ṣe irú ìgbékalẹ̀ yìí fún àwọn kọ́nsónáǹtì tó kù.

**Fífún Kọ́nsónáǹtì ní Orúkọ Ọlọ́rọ̀ Ìperí Mẹ́ta**

Gẹ́gẹ́ bí onímọ̀, a fẹ́ fún ọ̀kọ̀ọ̀kan awọn kọ́nsónáǹtì ní orúkọ, àwọn ohun tí a ó sì gùnlé ni

1. Ipò alàfo tán-án-ná – àìkùnyùn/akùnyùn
2. Ibi isẹ́nupè
3. Ọ̀nà isẹ́nupè

Bí a bá gùnlé àwọn alàkalẹ̀ òkè yìí orúkọ ti a lè fún ìró [f] [d] àti [k] ni:
[f] àìkùnyùn afiyínfètèpè afúnnupè
[d] akùnyùn afèrìgìpè àsénupè
[k] àìkùnyùn afàfàsépè àsénupè
Àtẹ kọ́nsónáǹtì ìsàlẹ̀ yìí yóó jẹ́ kí ó rọrùn fún ọ láti rí àwọn kọ́nsónáǹtì èdè Yorùbá àti orúkọ Ọlọ́rọ̀ ìperí mẹ́ta wọn.

| Ibi Isẹ́nupè → / Ọ̀nà Ìsẹ́nupè ↓ | Afejìètèpè | Àfeyínfètèpè | Afèrìgìpè | afàjàfèrìgìpè | afàjàpè | Afàfàsépè | afàfàséfètèpè | afitanannapè |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Asénupè | b | | t<br>d | | dʒ | k<br>g | kp<br>gb | |
| Afúnnupè | | f | s | ʃ | | | | h |

| | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Arán mú | m | | n | | | | | |
| Aréh án | | | r | | | | | |
| Afẹ̀g bẹ́-ẹnu-pè | | | l | | | | | |
| Aséè sétán | | | | | j | | w | |
| Arán mú asesí lébù | m | ɱ | n | | ɲ | ŋ | ŋm | |

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

A mẹ́nu bà á nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí pé ìró kọ́nsónáǹtì ni ìró tí a pè nígbà tí ìdíwọ́ wà fún èémí ni ibì kan ní òpópónà ajẹmọ́hùn tí a lè lò gẹ́gẹ́ bí apàalà sílébú. A fi kún un pé, èémí àmísóde ni a fi máa ń pe gbogbo iró kọ́nsónáǹtì èdè Yorùbá àyàfi ìró [kp] àti [gb] tí a máa ń lo àpapọ̀ èémí àmísínú àti àmísóde. A tún sàlàyé àwọn àbùdá fún gbígbé kọ́nsónáǹtì jade èyí tí a lò gẹ́gẹ́ bíi àtẹ̀gùn láti sàpèjúwe ìró kọ́nsónáǹtì kọ̀ọ̀kan. A sì gbìyànjú láti fún ìró kọ́nsónáǹtì ní orúkọ ọlọ́rọ̀ ìperí mẹ́ta èyí ti àtẹ kọ́nsónáǹtì ń ṣe afihàn rẹ̀.

## 6.0 ÌDÁNRAWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

1. Fún kọ́nsónáǹtì ní oríkì
2. Pín kọ́nsónáǹtì sí ìsọ̀rí nípa lílo òsùnwọ̀n
3. Fún kọ́nsónáǹtì ní orúkọ ọlọ́rọ̀ ìperí mẹ́ta

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Crysta David (2008). *A Dictionary of Linguistics and Phonetics*. Meldone. Blackwell Publishing

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá 1: Fonẹ́tîkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ìbàdàn. Universal Akada Book Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KÒỌ́ KẸTA

# ÌRÓ FAWẸ́LÌ

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọ já, a wo ọ̀kan lára ẹ̀yà ègé ìró tí i ṣe kọ́nsónáǹtì. Ní bàyìí, a ó wo ìkéjì rẹ̀ tí i ṣe fáwẹ́lì. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó wo oríkì fáwẹ́lì, àwọn àbùdá láti pín fáwẹ́lì Yorùbá, a ó sì dárukọ fáwẹ́lì pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ìperí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, Akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

- Ṣàlàyé ní kíkún nípa fáwẹ́lì èdè Yorùbá
- Tọ́ka sí àwọn àbùdá fáwẹ́lì Yorùbá
- Pín àwọn fáwẹ́lì Yorùbá sí ìsọ̀rí nípa lílo òsùnwọ̀n àbùdá wọn

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

1. Ṣàlàyé ọ̀wọ́ fáwẹ́lì èdè Yorùbá wọ́nyí pẹ̀lú àpẹẹrẹ
i. Fáwẹ́lì àhánupè
 ii. Fáwẹ́lì àyanupè
 iii. Fáwẹ́lì roboto
 iv. Fáwẹ́lì àárín
2. Fi ìyàtọ̀ hàn láàárín fáwẹ́lì aránmúpè àti àìránmúpè
3. Dárúkọ fáwẹ́lì wọ̀nyí: [a], [o], [ã], [ɔ] àti [ɛ]

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Gẹ́gẹ́ bí a ti gùn lé ìlànà fónẹ́tíìkì àti fonọ́lọ́jì láti fún kọ́nsónáǹtì ni oríkì náà ni a ó ṣe láti fún fáwẹ́lì ni oríkì. Bí a bá ṣe báyìí, oríkì tí a lè fún fáwẹ́lì lọ báyìí:

*Fáwẹ́lì ni ìró tí a pè nígbà tí kò sí ìdíwọ́ fún èémí ní ọ̀pọ́pónà ajẹmóhùn*. (Owólabi 2013)

Oríkì fónẹ́tíìkì ni èyí, ṣùgbọ́n bí a bá sọ pé àwọn ìró tí wọ́n siṣẹ́ odo sílébù ni fáwẹ́lì (Crystal 2008) ìlànà fonọ́lọ́jì ni ìyẹn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Kọ́nsónáǹti Aránmú aṣelílébù náà máa ń ṣiṣẹ́ odo sílébù, àmọ́ a ó máa ṣàlàyé ìyẹn ni iwájú.

Àwọn fáwẹ́lì èdè Yorùbá ní ìlànà àkọtọ́ ni wọ̀nyìí:
a e ẹ i o ọ u an ẹn in ọn un

Àwọn fáwẹ́lì èdè Yorùbá ní ìlànà IPA ni wọ̀nyìí:
a e ɛ i o ɔ u ã ĩ ɛ̃ ũ ɔ̃

## 3.1 Àwọn Àbùdá tí a lò gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n láti pín fáwẹ́lì Yorùbá

Gẹ́gẹ́ bí ìgbékalẹ̀ Owólabí (2013:84-88) òsùnwọ̀n mẹ́rin ni ó gbé kalẹ̀: ipò tí àfàsé wà, lílo apá kan ní ara ahọ́n tí ó gbé sí òkè jù lọ nínú ẹnu, lílo bí apá kan ní ara ahọ́n tí ó gbé sí òkè jù lọ ṣe ga tó nínú ẹnu àti ipò tí ètè wà

1. **Ipò tí àfàsé wà**:- Àfàsé lè gbé sókè kí ó dí ọ̀nà èémí sí imú tí èémí yóó sì máa ti ẹnu nìkan jade. Irú fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni à ń pè ní fáwẹ́lì àìránmúpè, àpẹẹrẹ wọn sì ni: [a], [e], [ɛ], [i], [o], [ɔ], [u]
   Àmọ́ tí àfàsé bá wá sílẹ̀ tí èémí sì ń gba ẹnu àti imú jade, irú fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni à ń pè ní, àránmúpè àpẹẹrẹ wọn sì ni:[ã], [ĩ], [ɛ̃], [ũ], [ɔ̃]
2. **Lílo apá kan ní ara ahọ́n tí ó gbé sí òkè jù lọ nínú ẹnu**:- Ibi tí ó ń gbé sókè lára ahọ́n ni iwájú-ahọ́n, àárín-ahọ́n àti ẹ̀yìn-ahọ́n. Èyí pín fáwẹ́lì sí ọ̀wọ́ mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.
   - Fáwẹ́lì Iwájú --- [i], [e], [ɛ], [ĩ], [ɛ̃]
   - Fáwẹ́lì àárín --- [a], [ã]
   - Fáwẹ́lì ẹ̀yìn --- [o], [u], [ũ], [ɔ], [ɔ̃]
3. **Báwo ni apá kan ni ara ahọ́n tí ó gbé sókè jùlọ se ga tó nínú ẹnu?**
   Ipò mẹ́rin ni èyí lè wà: ipò ìhánupè, ipò ìhánudíẹ̀pè, ipò ìyanudíẹ̀pè, àti ìyanupè. Pẹ̀lú ipò wọ̀nyí, a lè pín fáwẹ́lì sí ọ̀wọ́ mẹ́rin:
   - Fáwẹ́lì àhánupè --- [i], [u], [ĩ], [ũ]
   - Fáwẹ́lì àyanupè --- [a], [ã]
   - Fáwẹ́lì àhánudíẹ̀pè --- [e], [o]
   - Fáwẹ́lì àyanudíẹ̀pè --- [ɛ], [ɛ̃]
4. **Ipò tí Ètè wà**:- ipò méjì ni ètè lè wà, kí ó rí pẹrẹsẹ tàbí roboto. Èyí pín fáwẹ́lì sí ọ̀wọ́ méjì:
   - Fáwẹ́lì pẹrẹsẹ --- [i], [e], [ɛ], [a], [ĩ], [ɛ̃]
   - Fáwẹ́lì roboto --- [u], [o], [ɔ], [ũ], [ɔ̃]

Ṣùgbọ́n bí a bá gùn lé àgbékalẹ̀ Bámgbóse (1990) ọ̀nà mẹ́rin tí a lè pín ìró fáwẹ́lì sí nípa àbùdá pípe wọn ni: gíga odidi ahọ́n, gíga iwájú tàbí ẹ̀yìn ahọ́n, ipò ètè àti ipò àfàsé.

**Gíga odidi ahọ́n**: ahọ́n lè súmọ́ òkè ẹnu tàbí kí ó jìnnà sí i gédégédé. Ọ̀nà tí a fi ń mọ èyí ni bí ẹnu bá ṣe là sí. Nígbà tí ahọ́n bá súnmọ́ òkè ẹnu, ẹnu a fẹ́rẹ̀ẹ́ wà ní pídadé, ṣùgbọ́n nígbà tí ahọ́n kò bá lọ sókè rárá, ẹnu a wà ní sísí gbayawu. Ipò mẹ́rin ni gíga ahọ́n:

1. Ipò òkè: nígbà tí ahọ́n bá wà ní ipò òkè, ìró fáwẹ́lì tí a pè ni a mọ̀ sí fáwẹ́lì àhánupè. Àwọn fáwẹ́lì náà ni [i], [u], [ĩ] àti [ũ]
2. Ipò ẹ̀bákè: nígbà tí ahọ́n bá wà ní ipò ẹ̀bákè, ìró fáwẹ́lì tí a bá pè ni a mọ̀ sí fáwẹ́lì ahánudíẹ̀pè. Awọn fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni: [e], [o]

3. Ipò odò: nígbà tí ahọ́n bá wà ní ipò odò, ìró fáwẹ́lì tí a bá pè ni a mọ̀ sí àyanupè. Irú fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni: [a], [ã]
4. Ipò ẹ̀bádò: nígbà tí ahọ́n bá wà ní ipò ẹ̀bádò, iró fáwẹ́lì tí a bá pè ni a mọ̀ sí fáwẹ́lì àyanudíẹ̀pè. Irú fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni [ɛ], [ɔ], [ɛ̃], [ɔ̃]

**Gíga Iwájú tàbí Ẹ̀yin Ahọ́n**: yàtọ̀ sí gíga odidi ahọ́n, iwájú tàbí ẹ̀yìn ahọ́n náà lè ga. Orísìí fáwẹ́lì mẹ́ta ni àbùdá yìí lè fún wa: fáwẹ́lì iwájú, fáwẹ́lì ẹ̀yìn àti fáwẹ́lì àárín.

1. Fáwẹ́lì Iwájú: èyí ni ibi tí iwájú ahọ́n súnmọ́ òkè ẹnu jù nígbà tí a bá ń pe fáwẹ́lì. Àpẹẹrẹ ni [i], [e], [ɛ], [ĩ], [ɛ̃]
2. Fáwẹ̀lì Ẹ̀yìn: èyí ni ibi tí ẹ̀yìn ahọ́n ti súnmọ́ òkè ẹnu jù nígbà tí a ba pe fáwẹ́lì. Àpèèrè ni [o], [ɔ], [u], [ɔ̃], [ũ]
3. Fáwẹ́lì Àárín: èyí ni ibi tí àárín ahọ́n ti súnmọ́ òkè ẹnu jù nígbà tí a bá ń pe fáwẹ́lì. Àwọn náà ni [a], [ã]

**Ipò Ètè**: ipò méjì ni ètè lè wà nígbà tí a bá ń pe ìró fáwẹ́lì: ipò ètè sísù àti ipò ètè fífẹ̀. Nígbà tí a bá su ètè pọ̀ bí ẹni fẹ́ súfèé nígbà tí a bá pe ìró fáwẹ́lì ni ipò ètè sísù. Irú fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni a mọ̀ sí fáwẹ́lì roboto. Àwọn náà ni [o], [ɔ], [u], [ɔ̃], [ũ]. Ṣùgbọ́n nígbà tí a bá fẹ ètè, tí ó wá rí pẹrẹsẹ, ìró fáwẹ́lì tí a bá pè ní ipò ètè yìí ni a mọ̀ sí fáwẹ́lì pẹrẹsẹ. Irú àwọn ìró bẹ́ẹ̀ ni [a], [e], [i], [ɛ], [ã], [ĩ], [ɛ̃]

**Ipò Afàsé**: ipò méjì ni àfàsé lè wà. Ó lè gbéra sókè kí ó dí ọ̀nà tí èémí ń gbà lọ sí imú tí èémí sì ń gba ẹnu jáde. Ìró tí a bá pè ní ipò àfàsé yìí ni a mọ̀ sí fáwẹ́lì àìránmúpè. Irú fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni [a], [e], [ɛ], [i], [o], [ɔ], [i]. Ṣùgbọ́n nígbà tí àfàsé kò bá gbé sókè tí èémí ń gba imú àti ẹnu jáde, irú ìró f'wẹ́lì tí a bá pè ní ipò àfàsé yìí ni a mọ̀ sí fáwẹ́lì aránmúpè. Àwọn fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ ni [ã], [ɛ̃], [ɔ̃], [ĩ], [ũ]

Bí a bá gbé àlàyé Owólabí àti Bámgbósé sí ẹ̀gbẹ̀ ara wọn, a ó ri pé, ohun kan náà ni wọn sọ, orúkọ tí wọ́n fún àlàyé wọn ni ó yàtọ̀.
A lè tún fi àtẹ fáwẹ́lì ṣe ìgékúrú gbogbo àlàyé wà



## 3.2 Dídarúkọ fáwẹ́lì Ọlọ́rọ̀ ìperí mẹ́ta

Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe fún kọ́nsónáǹtì ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá náà la ó ṣe fún fáwẹ́lì. A ó fún wọn ní orúkọ ọlọ́rọ̀ ìpérí mẹ́ta, òsùnwọ̀n tí a ó gùn lé ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

i. Ìtọ́ka sí bí apá kan ni ara ahọ́n tí ó gbé sókè jù lọ se ga tó
ii. Apá kan ni ara ahọ́n tí o gbé sí òkè jù lọ
iii. Ipò tí ètè wà
iv. Fún fáwẹ́lì àránmúpè, a ó fi kún un bẹ́ẹ̀.

Ní báyìí, a ó fún fáwẹ́lì wọ̀nyí ní orúkọ:

[i] fáwẹ́lì àhánupè iwájú pẹrẹsẹ
[e] fáwẹ́lì àhánudíẹ̀pè iwájú pẹrẹsẹ
[ɛ] fáwẹ́lì àyanudíẹ̀pè iwájú pẹrẹsẹ
[a] fáwẹ́lì àyanupè àárín pẹrẹsẹ
[ɔ] fáwẹ́lì àyanudíẹ̀pè ẹ̀yìn roboto
[o]fáwẹ́lì àhánudíẹ̀lì ẹ̀yin roboto
[u] fáwẹ́lì àhánupè ẹ̀yìn roboto
[ĩ] fáwẹ́lì aránmúpè àhánupè iwájú pẹrẹsẹ
[ɛ̃] fáwẹ́lì aránmúpè àyànudípè iwájú pẹrẹsẹ
[ã] fáwẹ́lì aránmúpè àyanupè àárín pẹrẹsẹ
[ɔ̃] fáwẹ́lì aránmúpè àyanudíẹ̀pè ẹ̀yìn roboto
[ũ] fáwẹ́lì aránmúpè àhánupè ẹ̀yìn roboto

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

A ṣàlàyé oríkì fáwẹ́lì, gẹ́gẹ́ bí ìró tí a pè láì sí ìdíwọ́ fún èémí ni ibì kan ní òpópónà ajẹmóhùn. A fi kún pé ìró fàwẹ́lì náà ni a lè lò gẹ́gẹ́ bí odo sílébù. Lẹ́hìn èyí ni a wo àwọn àbùdá tí a lè lò gẹ́gẹ́ bí òsùnwọ̀n láti pín fáwẹ́lì èdè Yorùbá sí ìsọ̀rí. A mẹ́nuba ipò tí àfàsé wà, lílo apá kan ní ara ahọ́n tí ó gbé sí òkè jùlọ nínú ẹnu, bí apá kan ara ahọ́n tí ó gbé sókè ṣe ga tó, àti ipò tí ètè wà. A tún gbìyànjú láti fún fáwẹ́lì kọ̀ọ̀kan ní orúkọ ọlọ́rọ̀ ìperí mẹ́ta.

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

1. Ṣàlàyé ọ̀wọ́ fáwẹ́lì èdè Yorùbá wọ̀nyí pẹ̀lú àpẹẹrẹ
    i. Fáwẹ́lì àhánupè
    ii. Fáwẹ́lì àyanupè
    iii. Fáwẹ́lì roboto
    iv. Fáwẹ́lì àárín
2. Fi ìyàtọ̀ hàn láàárín fáwẹ́lì àránmúpè àti àìránmúpè
3. Dárúkọ fáwẹ́lì wọ̀nyí: [a], [o], [ã], [ɔ] àti [ɛ]

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Bámgbósé Ayọ̀ (1990) Fonọ́lọ́jì àti gírámà Yorùbá. Ibadan. University Press Limited.

Owólabí Kọ́lá (2011) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tîìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KẸRIN

# ÌRÓ OHÙN

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Lẹ́yìn tí a ti wo ìró kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ̀lì, ohùn tí mo rò pé ó tún yẹ kí á wò báyìí ni ìró ohùn. A sàlàyé saájú pé ègé ìró alágbèéká ni ìró ohùn jẹ́, àmì sì ni a fi máa ń sàdàkọ rẹ̀. Nítorí náà, ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí yóó fúnka mọ́ wíwo ìró ohùn yìí àti àwọn ohun tí ó rọ̀ mọ́ ọn. Ìrètí wa ni pé, lópìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, wà á lè ṣàlàyé ìrú ìró ohùn tí ó wà ní èdè Yorùbá

## 2.0 ÈRÒNGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè

- Kí ìró ohùn
- Tọ́ka sí ẹ̀yà ìró ohùn tó wà lédè Yorùbá
- Fi àmì sórí ọ̀rọ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ

## 2.1 Ìdánrawò Ibẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

1. Fún ìró ohùn ní oríkì gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ
2. Ṣe àlàyé ẹ̀yà ìró ohùn tí ó wà ní èdè Yorùbá
3. Fi àmì sí orí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí:

   Igba time
   Igba calabash
   Igba locust beans
   Igba two hundred
   Igba mounting rope

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ọ̀kan lára èdè olóhùn ni èdè Yorùbá. Owólabí (2013:17) ní
*ìró ohùn ni lílọ sókè tàbí yíyọ̀ rókè, yíyọ̀ rodò ohùn ènìyàn nígbà tí a bá ń fọ̀*

Èyí túmọ̀ sí pé nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀, ohùn wa a máa lọ sókè tàbí ki ó wá sí ìsàlẹ̀ láti fa ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ tàbí ìpèdè tí a ń sọ yọ. Oríkì tí Owólabí fún ìró ohùn jẹ́ kí a mọ̀ pé ìró ohùn yìí pín sí méjì: ìró ohùn geere àti ìró ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́.

## 3.1 Ìró Ohùn Geere

Èyí ni ìró tí kò ní ẹ̀yọ́ kankan rárá. Ìyẹn ni pé ohùn ènìyàn kò yọ́ láti ipò ìró ohùn kan sí òmíràn (wo Owólabí 2013:17). Itùmọ̀ èyí ni pé, ní gbígbé ìró ohùn yìí jáde, ipò kan náà ni ìró ohùn yìí máa ń dúró sí. Mẹ́ta ni ìrú ìró ohùn geere yìí:
Ìró ohùn òkè
Ìró ohùn ààrin
Ìró ohùn ìsàlẹ̀

### 3.1.1 Ìró ohùn òkè

A máa ń pe ìró yìí nípa gbígbé ohùn wa sókè. Àmì tí a máa ń lò fún ìró yìí ni [ ´] nínú àwọn ọ̀rọ̀ bíi:

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| wá | come | rárá | no | bíntín | small |
| sá | run | dádé | wear the crown | tíntín | small |
| ké | shout | wálé | come home | pínnísín | small |
| lé | chase | sáré | run | kínkín | small |

A lè lo ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ òkè yìí nínú gbólóhùn báyìí:
Ọmọ náà **wá** ilé wa lánàá

Mo ń **sá** fún Ọlọ́pàá nítorí owó orí
Ṣe ni ọmọ ń **ké** tagbára tagbára
Wọn **lé** ọ̀daràn náà títí ọwọ́ fi bà á
Ó ṣo pé **rárá**
Ó **dádé** idẹ

### 3.1.2 Ìró Ohùn ààrin

Èyí ni ìró tí a pè nígbà tí ohùn wa wà ní agbede méjì ohùn òkè àti ohùn ìsàlẹ̀. Àwọn onímọ̀ ni kí a má lò àmì rẹ̀ sí orí ọ̀rọ̀ àyàfi ní ìgbà tí ọ̀rọ̀ náà bá fẹ́ mú [2]pánna dáni. Àmi tí a máa ń lò fun ni (−) nínú àwọn ọ̀rọ̀ bíi:

| | | | |
|---|---|---|---|
| ra | rub | aya | wife |
| ya | tear | ọkọ | husband |
| le | strong/powerful | ọmọ | child |

A lè lo àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí nínú gbólóhùn bí i:
Adé fi epo **ra** ara
Ìdòwú **ya** aṣọ ìyá rẹ̀
**Ọmọ** náà **le**!

**Aya** rere sọ̀wọ́n
Ọkọ rẹ̀ ra ọ̀kọ̀ tuntun

### 3.1.3 Ìró Ohùn Ìsàlẹ̀

Èyí ni ìró tí a pè nígbà tí ohùn wa wà ní ìsàlẹ̀. Àmì tí a máa ń lò fún ìró yìí ni ( ` ) nínú àwọn ọ̀rọ̀ bí i:

| | | | |
|---|---|---|---|
| sùn | sleep | àrà | wonder |
| tà | sell/make profit | gbèsè | debt |
| rà | buy | àgbà | |
| fà | pull | kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ | fox |

A lè lo àwọn ọ̀rọ̀ náà ninú gbólóhùn báyìí:
Ọmọ mi ti **sùn**
Mo **tà** á ni owó ńlá
Ìbàdàn ni mo ti **rà** á
Wọ́n sà ń **fà** á ni
Ó máa ń fi ọ̀kọ̀ dá **àrà**
**Gbèsè** ò dára fún ọmọlúàbí
Bí ọmọdé ò kú **àgbà** ní dà
**Kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀** jẹ ẹ́ ni adìẹ

## 3.2 Ohun Ẹlẹ́yọ̀ọ́

Èyí ni ìró ohùn tí kò dúró sí ojú kan tàbí ipò kan náà. Dípò bẹ́ẹ̀, ní gbígbé ìró ohùn yìí jáde, ṣe ni ohùn ènìyàn máa ń yọ́ láti ipò rẹ̀ fún ìró kan lọ sí ipò ìró mìíràn (wo Owólabí 2013:18). Ní inú èdè Yorùbá, méjì ni irú àwọn ìró yìí: ìró ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ ròkè àti ìró ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ rodò.

### 3.2.1 Ìró Ohùn Ẹlẹ́yọ̀ọ́ Rókè

Èyí ni gbígbé ohùn wà láti ipò rẹ̀ tí i ṣe ìsàlẹ̀ lọ sí ipò mìíràn tí i ṣe òkè lài dánu dúró. Àmì tí a máa ń lò ni (ˇ) nínú àwọn ọ̀rọ̀ bí i:
yǐ
Níkẹ̌

### 3.2.2 Ìró Ohùn Ẹlẹ́yọ̀ọ́ Rodò

Ìdàkejì ìró ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ rókè ni eléyìí jẹ́ nígbà tí ènìyàn gbé ohùn ní ipò òkè lọ sí ipò ìsàlẹ̀ láì jẹ́ pé a dánu dúró. Àmì tí a ń lò fún eléyìí ni (ˆ) nínú ọ̀rọ̀ bí i:
bệ

### 3.2.3 Àtúnyẹ̀wò ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́

Kìí ṣe gbogbo àwọn onímọ̀ fonọ́lọ́jì ni ó fara mọ́ ọn pé ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ wà lédè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí a ti ṣàlàyé lókè. Bámgbóṣe (1990:41-42) ní bí a bá

gùnlé alàyé ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ yẹn, a jẹ́ pé a máa ní ju ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ ròkè àti ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ rodò lọ. Ìdí tí ó fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé gbogbo ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ kìí yọ bákan náà. Ó fún wa ní àpẹẹrẹ bí i **òórùn** tí ó yọ láti ìsàlẹ̀ lọ sí òkè àti **eérú** tí ó yọ láti àárín lọ sí òkè, bẹ́ẹ̀ sì ni ẹlẹ́yọ̀ọ́ rókè ni a ó pe àpẹẹrẹ méjéèjì bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé wọ́n ya ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ bí a ṣe rí i.

Bámgbóṣé tún lo ohùn ìsàlẹ̀ amòòkùn gẹ́gẹ́ bí àwíjàre láti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé a kò nílò ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ ní èdè Yorùbá. Ó fún wa ni àpẹẹrẹ

apá àpá

a ó ṣe àkíyèsí pé ohùn òkè ni ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ méjéèjì bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé gíga ìró ohùn òkè náà kìí ṣe ọ̀kan-un. Bí a bá wá so *oní* mọ́ àwọn méjéèjì, a ó ní:

oní-apá oní-àpá

bí a bá wá pa fáwẹ́lì iwájú apá àti àpá jẹ, abájáde rẹ̀ yóó fún wa ní

alápá alápa

báwo wa ni a ṣe fẹ́ mọ ìyàtọ̀ láàrin àwọn méjéèjì? Bámgbóṣé ṣàlàyé pé ohùn ìsàlẹ̀ tí ó wà lórí [a] ti àpá ti a pa jẹ kò lọ rárá. Ṣe ni ó fara sin, tí ó sì tún ń tọ́ka dídún ohùn bí ti àtẹ̀yìnwá. Ohùn tí ó fara sin yìí ni a mọ̀ sí ohùn ìsàlẹ̀ àmòòkùn. Ó wá fi ohùn ìsàlẹ̀ amòòkùn hàn báyìí

oní apá -> alápá
oní àpá -> alá`pá

ohùn ìsàlẹ̀ tí kò dúró sórí sílébù kankan ni ó dúró fún ohùn ìsàlẹ̀ amòòkùn. Nítorí náà oní àpá -> alápàá nitorí pé, kò sí ohùn ẹlẹ́yòóròkè nínú èdè Yorùbá àyàfi nínú irú ẹ̀hun báyìí.

Bámgbóṣé wá gúnlẹ̀ pé, ìwádìí òdé òní lórí èdè Yorùbá fi yé ni pé, a ò nílò ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ rárá. Ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ àti ohun geere ni pé ohùn geere wà lórí sílébù ẹyọ kan, bẹ́ẹ̀ ni ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ wà lórí sílébù méjì. A lè fi àwọn ọ̀rọ̀ yìí ṣe àpẹẹrẹ erú, eérú; ògún, oògùn, níkẹ̌, níkẹ̀ẹ́, yǐ, yìí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (wo Bamgboṣe 1990:42)

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNISÓKÍ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti ṣàlàyé ìró ohùn èdè Yorùbá. A mẹ́nu bà á pé ọ̀nà méjì ni a lè pín ìró ohùn sí: ìró ohùn geere àti ẹlẹ́yọ̀ọ́. A fi kún un pé ìró ohùn geere pín sí mẹ́ta: ìró ohùn òkè, ìró ohùn àarin àti ìró ohùn ìsàlẹ̀ tí a sì fi àpẹẹrẹ gbe ọ̀rọ̀ wa lẹ́sẹ̀. A tún ni ìró ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ náà pín sí méjì, àwọn ni ìró ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ́ ròkè àti ẹlẹ́yọ̀ọ́ rodò.

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ wọ̀nyí:

1. Fún ìró ohùn ní oríkì gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ
2. Ṣe àlàyé ẹ̀yà ìró ohùn tí ó wà ní èdè Yorùbá
3. Fi àmì sí orí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí:

Igba time
Igba calabash
Igba locust beans
Igba two hundred
Igba mounting rope

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Bamgbose Ayo (1990) *Fonolọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan, University Press Limited

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tîìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KARÙN UN

# ÌRÓ AṢÈYÀTỌ̀

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Nínú àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa àtẹ̀yìn wá, a ń sọ̀rọ̀ nípa ìró, a ti sọ̀rọ̀ nípa kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì, a tún ti sọ̀rọ̀ nípa ìró ohùn ṣùgbọ́n a ò tîì mẹ́nu ba àwọn ìró aṣèyàtọ̀. Má gbàgbé pé nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá a kàn sọ̀rọ̀ nípa àwọn ìró yìí ni, a ò mẹ́nu ba ìyàtọ̀ tí ó wà láarin fóònù àti fóníîmù. Bẹ́ẹ̀ ni a ò tîì mẹ́nu ba ìfọ́nká tí a máa ń fi ṣe àwárí fóníîmè. Àfojúsùn wa ni pé ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè ṣe àwárí fóníîmù àti àwọn ẹ̀dà wọn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

## 2.0 ERÒŇGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, wà á lè sọ ìyàtọ̀ fóónù àti fóníîmù. Ó yẹ kí o tún lè sọ fún wa bí a ṣe lè wá ìró aṣèyàtọ̀ rí nínú èdè Yorùbá.

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

- Ṣe àlàyé kíkún lórí ìfọ́nká aṣèyàtọ̀.
- Kín ni tóníîmù?

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ saájú, nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀, ìró ni a máa ń pè. Ojú tí a fi ń wo ìró yìí yàtọ̀ sí ara wọn. Nígbà tí onímọ̀ Fónẹ́tíìkì máa ń fúnka mọ́ bí a ṣe ń pe ìró kọ̀ọ̀kan. Onímọ̀ Fonọ́lọ́jì máa ń wo ìbátan tí ó wà láarin ìró kọ̀ọ̀kan. Bí àpẹẹrẹ, ìró wo ni ó fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ nínú àwọn ọ̀rọ̀ ìsàlẹ̀ yìí?:

sá
sẹ́
sú

A ó ṣe àkíyèsí pé ìró fáwẹ́lì ni ó fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ nínú àwọn ọ̀rọ̀ òkè yìí. Fáwẹ́lì [á], [ẹ́], [ú] ni ó fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìró kọ́nsónáǹtì àti ìró ohùn kán náà ni gbogbo wọn ní. Nítorí náà, àwọn ìró fáwẹ́lì yẹn ni ìró aṣèyàtọ̀.

Ìró aṣèyàtọ̀ ni ó ṣe pàtàkì nínú èdè Yorùbá, àwọn tí kò ṣe pàtàkì ni ìró àìṣèyàtọ̀/aláìṣèyàtọ̀ (ẹ̀dà fóníîmù). Kín wá ni Ìró Aṣeyàtọ̀? Nínú ìmọ̀ Ẹ̀dá-Èdè, ohùn tí a ń pe gbogbo ìró tí à ń pè jáde ni nígbà tí a bá ń fọ̀ ni a mọ̀ sí Fóònù. Ṣùgbọ́n kìí ṣe gbogbo fóòù ni ó máa ń mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ bá ọ̀rọ̀. Àwọn ìró tí ó máa ń fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ ni a mọ̀ sí ìró aṣèyàtọ̀. Owólabí (2013:97) ṣàlàyé pé àwọn fóònù kan jẹ ìró aṣèyàtọ̀ nígbà tí àwọn fóònù

mìíràn náà wà tí wọ́n jẹ́ ìró aláìṣeyàtọ̀. Fóònù tí ó máa fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ láàárín ọ̀rọ̀ kan sí òmíràn ni a mọ̀ sí ìró aṣèyàyọ̀ gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn lókè. Àmọ́, àwọn fóònù tí kìí fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ láàárín ọ̀rọ̀ kan sí òmíràn ni a mọ̀ sí ìró aláìṣeyàtọ̀. Láti ṣe ìtúpalẹ̀ èdè kan onímọ̀ ẹ̀dá-èdè gbọ́dọ̀ ṣe àdàkọ fóònù inú èdè ọ̀hún lẹ́yìn náà ni yóó wá ṣe akitiyan láti wá àwọn ìró aṣèyàtọ àti ìró aláìṣeyàtọ̀ rí.

## 3.1 Síṣe àwárí ìró aṣèyàtọ̀

Láti le fi hàn pé ìró kan jẹ́ aṣèyàtọ̀ tàbí aláìṣèyàtọ̀, a ó yẹ ìfọ́nká wò (distribution). Orísìí ìfọ́nká méjì ni ó wà. Ìfọ́nká Aṣèyàtọ̀ àti Àìṣèyàtọ̀. Ìfọ́nká tí à ń wí yìí dúró lórí ipò tí ìró bá ti jẹyọ, bóyá sí iwájú ni, ẹ̀yìn tàbí àárín.

### 3.1.1 Ìfọ́nká Aṣèyàtọ̀

Bí ìró méjì bá jẹyọ ní sàkání kan náà tí ó sì jẹ́ pé bí a bá fi ọ̀kan rọ́pò èkejì, tí irú ìrọ́pò bẹ́ẹ̀ mú ìyípadà bá ìtumọ̀ ọ̀rọ̀, nínú ìmọ̀ ẹ̀dá èdè tí a tún pè ní Lìngúísíìkì, a máa ń sọ pé àwọn ìró bẹ́ẹ̀ ṣe ìyàtọ̀. Bí àpẹẹrẹ wo ìró [b], [d]; [m], [n]; [a], [ɔ] nínú ọ̀rọ̀ ìsàlẹ̀ yìí

i. bɛ àti dɛ
ii. iñú àti im̃ú
iii. rɛ́ àti rɔ́

Wà á sàkíyèsí pé nínú (i) ìró [b] àti [d] ni wọ́n fa ìyàtọ̀ nínú ìtumọ̀ bí a bá fi ọ̀kan rọ́pò èkejì. Ní sàkáni wo ni wọ́n ti jẹyọ? wà á rí i pé iwájú ni wọ́n wà. Ní ti (ii) àárín ni ìró [n] & [m] wà, àwọn ni wọ́n sì mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ bá ọ̀rọ̀ náà bí a bá lo ọkan nínú wọ́n láti rọ́pò èkèjì. Ìró [ɛ] & [ɔ] tí ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ (iii) ni ó mú ìyàtọ̀ bá ìtumọ̀ bí a bá ṣe ìrọ́pò gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe sọ sáajú. Sàkání tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìró yìí tí ó mú ìtumọ̀ bá àwọn ọ̀rọ̀ òkè yẹn ni à ń pè ní ìfọ́nka aṣèyàtọ̀, nítorí náà, ìró aṣètàtọ̀ ni wọ́n.

### 3.1.2 Ìfọ́nká Aláìṣèyàtọ̀

Bí ìró kan bá yọ ní sàkání ìró mìíràn ṣùgbọ́n tí kò mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ dáni, sàkání tí wọ́n ti jẹyọ ni ìfọ́nká aláìṣèyàtọ̀, nítorí náà, wọ́n jẹ́ ìró aláìṣèyàtọ̀. Bí àpẹẹrẹ, [l] àti [n] jẹ́ ìró aláìṣèyàtọ̀. Fún ìdí èyí àwọn méjéèjì ni ẹ̀dà fún /l/




Bí àpẹẹrẹ wo ọ̀rọ̀ bí i

Oní +ilé = onílé
Oní + aṣọ = aláṣọ

Wà á kíyèsí pé sàkání tí kọ́nsónáǹtì [n] àti [l] ti jẹyọ jọ ọ̀kan-ùn ṣùgbọ́n kìí ṣe ọ̀kan náà. Ní ìgbà tí kọ́nsónáǹtì [n] jẹyọ ní agbègbè ìránmú, kọ́nsónáǹtì [l] jẹyọ ní agbègbè àìránmú, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ipò kan náà ni wọ́n ti jẹyọ. Ìyẹn já sí pé ìfọ́nká aláìṣèyàtọ̀ ní àwọn ìró méjéèjì ti jẹyọ nítorí náà ìró aláìṣèyàtọ̀ ni wọ́n. Wọn kìí ṣe fóníìmù, ẹ̀dà fóníìmù ni wọ́n.
Kín ni fóníìmù?

## 3.2 Fóníìmù

Nínú èdè tó wù kó jẹ́, àwọn ìró tí wọn bá lè fi ìyàtọ̀ láàárín ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ kan tàbí òmíràn hàn tàbí tí wọ́n bá lè mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ bá ọ̀rọ̀ ní sàkání kan náà, àwọn irú ìró bẹ́ẹ̀ ni a máa ń pè ní fóníìmù. Irú àdàkọ ti a sì máa ń ṣe fún àwọn fóníìmù ni èyí tí a mọ̀ sí àdàkọ fóníìmù.

Báwo ni a ṣe lè wá fóníìmù rí nínú èdè kan? Ọ̀nà kan tí a fi lè wá fóníìmù rí nínú èdè kan ni nípa wíwá àwọn àpẹẹrẹ wúnrẹ̀n méjì tí ìró wọn jẹ́ bákannáà, àyàfi ẹyọ ìró kan ṣoṣo tí yóó yàtọ̀. Àwọn wúnrẹ̀n méjì tí wọn bá fi ìró kan ṣoṣo yàtọ̀ sí ara wọn báyìí ni à ń pè ni ***èjì-ọ̀kán-yà*** (minimal pairs), fún àpẹẹrẹ wo àwọn àtòjọ ọ̀rọ̀ ìsàlẹ̀ yìí

| | | |
|---|---|---|
| ètè | ɛ̀tɛ̀ | ɛ̀tɛ́ |
| èdè | ɛ̀fɛ̀ | ɛ̀sɛ́ |
| èkpè | ɛ̀bɛ̀ | ɛ̀kpɛ́ |

Àwọn ìró wo ni fóníìmù nínú àwọn ọ̀rọ̀ òkè yìí?
Kín ni ó sì fà á?

Ìró /t/, /d/, /kp/, /b/, /f/, àti /s/ jẹ́ fóníìmù. A ó ri pé ìró [t], [d], àti [kp] ni ó mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ bá *ètè, èdè*, àti *èkpè*. A jẹ́ pé fóníìmù ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni /t/, /d/, àti /kp/ jẹ́. Bẹ́ẹ̀ náà ni [t], [f] àti [b] jẹ́ nínú àpẹẹrẹ ɛ̀tɛ̀, ɛ̀fɛ̀, *àti* ɛ̀bɛ̀. Fóníìmù ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni /t/, /f/. /b/ nítorí pé àwọn ni wọ́n fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ nínú àpẹẹrẹ náà. Ẹ̀wẹ̀, bí a bá wo àpẹẹrẹ ɛ̀tɛ́, ɛ̀sɛ́ àti ɛ̀kpɛ́, ìró [t], [s] àti [kp] ni ó fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀, láìsí àní àní, fóníìmù ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni /t/, /s/ àti /kp/ nítorí pé àwọn ni wọ́n mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ bá àwọn ọ̀rọ̀ òkè yẹn.
Jẹ́ kí á tún wo àpẹẹrẹ mìíràn:

| | |
|---|---|
| dá | (dá owó) |
| dé | (dé ọbẹ̀) |
| dí | (dí garawa) |

dú (dú adìrẹ)
dó (tẹ ìlú dó)

A ó rí i pé, àwọn ìró /á/, /é/, /í/, /ú/, àti /ó/ ni ó fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀. Nítorí náà fóníìmù ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n.
Tún wo àpẹẹrẹ yìí

gbá
gbà
gba

Kín ni ó fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ òkè yìí?
Ohùn, àbí?
A jẹ́ pé ohun náà lè fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀, èyí já sí pé àwọn ohùn náà jẹ́ fóníìmù ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.

## 3.3 Fóníìmù Kọ́nsónáǹtì

Fóníìmù Kọ́nsónáǹtì ni àwọn fóníìmù tí wọ́n jẹ́ kọ́nsónáǹtì. Ìyẹn ni pé, àwọn kọ́nsónáǹtì tí wọ́n lè mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ bá ọ̀rọ̀ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣàlàyé lókè. Owólabí (2013:108) sọ pé, kò sí fóníìmù tí kì í ní ẹ̀dà-fóníìmù tirẹ̀. Òmíràn lè ní ẹ̀dà-fóníìmù kan ṣoṣo péré, òmíràn sì lè ní ju ẹ̀dà kan lọ. Nínú èdè Yorùbá, bí fóníìmù kan bá ní ju ẹ̀dà-fóníìmù kan lọ, àwọn ẹ̀dà-fóníìmù bẹ́ẹ̀ a máa wà ní ìfọ́nká aláìṣeyàtọ̀. Ní báyìí àwọn fóníìmù tí wọ́n jẹ́ kọ́nsónáǹtì èdè Yorùbá ni ìwọ̀nyí: /b/, /t/, /d/, /|/, /k/, /g/, /kp/, /gb/, /f/, /s/, /Σ/, /h/, /m/, /r/, /l/, /j/, /w/.

Kọ́nsónáǹtì [l] àti [n] jẹ́ ẹ̀dà fóníìmù kan náà. Ìdí ni pé wọ́n jẹyọ ni ìfọ́nká aláìṣèyàtọ̀ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe fi hàn saájú tí a ó tún fi hàn báyìí fún ìtẹnumọ́.

oní + ilé = onílé
oní + asọ = alásọ

ìró [n] jẹyọ ní sàkání ìránmú nígbà tí ìró [l] lè jẹyọ ní ipò mìíràn. Nítorí náà ẹ̀dà fóníìmù ni ìró [n] àti ìró [l] jẹ́. Ẹ̀dà fóníìmù wo wá ni wọ́n jẹ́? Wọ́n jẹ́ ẹ̀dà fóníìmù /l/. Àlàyé ni pé àgbègbè ìránmú nìkàn ni ìró [n] tilè jẹyọ. A jẹ́ pé bí ìró [l] bá ti jẹyọ ní sàkání ìránmú yóó yí padà sí ẹ̀dà rẹ́ tí ṣe ìró [n].

Ó yẹ kí a fi kún un pé bẹ́ẹ̀ kọ ni ọ̀rọ̀ rí nínú àwon ẹ̀ka èdè Yorùbá kan o. Àpẹẹrẹ ni ẹ̀kà èdè Òǹdó. Dípò

oní + owó = olówó

Ẹ̀ka èdè Òǹdó yóó sọ pé **onówó**. A jẹ́ pé fóníìmù ni /n/ jẹ́ nínú irú ẹ̀ka èdè bẹ́ẹ̀.

Àpẹẹrẹ ẹ̀dà fóníìmù mìíràn ni ọ̀rọ̀ ìsàlẹ̀ yìí fi hàn wá

wọ́n wọ́

tí a bá ṣe àdàkọ ọ̀rọ̀ òkè yìí yóó fi ìyàtọ̀ wọn hàn dáadáa
 w̃ɔ̃ wɔ́

kí ni o sàkíyèsí nípa [w] méjéèjì?
ọ̀kan ní ìránmú nígbà tí èkejì kò ní. Ṣùgbọ́n oun gan tí ó fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ ni fáwẹ́lì aránmúpè àti àìránmúpè. Nítorí náà, ìfọ́nká aláìṣèyàtọ̀ ni [w] méjééjì ti jẹyọ wọ́n sì jẹ́ ẹ̀dà fóníìmù.

A tún lè fi fóníìmù kọ́nsónáǹtì àti ẹ̀dà wọn hàn láti inú àtẹ yìí báyìí







## 3.4 Fóníîmù Fáwẹ́lì

Àwọn fóníìmù fáwẹ́lì èdè Yorùbá ni ìwọ̀nyí:

**Fóníîmù fáwẹ̀lì àìránmúpè**
 / i /, / e /, / E /, / a /, / □ /, / o /, / u /

**Fóníîmù fáwẹ̀lì àránmúpè**
 / ĩ /, / Ẽ /, / □̃ /, / ũ /
Jẹ́ kí a wo ìpèdè yìí:
 [ìbàdã] àti [ìbàdɔ̃]
 [ahã] àti [ahɔ̃]

Àkíyèsí wa ni pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyàtọ̀ wà nínú pípe ìbàdàn síbẹ̀ kò mú ìyàtọ̀ ìtumọ̀ dán, nítorí náà, ìfọ́nka aláìṣèyàtọ̀ ni [ɔ̃] ati [ã] wà, wọ́n sì jẹ́ ẹ̀dà fóníîmu kan. Fóníìmù tí wọ́n jẹ́ ẹ̀dà rẹ̀ bi /ɔ̃/. A sì lè fi ẹ̀dà náà hàn báyìí:




## 3.5 Fóníîmù Ohùn tàbí Tóníîmù

Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ pé ohùn mẹ́ta ni ó máa ń fa ìyàtọ̀ ìtumọ̀ nínú èdè Yorùbá, a jẹ́ pé tóníîmù mẹ́ta náà ni ó wà nínú èdè Yorùbá. Wó àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

| | | |
|---|---|---|
| gbá | sún | wá |
| gbà | sùn | wà |
| gba | sun | wa |

a jẹ́ pé àwọn tóníîmù Yorùbá kò ní ẹ̀dà.

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti mẹ́nu bà á pé ìró aṣèyàtọ̀ ti a tún mọ̀ sí fóníìmù ni a máa ń sàwárí rẹ̀ nípa ìfọ́nká. A kò sàìmẹ́nuba àwọn ẹ̀dà fóníìmù kọ̀ọ̀kan, a wo fóníìmù kọ́nsónáǹtì, fóníìmù fáwẹ́lì àti fóníìmù ohun tí a tùn lè pè ní tóníìmù. Ìfọ́nka méjì ni a wò: ìfọ́nká aṣèyàtọ̀ àti ìfọ́nká aláìṣèyàtọ̀. A sì máa ń sábà wò ó nínú àwọn ọ̀rọ̀ èjì-ọ̀kanyà.

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

1. Ṣe àlàyé kíkún lórí ìfọ́nká aṣèyàtọ̀.
2. Kín ni tóníìmù?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tîìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KẸFÀ

# DÍDA ÀWỌN ÌRÓ KỌ

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá, a mẹ́nu ba dída ìró kọ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a ò fúnka mọ́ ọn rárá. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ó ti ṣe àfihàn dídá fóònù àti fóníìmù kọ̀. A ó mẹ́nu bá ìlànà àdàkọ méjì tí ó wà àti ohun tí ó ya àwọn méjéèjì sọ́tọ̀. Kìí kàn ṣe ìró tí a ti mẹ́nu bà sáájú nìkan ni a ó wò, a ó wo àwọn àmì mìíràn tí a máa ń lò nígbà tí a bá ń da ìró kọ pàápàá nípa ìlànà àkọtọ́ àti ìlànà IPA.

## 2.0 ÈRÒNGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìrètí wa ni pé, wà á lè sàlàyé bí a ṣè lè da ìró kọ pẹ̀lú àwọn ìlànà tí a máa ń tẹ̀lé láti da àwọn ìró kọ.

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

- Àwọn àmì wo ni a máa ń lò nínú arokò ìlànà akọ́tọ́ tí a kìí lò nínú ìlànà IPA
- Àwọn àmì tí a máa ń lò nínú ìlànà IPA fún ìdánudúró àti ìdánudúródìẹ̀ ni ………………. àti ………………..
- Níní ìlànà ………………………… ni a ti máa ń lo lẹ́tà ńlá láti bẹ̀rẹ̀ gbólóhùn.

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Nígbà tí a bá ń sọ̀ro̩ tàbí ṣafọ̀. Ìró (ìfọ̀) ni a máa ń gbọ́. Ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ nígbà tí a bá ń kàwé. Bí a bá ń kàwé, àmì tí òǹkọ̀wé lò bí àrokò ni a ń fojú rí tí afọ̀ òǹkọ̀wé á sì yé òǹkàwé. Fún ìdí èyí, ìlànà méjì ni ó wà tí a fi máa ń da ìró kọ:

i. Ìlànà àkọtọ́
ii. Ìlànà Ìdàkọ

Awọn elédè ni ó máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ àkọtọ́ èdè wọn, àwọn tí ó bá sì gbọ́ èdè yẹn nìkan ni ó lè ka ohun tí a bá fi àkọtọ́ èdè náà kọ ṣùgbọ́n lílo àrokò (bí àpẹẹrẹ lẹ́tà àti àmì) tí ẹnu àwọn onímọ̀ Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì ti kò lé lórí fún kíkọ àwọn ìró inú gbogbo èdè àgbáyé sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ ni ìlànà ìdàkọ IPA (International Phonetic Alphabet).

Àrokò inú ìlànà akọ́tọ́: b d f g gb h j k l m n p r s ṣ t w y
a e ẹ i o ọ u an ẹn in ọn un
Àrokò inú ìlànà ìdàkọ IPA: b d f g gb h dʒ k l m n kp r s ʃ t w j
a e ɛ i o ɔ u ã ɛ̃ ĩ ɔ̃ ũ
àmì "˜ " ń fi ìránmú hàn nínú ìlànà ìdàkọ IPA.

## 3.1 Àǹfààní ṣíṣe àpèjúwe ìró èdè Yorùbá ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ìdàkọ, yàtoọ̀ sí ìlànà àkọ́tọ́

Owólabi (2013) ṣàlàyé àwọn àǹfààní ṣíṣe àpèjúwe ìró èdè Yorùbá pẹ̀lú ìlànà ìdàkọ. Ó sàlàyé pé, àrokò inú ìlànà àkọ́tọ́ kò tó fún fífi gbogbo àwọn ìró tí a lè gbé jáde nínú èdè Yorùbá hàn. Ní ìdà kejì ẹ̀wẹ̀, àrokò inú ìlànà ìdàkọ kógo já fún ṣíṣe èyí. Láti kín àkíyèsí tí Owólabi ṣe yìí lẹ́yìn, ó fi àwọn gbólóhùn wọ̀nyí ṣe àpẹẹrẹ:

(i) ó wọ́n
(ii) ó wọ́

Tí a bá wo gbólóhùn méjéèjì dáadáa, a ó sàkíyèsí pé ìyàtọ̀ wà nínú bí a ṣe pe kọ́ńsónáǹtì 'w' ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì nínú gbólóhùn (i) yàtọ̀ sí bí a ṣe pè é ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì nínú gbólóhùn (ii). Ìyàtọ̀ náà sì ní pé a ránmú pe 'w' ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì nínú gbólóhùn (i), ṣùgbọ́n a kò ránmú pè é ni ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì nínú gbólóhùn (ii). Ìlànà àkọtọ́ kò fi ìyàtọ̀ tí a tọ́ka sí yìí hàn rárá nítorí pé lẹ́tà 'w' kan ṣoṣo ni ìlànà náà gbà wá láyè láti lò fún kọ́ńsónáǹtì 'w' *(èyí tí a ránmú pè)* ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì nínú gbólóhùn (i) àti kọ́ńsónáǹtì 'w' *(tí a kò ránmú pè)* ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì nínú gbólóhùn (ii). Ó fi kún un pé, a gbọdọ̀ fi ìyàtọ̀ hàn nípa lílo àrokò tí yóò fi ìránmú hàn fún pípe kọ́ńsónáǹtì 'w' ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì nínú gbólóhùn (i) àti àrokò tí kò ní fi ìránmú hàn fún pípe kọ́ńsónáǹtì 'w' ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ kejì nínú gbólóhùn (ii) báyìí:

[w̃] (fún pípe kọ́ńsónáǹt 'w' nínú gbólóhùn (i) )
[w] (fún pípe kọ́ńsónáǹt 'w' nínú gbólóhùn (ii) )

Lọ́nà kẹ́ta, lílo àrokò inú ìlànà ìdàkọ fún ṣíṣe àpèjúwe àwọn ìró èdè Yorùbá tàbí fún kíkọ wọ́n sílẹ̀ yóò jẹ́ kí àwọn ìró náà ṣeé pè gẹ́gẹ́ bí ó ṣe tọ́ àti bí ó ṣe yẹ, èyí tí yóò sì mú kí èdè Yorùbá rọrùn láti kọ fún ẹni tí Yorùbá kì í ṣe èdè abínibí rẹ̀. Ìdí ni pé àwọn àrokò inú ìlànà ìdàkọ máa ń fi bí a ṣe lè pe ìró inú èdè hàn ní pàtó, láìsí pọ́n-na rárá.

Ìlànà yìí yóò mú kí ẹ̀kọ́ nípa àwọn ìró èdè Yorùbá wà ní ìbámu pẹ̀lú ẹ̀kọ́ nípa àwọn ìró èdè àgbáyé tó kù nítorí pé gbogbo èdè ní àwọn àrokò inú ìlànà ìdàkọ wà fún, ṣùgbọ́n àwọn àrokò inú ìlànà àkọ́tọ́ kò wà fún gbogbo èdè àgbáyé.

## 3.2 Iyàtọ̀ Láàárín Ìlànà Àkọtọ́ àti Ìlànà Ìdàkọ

Owólabí (2013) ṣàlàyé àwọn ìyàtọ̀ tí ó wà láarin àṣà dída ìró kọ ní ìlànà àkọtọ́ àti ìlànà ìdàkọ báyìí:

1. Ṣíṣe ìfàmìsí: Àwọn àmì kan wà tí a máa ń lò nínú àkọtọ́ tí a kìí lò nínú ìlànà Ìdàkọ, bí àpẹẹrẹ, kọmá (**,**); àdàmọ̀dì-kólọ̀ọ̀nù (**;**); kólọ̀ọ̀nù (**:**); àmì ìbéèrè (**?**); àmì ìyanu (**!**); àmì ìdánudúró (**.**).

   Àwọn àmì tí a ń sábà máa ń lò nínú ìdàkọ ni ìwọ̀nyí:
   I fún ìdánudúró díẹ̀ (dípò kọmá)

   II fún ìdánudúró pípẹ́(dípò àdàmọ̀dì kólọ̀ọ̀nù, kólọ̀ọ̀nù, àmì ìbéèrè, àmì
   ìyanu àti àmì ìdanudúró)
2. Àwọn àmì ìfàmìsí mìíràn tí a máa ń lò nínú àkọtọ́ tí kò sí nínú ìdàkọ ni:
   kọmá olókè (**’**) ; àmì ayọlò (**‘’**); àmì afò (tàbí àmì fífò) (**…**); àkámọ́ [afìwọ̀fún-hàn] (**( )**).
3. lílo lẹ́tà ńlá ní ìbẹ̀rẹ̀ orúkọ, ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn abbl tí a máa ń tẹ̀lé nínú àkọtọ́ kò sí nínú ìdàkọ.

## 3.3 Ẹ̀yà Àdàkọ

Ẹ̀yà tàbí orísìí ìdàkọ méjì pàtàkì ni ó wà. Àwọn náà ni àdàkọ fóónù àti àdàkọ fóníìmù tí a tún lè pè ní ìdàkọ fònẹ́tíìkì àti ìdàkọ fonẹ́míìkì. Ìdàkọ fóónù (fonẹ́tíìkì) a máa lo àwọn àrokò tí wọ́n dúró fún ìró tí a ń pè jade nígbà tí abá ń fọ̀. Irú ìró bẹ́ẹ̀ ni a mọ̀ sí fóónù, àkámọ́ onírú èyí [ ] ni a sì máa ń lò. Àwọn àrokò tí wọ́n dúró fún ìró asìyàtọ̀ tí a ń pè ní fóníìmù ni ìdàkọ fóníìmù (fònẹ́míìkì) máa ń lò ní tirẹ̀. Àkámọ́ onírú èyí / / sì ni a máa ń lò fún un. Nitorí náà, ìlànà tí a bá fẹ́ lò ni yóó sọ irú àdàkọ tí a ó ṣe. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí láti fi ìyàtọ̀ ìdàkọ fónẹ́tíìkì àti fónẹ́míìkì hàn

| Àkọtọ́ | fóónù (fònẹ́tíìkì) | fóníìmù (fònẹ́míìkì) |
|---|---|---|
| wọ́ | [wɔ˥] | /wɔ˥/ |
| wọ́n | [w̃ɔ̃˥] | /wɔ̃˥/ |
| yàn | [ jã˩ ] | /jɔ̃˩/ |
| ojó | [odʒó] | /odʒó/ |

Ó ṣe é sẹ kí a fẹ́ ṣe ìtúpalẹ̀ fóònù ìpèdè yìí:

Yorùbá ka ẹwà sí ẹ̀bùn Ọlọ́run (Adeoye 1980:162)
[yorùbá ka ɛwà sí ɛ̀bũ˩ ɔlɔ́rũ]

A sì lè ṣe àdàkọ fóníìmù ìpèdè ìsàlẹ̀ yìí
À ńlọ sí “Ọdúndún”, a sode Dẹ̀rọ̀ (Olu Daramola 1970:36)
/ à m̀lɔ sí ɔdṹdṹ/ a sode dɛ̀rɔ̀/

Wà á ṣàkíyèsí pé ìlànà àdàkọ ni a lò fún méjéèjì tí a sì lo òfin tí ó tẹ̀lé e. Àmọ́, àkámọ́ tí a lò fún wọn yàtọ̀ sí ara wọm. Nígbà tí a lo akámọ́ onírú èyí [ ] fún àdàkọ ti fóònù, a lo àkámọ́ onírú èyí / / fún àdàkọ ti fóníìmù. Ìró aṣèyàtọ̀ ni a lò fún ti àdàkọ fóníìmù nígbà tí ó jẹ́ pé ìró fóònù ni a lò làti ṣe àdàkọ fóònù.

Ní báyìí a ó gbìyànjú láti ṣe àdàkọ fóónù àti fóníìmù fún àyọkà ìsàlẹ̀ yìí:

**Àkọtọ́:** Mo bá ọ̀rẹ́ bàbá mi lọ ṣiṣẹ́ ní oko ẹgàn ní ọdún tí ó kọjá. Lẹ́yìn iṣẹ́, a gúnyán jẹ. Ọ̀rẹ́ bàbá mi pa àparò àti ikún tí a fi jẹ iyán. Inú mi dùn jọjọ ní ojọ́ náà, mo gbádùn oúnjẹ oko.

Àdàkọ fóónù (fònẹ́tíìkì)

[mo bá ɔ̀rɛ́ bàbá mĩ̄ lo ʃiʃɛ́ nĩ̄ oko ɛgã̀ nĩ̄ ɔdũ̄ tí ó kɔʤá//
lɛ́jĩ̄ iʃɛ́/ a gũ̄jã̄ ʤɛ// ɔ̀rɛ́ bàbá mĩ̄ kpa àkparò àti ikũ̄ tí a fi ʤɛ
ijã̄// inũ̄ mĩ̄ dũ̄ ʤɔʤɔ nĩ̄ ɔʤɔ nã̄ã̄/ mo gbádũ̄ oũ̄ʤɛ oko//]

Àdàkọ fóníìmù (fònẹ́míìkì)

// mo bá ɔ̀rɛ́ bàbá mi lo ʃiʃɛ́ ní oko ɛgã̀ ní ɔdũ̄ tí ó kɔʤá//
lɛ́jĩ̄ iʃɛ́/ a gũ̄jã̄ ʤɛ// ɔ̀rɛ́ bàbá mi kpa àkparò àti ikũ̄ tí a fi ʤɛ
ijã̄// inũ̄ mi dũ̄ ʤɔʤɔ nĩ̄ ɔʤɔ nã̄ã̄/ mo gbádũ̄ oũ̄ʤɛ oko//

gbìyànjú láti ṣe àwárí ìyàtọ̀ tí ó wà nínú àdàkọ fònẹ́tíìkì àti fònẹ́míìkì.

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti sọ nípa dída ìró kọ. A mẹ́nu bà á pé ìlànà méjì ni ó wà láti da ìró kọ: ìlànà ìdàkọ IPA àti ìlànà àkọtọ́. A sàlàyé àǹfààní ìlànà méjéèjì àti kùdìẹ̀-kudiẹ wọn. A kò salâì mẹnu bà àwọn ìyàtọ̀ tó wà láàárín ìlànà méjéèjì.

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Gbìyàjú láti ṣe àdàkọ fóònù (fònẹ́tíìkì) àti fóníìmù (fònẹ́míìkì) àyọkà ìsàlẹ̀ yìí

Alábàpàdé bá tún bèrè ó ní, "Báwo lo ha ṣe dé inú àpótí nínú ìtẹ́ òkú?" òun náà dáhùn ó ní, "Èyí kò yé èmi pàápàá jù bẹ́ẹ̀ lọ, ṣùgbọ́n kinni kan ni mo rántí òun ni pé ìyáálé mi àgbà pátápátá ní ààfín ló gbé ọbẹ̀ kan 'fun mi tí mo lá, ṣùgbọ́n bí mo ti ṣe dee inú àpótí kò yé mi dáadáa." Alábàpàdé tún bèrè ó ní, "Ṣé ìyáálé rẹ̀ yìí fẹ́ràn rẹ?" ó dáhùn ó ní, "Ní ti ojú, ó fẹ́ràn mi, ṣùgbọ́n Olódùmarè ló mọ ti ọkàn. Si, gbọ́ bí kò tilẹ̀ fẹ́ mi tọkàntọkàn nkọ́? Ó ṣebi ó lè mú u jẹ ni? – ó tì o, gẹ́gẹ́ bí orúkọ mi, Ẹ̀san-ń-bọ̀, ẹsan kò ní, ṣâì dé bá a". Nígbà tí Alábàpàdé wá tún bèrè tí ó ní, "Èwo ni a ó ha

ṣe? Ṣe kí á wa ọ̀nà kí o padà sí ààfin" Ẹ̀san ké kàrá ó ní, "Lílọ àbí ńlá? Bí Aláyé bá fojú kàn mí ìyà tó máa tún fi jẹ mi yóò burú ju ikú lọ, Ṣùgbọ́n tìrẹ kó ní àní àní, pípa ló máa pa ọ́ wéréwéré, ìpa oró sì ni, nítorí ó rí mi lọ́dọ̀ rẹ gan-an, bí awa ayaba bá ń bọ̀ lọ́jà, ọjà ń tú ni. Ọkùnrin tí kò bá sá, síbẹ̀ ni! Ò̀un kọ, Ọba tí ó lkè tí o jù dàrọ́, tí ó burú tí ó ju májèlé lọ! (D.O Fagunwa 2005 (12th edition))

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tîìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# MÓÒDÙ KEJÌ

## ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKÍNNÍ

## SÍLÉBÙ

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ohun tí a fẹ́ gbéyẹ̀wò báyìí ṣe pàtàkì nínú títú èdè kan palẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó jẹ́ ègé tí ó kéré jù lọ ṣùgbọ́n ó lè tóbi ju ìró lọ. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ó ti wo ìhun àti ẹ̀yà sílébù èdè Yorùbá. A ó wo ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ àti ọlọ́pọ̀ sílébù. A ó tún mẹ́nuba ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù tó bẹ́ẹ̀ tó jẹ́ pé lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí sílébù èdè Yorùbá tí á sì lè pín irú ọ̀rọ̀ yówù kó jẹ́ sí ìye sílébù tó jẹ́.

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÌDÀNILẸ́KỌ̀Ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè ṣe:

- Sọ iye sílébù tí ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan ni

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Iye sílébù mélòó ni ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ yìí ni:

Adígarawa, àjàgùnmàlè, páńpẹ́, wá, agbódórogun, dánáfojúrà

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Sílébù ni ìdá tàbí ègé tí ó kéré jù lọ tí a lè dá fi ohùn pè (Owólabí 2013:137). Oríkì Owólabí yìí gùn lé otítọ́ kan tí ó dájú nípa èdè Yorùbá, ìyẹn ni pé, èdè olóhùn ni èdè Yorùbá, nítorí náà ni oríkì náà ṣe ki sílébù èdè Yorùbá mọ́ ohùn. Gbogbo ibi tí ohùn bá sì ti jẹ yọ ni a ti lè ṣe ìdámọ̀ sílébù èdè Yorùbá. Bí a bá gùn lé oríkì yìí, yóó rọ̀ wá lọ́rùn láti ṣàwárí sílébù èdè Yorùbá.

Àlàyé Bámgbóṣe (1990:25) náà wúlò láti lè sàwárí sílébù bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò gbé e ka orí ohùn. Ó ní, nígbà tí a bá pe ọ̀rọ̀ ní èdè Yorùbá, a ṣàkíyèsí pé a máa ń ṣe àpèpọ̀ fún kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì (bá, bẹ́, bú abbl) ṣùgbọ́n tí kò bá sí kọ́nsónáǹtì tí ó sáájú fáwẹ́lì, a ó dàá fáwẹ́lì ọ̀hún pè. Bí àpẹẹrẹ, a ó dá **a** àkọ́kọ́ nínú **àbá** pè. Ní báyìí, ẹ jẹ́ kí a wo iye sílébù tí àwọn ọ̀rọ̀ ìsàlẹ̀ yìí ni:

a. Adígarawa
b. Àjàgùnmalè

d. Páńpẹ́
e. Wá

Àpẹẹrẹ àkọ́kọ́ òkè yìí ṣe é pín báyìí A/dí/ga/ra/wa. Nítorí náà, àpẹẹrẹ náà ní sílébù márùn-ún. A sì lè pín *àjàgùnmàlè* báyìí à/jà/gùn/mà/lè, èyí náà ní sílèbú márùn-ún. *Páńpé* ni sílébù mẹ́ta a sì lè pín-in báyìí pá/ń/pẹ́ nígbà tí *wá* ni sílébù kan. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé, iye ibi tí ohùn wà ni a fi pín àwọn ọ̀rọ̀ tí à ń gbé yẹ̀wò sí sílébù. Bẹ́ẹ̀ náà ni a dá pe fáwẹ́lì tí kò ní kọ́nsónáǹtì níwájú rẹ̀, tí a sì ṣe àpèpọ̀ kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì. Lọ́rọ̀ kan sá, ohùn ṣe pàtàkì nínú síṣe àwárí sílébù èdè Yorùbá.

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Sílébù gẹ́gẹ́ bí ègé ọ̀rọ̀ tí ó kéré tí a lè dá fi ohùn pè ni a ṣàlàyé nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. A jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé ohùn ṣe pàtàkì nínú pípín àwọn ọ̀rọ̀ sí sílébù bẹ́ẹ̀ náà ni a gbìyànjú láti pín àwọn ọ̀rọ̀ kan sí sílébù.

## 6.0 IDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Gbìyànjú láti pín àwọn ìpèdè ìsàlè yìí sí ìye sílébù tí wọ́n ní:

adígarawa,
àjàgùnmàlè,
páńpẹ́,
aá,
agbódórogun,
dánáfojúrà

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Bamgbose Ayo (1990). *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorubá*. Ibadan. University Press Limited

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKEJÌ

# ÌHUN SÍLÉBÙ

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá, a sọ̀rọ̀ nípa sílébù, pàápàá a jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé ohùn ṣe pàtàkì nínú ìsàpèjúwe àti ìdámọ̀ sílébù èdè Yorùbá nítorí pé èdè olóhùn ní i ṣe. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, oun gan-an tí a fẹ́ ṣe ni láti wo ìhun sílébù èdè Yorùbá. Ìbéèrè kan tí ó ṣe pàtàkì tí ó gbọdọ̀ máa tawọ́ tasẹ̀ nínú wa ni pé, kín ni àwọn nǹkan náà tí a lè tò jọ tí a ó sì pè ní sílébù?

## 2.0 ÈRÒNGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

- Sàlàyé ìhun sílébù èdè Yorùbá
- Ṣe àlàyé ẹ̀yà ìhun sílébù èdè Yorùbá

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

i. Ṣàlàyé ìhun sílébù èdè Yorùbá pẹ̀lú àpẹẹrẹ
ii. Lo ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ ṣe àlàyé ẹ̀yà ìhun sílébù

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá, a sọ̀rọ̀ nípa sílébù gẹ́gẹ́ bí i ègé tí ó kéré jùlọ tí a lè dá fi ohùn pè. A ṣàlàyé pé ohùn ṣe pàtàkì nínú síṣàlàyé àti síṣàwárí sílébù, ní báyìí, ohun mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì nípa sílébù tí a fẹ́ wò ni ìhun rẹ̀. Tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìhun sílébù, odo àti apàálà sílèbù ni à ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀. Owólabi (2013:137) ṣàlàyé pé bí a bá pe sílébù sí ìta, odo sílébù ni a máa ń gbọ́ ju apàálà sílébù lọ. Ó tún ṣàlàyé pé, odo sílébù yìí ni agbátẹ̀rù ohùn àti pé, kò sí sílébù tí kò ní odo sílébù nínú ìhun rẹ̀. Nítorí náà bí sílébù bá ní ègé ìró kan soso, ègé ìró náà ni yóó dúró gẹ́gẹ́ bí odo sílébù. Sílébù lè ní apàálà sílébù nínú ìhun rẹ̀ tàbí kí ó máà ní. Àmọ́ sá, bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìhun sílébù èdè Yorùbá, ìró kọ́nsónáǹtì ni ó máa dúró gẹ́gẹ́ bí apàálà sílébù nígbà tí ìró fáwẹ̀lì àti ìró kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù sì máa ń dúró gẹ́gẹ́ bí odo sílébù. Wà á ṣàkíyèsí pé ìró fawẹ̀lì ni ó máa ń gba ohùn, ìró kọ́nsónáǹtì kìí gba ohùn àyàfi ìró kọ́nsónáǹtì aránmú asesílébù. Nítorí ìdí yìí ni ìró kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ̀lì fi gba oríkì Fonọ̀lọ́jì gẹ́gẹ́ bí a ti fi hàn saájú ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Móòdù ìkínní, ìkejì àti ìkẹta tí a ó tún ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀ níbí kí ó lè rọrùn láti rántí.

*Ìró kọ́nsónáǹtì ni ó máa ń sìṣẹ́ apàálà sílébù*
*Ìró fáwẹ̀lì ni ó máa ń sìṣẹ́ odo sílébù*

Nǹkan pàtàkì tí oríkì òkè yìí fi yé wa ni pé, kò fàyè gba ìró kọ̀nsónáǹtì aránmú asesílébù gẹ́gẹ́ bí i ìró kọ̀nsónáǹtì nítorí pé kò lè sísẹ́ apàálà sílébù bí i àwọn kọ̀nsónáǹtì yòókù. Ìdí gan-an tí ó fi yàtọ̀ sí àwọn kọ̀nsónáǹtì tókù nìyẹn. bí ó tilẹ̀ jẹ́ kọ̀nsónáǹtì, òun nìkan ni kọ̀nsónáǹtì tí àyè gbà láti sísẹ odo sílébù.

## 3.1 Ẹ̀ya Ìhun Sílébù

Ẹ̀yà ìhun sílébù mẹ́ta ni ó wà ní èdè Yorùbá, àwọn náà ni:
Fáwẹ́lì
Kọ̀nsónáǹtì àti Fáwẹ́lì
Kọ̀nsónáǹtì Arámú Asesílébù
A lè fi lẹ́tà rọ̀pò gẹ́gẹ́ bí àrokò tí yóò máa dúró fún wọn báyìí
F= Fáwẹ́lì
KF = Kọ̀nsónáǹtì àti Fáwẹ́lì
N = Kọ̀nsónáǹtì Arámú Asesílébù
Àpẹẹrẹ tí a ó lò láti fi ẹ̀yà ìhun sílébù hàn nínú èdè Yorùbá ni
A dé wá lé
F KF KF KF

A lá ǹ gbá
F KF N KF

A bí m bọ́ lá
F KF N KF KF

Àwọn ìwọ̀nyí dájú nipa ẹ̀yà ìhun sílèbù tí a ṣàlàyé yìí:

- Sílébù lè ní ègé ìró kan soso nínú ìhun rẹ̀, bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, ègé ìró yóó jẹ́ ìró fáwẹ́lì tàbí kí ó jẹ́ kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù. Àmọ̀ sá, bí sílébù bá ní ju ègé ìró kan soso lọ, a jẹ́ pé ègé ìró náà yóó jẹ́ ìró kọ̀nsónáǹtì àti fáwẹ́lì ní tẹ́léǹtẹ̀lé.
- Kọ̀nsónáǹtì kìí parí sílébù èdè Yorùbá,
- Èdè Yorùbá kò fàyè gba ìsùpọ̀ kọ̀nsónáǹtì (ìyẹn ni kí kọ̀nsónáǹtì méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tẹ̀lé ara wọn ní tẹ̀léǹtẹ̀lé).

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti sọ̀rọ̀ nípa ìhun sílébù àti ẹ̀yà ìhun rẹ̀. A ní, ìhun sílébù ni odo àti apàálà sílébù. Fáwẹ̀lì ni ó máa ń sisẹ́ odo sílébù, àtunfi kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù. Ìró kọ̀nsónáǹtì ni ó máa ń sisẹ́ apàálà sílébù.

Ohun mìíràn tí a mẹnu bà ni ẹ̀yàn ìhun sílébù. A sọ pé bí a bá lo lẹ́tà àwọn wọ̀nyí ni yóó jẹ́ ẹ̀yà ìhun sílébù èdè Yorùbá

F fún Fáwẹ́lì
KF fún Kọ́nsónáǹtì àti Fáwẹ́lì
N fún kọ́nsónáǹtì Aránmú Asesílébù
A fi kún un pé, kọ́nsónáǹtì kìí parí sílébù èdè Yorùbá, bẹ́ẹ̀ náà ni kìí sí ìsùpọ̀ kọ́nsónáǹtì nínú èdè náà. Bí sílébù bá sì jẹ́ ẹlẹ́yọ ègé ìró kan soso, irú sílébù bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ fáwẹ́lì tàbí kí ó jẹ́ kọ́nsónáǹtì aránmú asesílébù. Ohun tí ó yẹ kí a tún mọ̀ ni, àwọn ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù àti ọlọ́pọ̀ sílébù. A ó wo eléyìí ní iwájú

## 6.0 ÌDÁNRAWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ṣe àlàyé àwọn kókó ọ̀rọ̀ yìí ní kíkún

1. Ìhun sílébù èdè Yorùbá
2. Ẹ̀yà ìhun sílébù èdè Yorùbá

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KẸTA

# KỌ́NSÓNÁǸTÌ ARÁNMÚ AṢESÍLÉBÙ

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Mo mọ̀ pé, a ti wo fóníìmù ní Móòdù àkọ́kọ́ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ṣùgbọ́n ní báyìí kọ́nsónáǹtì aránmú sílébù gẹ́gẹ́ bí i fóníìmù àti irú ẹ̀dà tí ó ní. A ó tún wo sàkání tí àwọn ẹ̀dà fóníìmù yìí ń jẹyọ.

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ní ìrètí pé, ó yẹ kí a lè sàlàyé fóónù àti fóníìmù kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù.

Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀

1. Ṣe àpèjúwe fóníìmù kọ́ńsónáǹtì aránmú aṣesílébù /m̄/ ní ọ̀rínkinniwín
2. Ṣe àdàkọ-fóníìmù àti àdàkọ-fóònu fún ìsọ wọ̀nyí:

    Ó ń dún  
    Ó ń yó  
    Ó ń mí  
    Ó ń pẹ́  
    Ó ń fọ́

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Kọ́nsónáǹtì Aránmú aṣesílébù ni kọ́nsónáǹtì tí a lè dá fi ohùn pè gẹ́gẹ́ bíi fáwẹ̀lì. Fọ́nrán èdè tí a mọ̀ sí odo sílébù ni fáwẹ̀lì ṣùgbọ́n àwọn kọ́nsónáǹtì aránmú tí à ń wí yìí náà ń ṣiṣẹ́ odo sílébù nítorí náà ni a ṣe ń pè wọ́n ní kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kìnní àti ikèjì móòdù yìí.

Orísìírísìí ni ìrísí kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù, Owólabí (2011:115) ṣàlàyé pé nínú èdè Yorùbá, kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù a máa ní ìrísí mẹ́fà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ èyí tí ó sábà máa ń dúró lórí ibi ìsẹ́nupè tí ìró tí ó tẹ̀lé kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù bá ní. Èyí já sí pé àwọn kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù mẹ́fẹ̀ẹ̀fà wọ̀nyí wà ní ìfọ́nká aláìṣèyàtọ̀. Nítorí ìdí èyí, gbogbo wọn jẹ́ ẹ̀dà-fóníìmù tí a gbọdọ̀ fi sí abẹ́ fóníìmù kan ṣoṣo. Àrokò tí a lò fún fóníìmù kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù nínú èdè Yorùbá ni èyí: /m̄/. Bí kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù bá jẹyọ sáájú ìró àfèjì-ètè-pè ([b] àti [m]) òun náà yóò ní àbùdá àfèjì-ètè-pè [m̄] nínú àpẹẹrẹ bí i:

ó ń bọ̀ ó ń bú ramú ramù  
[ó ḿ b̄ɔ̀] [ó ḿ b̄ú ramũ̂ ramũ̀]

/ ó ḿ ̄bɔ̀/ / ó ḿ ̄bú ramṹ ramũ̀/

Bí kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù bá jẹyọ sáájú ìró àfeyínfètèpè ([f]) òun náà yóó ní àbùdá àfeyínfètèpè nínú àpẹẹrẹ bí i:

ó ń fẹ́ ọwọ́ ó ń fọsọ

[ó Ḿ ̄fɛ́ ɔwɔ́] [ó Ḿ ̄fɔʃɔ]

/ó ḿ ̄fɛ́ ɔwɔ́/ /ó ḿ ̄fɔʃɔ/

Bí kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù bá jẹyọ sáájú ìró afèrìgìpè ([d], [t], [n], [s], [r], [l]) àti ìró afàjàjàfèrìgìpè ([Σ], [dZ]) yóó ní ìrísí ìró afèrìgìpè àpẹẹrẹ ni

ó ń sínọmọrí náà ń ṣí kòkòrò náà ń dún

[ó ń sĩ́] [ɔmɔrí nã́ã̀ ń Σí] [kòkòrò nã́ã̀ ń dṹ]

/ ó ḿ ̄sĩ́/ /ɔmɔrí nã́ã̀ ḿ ̄Σí/ /kòkòrò nã́ã̀ ḿ ̄dṹ/

Bí kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù bá jẹyọ sáájú ìró afàjàpè ([ ], [j]), òun náà yóó ní ìrísí afàjàpè. Àpẹẹrẹ ni

Adé ń yọ̀

[adé ̄jɔ̀]

/adé ḿ ̄jɔ̀/

Bí kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù bá jẹyọ sáájú afàfàsépè ([k], [g]) àti afitán-ánnápè ([h]) yóó ní àbùdá afàfàsépè [N ̄] nínú àpẹẹrẹ bí i

ó ń ké ọṣẹ náà ń hó

[ó N ̄ké] [ɔΣɛ nã́ã̀ N hó]

/ ó ḿ ̄ké / / ɔΣɛ nã́ã̀ ḿ ̄hó /

Bí kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù bá jẹyọ sáájú ìró afàfàséfètèpè ([k□p], [g□b]), òun náà yóó ní àbùdá afàfàséfètèpè ([N□m ̄]) àpẹẹrẹ ni

Ọlọ́run ń gbọ́

[ɔlɔ́rũ N□m ̄gbɔ́]

/ ɔlɔ́rũ ḿ ̄gbɔ́/

## 3.1 Dídárúkọ kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù Ọlọ́rọ̀ ìperí mẹ́rin

Bí a ti ṣe fún kọ̀nsónáǹtì àti fáwẹ̀lì náà ni a ó ṣe fún kọ̀nsónáǹtì aránmú aṣesílébù, àwọn ohun tí wà á tẹ̀lé ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

i. Ipò tí alàfo tán-an-ná wà
ii. Ibi Ìsẹ́nupè
iii. Ọ̀nà Ìsẹ́nupè
iv. Ohùn ni a fi pè é (Aṣesílébù).

[n] akùnyùn afàrìgìpè aránmú aṣesílébù
[ ̄] akùnyùn afàjàpè aránmú aṣesílébù
[N] akùnyùn afàfàsépè aránmú aṣesílébù
[M] akùnyùn afeyínfètèpè aránmú aṣesílébù
[N□m ̄] akùnyùn afàfàséfètèpè aránmú aṣesílébù
[ḿ ̄] akùnyùn afèjì-ètè-pè aránmú aṣesílébù

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Àwòrán atọ́ka igi ìsàlẹ̀ yìí ni mo fẹ́ fi ṣe ìsọnísókí láti ṣàlàyé kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù




## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

1. Ṣe àpèjúwe fóníìmù kọ́ńsónáǹtì aránmú aṣesílébù / m ¯ / ní ọ̀rínkinniwín
2. Ṣe àdàkọ-fóníìmù àti àdàkọ-fóònu fún ìsọ wọ̀nyí:

   Ó ń dún
   Ó ń yó
   Ó ń mí
   Ó ń pẹ́
   Ó ń fọ́

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ̀lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ ÌKẸRIN

# Ọ̀RỌ̀ ẸLẸ́YỌ ÀTI ỌLỌ́PỌ̀ SÍLÉBÙ

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Nínú àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa àtẹ̀yìnwá, a ti sọ̀rọ̀ nípa ìhun sílébù èdè Yorùbá àti ẹ̀yà ìhun rẹ̀. A mẹ́nu bà á wí pé bí sílébú bá ni ẹyọ ègé ìró kan soso, irú ìró bẹ́ẹ̀ yóó jẹ́ ìró fáwẹ́lì tàbí kí ó jẹ́ kọ́nsónáǹtì aránmú asesílébù tí wọ́n máa ń sísẹ́ odo sílébù ṣùgbọ́n bí sílébù bá ni ju ègé ìró kan lọ, a jẹ́ pé yóó jẹ́ àpapọ̀ kọ́nsónáǹtì (tí ń siṣẹ́ apàálà sílébù) àti fáwẹ́lì (tí ó ń siṣẹ́ odo sílébù) tí wọ́n tẹ̀lé ara wọn tẹ̀léǹttẹ̀lé.

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó wo àwọn ọ̀rọ̀ oní sílébù kan àti àwọn ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù. A ó mẹ́nu ba ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú àwọn ọ̀rọ̀ olọ́pọ̀ sílébù, tí a ó sì wo bí wọ́n ṣe ń ba ara wọn siṣẹ́.

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

- Tọ́ka sí ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù àti ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù
- Ṣe àpèjúwe ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù èdè Yorùbá

### 2.1 Ìdániwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

i. Tọ́ka sí àwọn ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù nínú àtòjọ ọ̀rọ̀ ìsàlẹ̀ yìí:
Wá, Adéwálé, Ìpàdéọlá, sọ, sùn, sá, Túnráyọ̀,

ii. Ṣe àpèjúwe ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù èdè Yorùbá

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Bí ènìyàn bá ń sọ̀rọ̀, orísìírísìí ọ̀rọ̀ ni ènìyàn máa ń lò. Irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ọ̀rọ̀ oní sélébù kan tàbí kí ó ní ju sílébù kan lọ. Ọ̀rọ̀ tí ó ní sílébù kan ni à ń pè ní ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù, àpẹẹrẹ ni *wá, lọ, sùn, jẹ, kú* abbl. Ọ̀rọ̀ tí ó bá ní ju sílébù kan lọ nínú ìhun rẹ̀ ni a mọ̀ sí ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù. Irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ni: *ẹ̀wà, òpóponà, Inálẹ́ndé, Ìpàdéọlá, Ìfẹ́dàpọ̀* abbl.

### 3.1 Ìjẹyọpọ̀ Fáwẹ́lì Nínú Ọ̀rọ̀ Ọlọ́pọ̀ Sílébù

Fáwẹ́lì kìí kàn sà dédé jẹyọ nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù, wọ́n ní ètò ìjẹyọpọ̀ wọn. Àwọn fáwẹ́lì kan kìí jẹyọ pọ̀ pẹ̀lú àwọn kan. Ohun gan-an tí a fẹ́ gbé yẹ̀wò ní apá yìí nìyí. Bátánì tí a ó tẹ̀lé nìyí; bí sílébù àkọ́kọ́ bá jẹ́ Fáwẹ́lì tí sílébù kejì sì jẹ́ Kọ́nsónáǹtì àti Fáwẹ́lì tí a lè ṣe ìgékúrú rẹ̀ báyìí: $F_1 – KF_2$
Báyìí ni ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì náà ṣe máa ń rí ní èdè Yorùbá:

Bí fáwẹ̀lì [i] bá wà ní $F_1$ gbogbo fáwẹ̀lì èdè Yorùbá yòókù ni wọ́n lè wà ní $F_2$. Àwọn fáwẹ̀lì bí i: a, e, ẹ, i, o, ọ, u, in, ẹn, ọn, an, àti un nínú ọ̀rọ̀ bí i
Ìlà, ilé, ìlẹ̀, ìdí, ihò, ìjọ, ìlù, ìpín, ìyẹn, ifọ́n, iyán, inú
Bí fáwẹ̀lì [a] bá jẹyọ ni $F_1$ gbogbo fáwẹ̀lì èdè Yorùbá ni ó lè jẹyọ ni $F_2$ (a, e, ẹ, i, o, ọ, u, in, ọn, an, àti un) àyafi fáwẹ̀lì ẹn nínú àwọn ọ̀rọ̀ bí i:
Aya, àlè, alẹ́, àdí, àdó, akọ, adú, akin, àpọ́n, àyàn, àmù ṣùgbọ́n kò sí ọ̀rọ̀ bí i *ayẹn ní èdè Yorùbá.
Bí fáwẹ̀lì [e] bá wà ní ipò $F_1$, àwọn wọ̀nyí ni fáwẹ̀lì tí ó lè wà ní ipò $F_2$, i, e, o, u, in, un nínú àwọn ọ̀rọ̀ bí i:
ebi, èdè, ètò, eku, egbin, egúngún
A ó ṣàkíyèsí pé bí fáwẹ̀lì [e] bá wà ní ipò $F_1$ kò lè jẹyọ pọ̀ pẹ̀lú àwọn fámẹ̀lì bí i, ẹ, ọ, a, àti ẹn ní ipò $F_2$. Nítorí náà a kò lè rí ọ̀rọ̀ bí ìwọ̀nyí ní èdè Yorùbá
*epẹ̀, *elọ, *egbà, àti èpọn
Bí fáwẹ̀lì [ẹ] bá wà ní ipò $F_1$, àwọn wọ̀nyí ni àwọn fawẹ́lì tí wọ́n lè wà ní $F_2$: i, ẹ, a, ọ, u, ọn, un nínú ọ̀rọ̀ bí i:
ẹbí, ẹ̀bẹ̀, ẹ̀pà, ẹ̀fọ́, ẹbu, ẹ̀fọn, ẹ̀bùn. Bí fáwẹ̀lì [ẹ] bá wà ni ipò $F_1$, àwọn fáwẹ̀lì yìí kò le wà ní ipò $F_2$: e, o, àti ẹn. Nítorí náà, awọn ọ̀rọ̀ bí i *ẹpe, *ẹbo àti *ẹ̀yẹn kò lè wáyé nínú èdè Yorùbá
Bí fáwẹ̀lì [o] bá wà ní ipò $F_1$, àwọn fáwẹ̀lì yìí ni wọ́n lè wà ní ipò $F_2$: i. e, o, u, in, un, nínú ọ̀rọ̀ bí i:
òbí, olè, òdo, olú, opìn, okùn
Àmọ́, àwọn fáwẹ̀lì yìí: ẹ, ọ, a, ẹn, àti ọn kò lè wà ní ipò $F_2$ bí fáwẹ̀lì [o] bá wà ní ipò $F_1$. Nítorí náà, a kò lè ní irú ọ̀rọ̀ báyìí: *òpẹ̀, *òbọ, *òpá, *òsàn, *obọn
Bí fáwẹ̀lì [ọ] bá wà ní ipò $F_1$, àwọn fáwẹ̀lì tí ó lè wà ní ipò $F_2$ ni: i, ẹ, a, ọ, in, ọn, àti un nínú ọ́rọ́ bí i:
ọtí, ọ̀lẹ, ọfà, ọ̀bọ, ọ̀kín, ọpọ́n, ọ̀bùn
àwọn fáwẹ̀lì bí i: e, o, u, àti ẹn kò lè bá fáwẹ̀lì [ọ] jẹyọpọ̀ ní ipò $F_2$ bí ó bá wà ní $F_1$. Nítorí náà, a kò lè ní ọ̀rọ̀ bí i: *ọbe, *ọpo, *ọko, *ọbù àti ọ̀yẹn

## 3.2 Àwọn Fáwẹ̀lì tí Wọn ò le wà ní $F_1$

Ó yẹ kí a ṣàlàyé ní kíkún pé, àwọn fáwẹ̀lì èdè Yorùbá kan wà tí wọn kò lè wà ní ipò $F_1$ nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn saájú. Àkọ́kọ́ tí a ó mẹ́nu ba ni fáwẹ̀lì [u]. Nínú ẹ̀ka èdè àjùmọ̀lò, fáwẹ̀lì [u] kìí bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ àyàfi àwọn ẹ̀ka èdè kan pàápàá ẹ̀ka èdè àrin gbùngùn gẹ́gẹ́ bí àlàkalẹ̀ Awobùlúyì (1998) nínú èyí tí ẹ̀ka èdè Ìjẹ̀sà, Ifẹ̀ abbl jẹ ara wọn. Nínú irú ẹ̀ka èdè yìí ni a ti lè rí ọ̀rọ̀ bí i *ulé, ùdí, ùkòkò* abbl.

Àwọn fáwẹ̀lì aránmú náà kìí bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ nínú èdè Yorùbá nítorí náà wọn kò lè jẹyọ ní $F_1$. ẹ jẹ́ kí a wo ọ̀rọ̀ bí i:
*unfin, *ọnmọ̀, *indí abbl
Àmọ́ sá, ó yẹ kí a fi kún un pé, ó ṣe é ṣe kí a rí àwọn aránmú yìí kí wọ́n bẹ̀bẹ̀ ọ̀rọ̀ ayálò láàárín àwọn Yorùbá òde oní pàápàá àwọn ọmọ Yorùbá tí

wọ́n ti ní ìfarakínra pẹ̀lú èdè Gẹ̀ẹ́sì bí i: ìnsìpẹ́kítọ̀ (inspector), ẹ́ngínì (engine), indonésíà (indonesia) abbl. Nítorí náà, bí a bá ni àwọn fáwẹ̀lì aránmú kò le bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ní èdè Yorùbá, ó yẹ kí a máa rántí pé èyí kò rí bẹ́ẹ̀ láàárín àwọn Yorùbá tí wọ́n ti ní ìfarakínra pẹ̀lú èdè Gẹ́ẹ̀sì pàápàá ní ilé-ìwé. Ó ṣe é ṣe kí àwọn Yorùbá tí wọn kò ní ìfarakínra pẹ̀lú èdè Gẹ̀ẹ́sì pe àwọn ọ̀rọ̀ tí a fi ṣe àpẹẹrẹ wọn lókè bámìíràn (ìsìpẹ́kítọ̀, ẹgínnì, idonésíà). Kí ó sì wà ní ìbámu pẹ̀lú ìwòye Owólabí (2013) nípa òfin tí ó de ọ̀rọ̀ àyálò wọ inú èdè Yorùbá.

## 3.3 Àkíyèsí lórí Bátánì Ìjeyọpọ̀ Fawẹ̀lì nínú Ọ̀rọ̀ Ọlọ́pọ̀ Sílébù

Owólabí (2013:145) ṣe àwọn àkíyèsí yìí

- Bátánì ìjẹyọpọ̀ fáwẹ̀lì fún fáwẹ̀lì ‘e’ àti ‘o’ jẹ ọ̀kan-ùn nítorí pé iye fáwẹ̀lì kan náà ni kò lè tẹ̀lé wọn
- Bátánì ìjẹyọpọ̀ fáwẹ̀lì fún fáwẹ́lì ‘ẹ’ àti ‘ọ’ fẹ́rẹ̀ẹ́ jẹ ọ̀kan-ùn nítorí pé fáwẹ̀lì ‘u’ nìkan soso tí ó lè tẹ̀lé ‘ẹ’, ṣùgbọ́n tí kò tllé ‘ọ’ ni ó fa ìyàtọ̀ láàárín bátánì ìjẹyọpọ̀ fáwẹ̀lì fún àwọn fáwẹ̀lì méjéèjì yìí.
- Bátánì ìjẹyọpọ̀ fáwẹ̀lì fún fáwẹ̀lì ‘i’ àti ‘a’ fẹ́rẹ̀ẹ́ jẹ ọ̀kan-ùn nítorí pé fáwẹ̀lì ‘ẹn’ nìkan soso tí ó lè tẹ̀lé ‘i’ ṣùgbọ́n tí kò tẹ̀lé ‘a’ ni ó fa ìyàtọ̀ láàárin bátánì ìjẹyọpọ̀ fáwẹ̀lì fún àwọn fáwẹ̀lì méjéèjì yìí.
- Bátánì ìjẹyọpọ̀ fáwẹ̀lì fún fáwẹ̀lì ‘u’ àti àwọn fáwẹ̀lì aránmú ‘ẹn’, ‘ọn’, ‘in’, ‘un’, jẹ́ ọ̀kan-ùn nítorí pé kò sí èyíkéyìí nínú àwọn fáwẹ̀lì wọ̀nyí tí ó lè jẹ yọ ni ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù nínú èdè Yorùbá.

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSONÍSÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti ọ̀rọ̀ nípa ọ̀rọ̀ ẹléyọ àti ọlọ́pọ̀ sílébù. A fi àpẹẹrẹ gbe àlàyé wa lórí ọ̀rọ̀ ẹléyọ sílébù àti ọlọ́pọ̀ sílébù lẹ́sẹ̀. Lẹ́yìn ẹyí ni a mẹ́nu ba ìjẹyọpọ̀ fáwẹ̀lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù tí a ó fi àtẹ ìsàlẹ̀ sí ṣe ìsọnísókí rẹ̀.

| $F_2$→ | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| $F_1$↓ | e | O | ẹ | ọ | A | i | u | ẹn | ọn | in | un |
| e | + | + | - | - | - | + | + | - | - | + | + |
| o | + | + | - | - | - | + | + | - | - | + | + |
| ẹ | - | - | + | + | + | + | + | - | + | + | + |
| ọ | - | - | + | + | + | + | - | - | + | + | + |
| a | + | + | + | + | + | + | + | - | + | + | + |
| i | + | + | + | + | + | + | + | + | + | + | + |
| u | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - |
| ẹn | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - |
| ọn | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - |
| in | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - |
| un | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - | - |

*A ṣe àmúlò àtẹ yìí láti inú Owólabí (2013:144)*

Afi kún àlàyé wa pé àwọn fáwẹ́lì aránmú tí ń di lílò láàrin àwọn Yorùbá tí wọ́n ni ìfarakínra pẹ̀lú èdè Gẹ̀ẹ́sì tí ó yàtọ̀ díẹ̀ sí èrò Owólabí (2013)

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Gbìyànjú láti dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí dáadáa

1. Tọ́ka sí àwọn ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù nínú àtòjọ ọ̀rọ̀ ìsàlẹ̀ yìí:
2. Wá, Adéwálé, Ìpàdéọlá, sọ, sùn, sá, Túnráyọ̀,
3. Ṣe àpèjúwe ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù èdè Yorùbá

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Awóbùlúyì, O. (1998). "Àwọn Ẹ̀ka Èdè Yorùbá" Paper presented at YSAN Conference, Ìbàdàn.

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

# MÓÒDÙ KẸTA

Àbùdá afọ̀ geere
Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìkìnní
Ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn

## ÀBÙDÁ AFỌ̀ GEERE

## ÀRÀNMỌ́

1.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
2.0 Ìdánwo Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Ìyípadà ohùn
3.1.1 Ìhun tí Ìyípadà Ohùn ti Máa ń Wáyé
3.1.1.1 Ọ̀rọ̀-Ìṣe + Ọ̀rọ̀-Orúkọ Àbọ̀
3.1.1.2 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Ẹ̀rún Ọ̀rọ̀ Ìṣe ‘ń’
3.1.1.3 Ọ̀rọ̀-Ìṣe + Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Àbọ̀
3.1.1.4 Ẹ̀rún Ọ̀rọ̀-Ìṣe ‘ń’ + Ọ̀rọ̀-Ìṣe (pẹ̀lú àbọ̀) + Ọ̀rọ̀-Ìṣe
3.1.1.5 Olùwà + Kókó-Gbólóhùn
3.1.1.6 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Ìsọ̀rí àwọn Wúnrẹ̀n kan
3.1.1.7 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Wúnrẹ̀n ‘a’
3.1.1.8 Ọ̀rọ̀ Orúkọ + Ẹ̀yán
3.1.1.9 Gbólóhùn Alátẹnumọ́
3.2 Isóhùnnípò àti Ìgbohùnnípò
3.3 Lílo Ohùn
3.3.1 Fífi Ìtumọ̀ Àdámọ́ Hàn
3.3.2 Fífi Ìtumọ̀ Gírámà Hàn
3.4 Èrò Oyèbádé
4.0 Conclusion
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Nígbà tí a bá ń fọ̀ tàbí ọ̀rọ̀ orísìírísìí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ni ó máa ń wáyé lára wọn ni ìyípadà ohùn, ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò, àrànmọ́, ìsúnkì, ìpajẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú ìdanilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó wo ìgbẹ́sẹ̀ ajẹmọ́ ohùn. Lára ohun tí a ó mẹ́nu bà ni ìyípadà ohùn, ìhun tí ìyípadà ohùn ti máa ń wáyé, ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò. Àwọn ìgbésẹ̀ tó kù ni a ó wò nínú àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó tẹ̀lé eléyìí.

Ní móòdù akọ́kọ́, a ṣàlàyé pé, èdè olóhùn ni èdè Yorùbá, àti pé ègé ohùn mẹ́ta ni a lè yà sọ́tọ̀ nínú èdè náà yàtọ̀ sí àwọn ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ̀. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí yóó ṣàlàyé bí àwọn ohùn náà ṣe ń sisẹ́ àti sàkání tí wọn ti ń ṣiṣẹ́ àti àwọn ìyípadà tí ó máa ń pa wọn pẹ̀lú àwọn oun tí ó fà á.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

- Ṣe àlàyé ìyípadà ohùn
- Tọ́ka sí ìhun tí ìyípadà ohùn ti máa ń wáyé
- Ṣàlàyé ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ìyípadà ohùn àti ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò

## 2.1 Ìdánwo Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

i. Kí ni Ìyípadà ohùn?
ii. Ṣe àlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ ìhun tí ìyípadà ohun ti máa ń wáyé márùn-ún
iii. Ìyàto pàtàkì wo ni ó wà láàrin ìyípadà ohùn àti ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò?

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Kí ni ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn? Èyí ni fífi ohùn kan rọ́pò òmíràn nínú ìsọ (wo Owólabí 2013:126). Àpẹẹrẹ ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn ni ìyípadà ohùn, ìsóhùnnípò, ìgbohùnnípò, àti àrànmọ́-ohùn. A kò ní mẹ́nu ba àrànmọ́-ohùn ní ibí yìí, inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó dá lórí arànmọ́ ni a ó ti mẹ́nu bà á.

## 3.1 Ìyípadà ohùn

Ìyípadà ohùn ni kí ohùn ọ̀rọ̀ kan yìí padà kúrò gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ sí ohùn mìíràn nígbà tí a bá lò ó nínú ẹ̀hun. Itùmọ̀ ohùn àdámọ́ ni ohùn tí ọ̀rọ̀ ní nígbà tí ó bá dá wà tàbí kọ ọ́. Oun tí a mọ̀ ni pé ohùn ọ̀rọ̀ máa ń yí padà nígbà tí a bá ń fọ̀/sọ̀rọ̀ kúrò ní ohun àdámọ́ rẹ̀ sí ohùn mìíràn. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

a. Òjò (rain) òjò rọ̀ → òjó rọ̀
b. Sùn (sleep) Bùsáyọ̀ sùn orí àga → Bùsáyọ̀ sun orí àga

Bí a bá wo àpẹẹrẹ méjéèjì òkè yìí, a ó ṣàkíyèsí pé ohùn ọ̀rọ̀ bí i **òjò** ní ohùn ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ ṣùgbọ́n nígbà tí a lò ó nínú gbólóhùn ohùn náà yí padà sí ohùn ìsàlẹ̀ àti ohùn òkè (**òjó**). Bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀rọ̀ rí fún àpẹẹrẹ kejì. **Sùn** tí ó ní ohùn ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ yí padà nínú gbólóhùn sí ohùn àárín (**sun**). Irú ìyípadà báyìí ni à ń pè ní ìyípadà ohùn. Oun tí ó kàn báyìí ni láti wo ìhun tí ìyídapà ohùn ti máa ń wáyé

### 3.1.1 Ìhun tí Ìyípadà Ohùn ti Máa ń Wáyé

Owólabí (2013:126-132) ṣàlàyé ìhun gírámà mẹ́sàn-án tí ìyípadà ohùn ti máa ń wáyé. A ó wo ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn báyìí:

#### 3.1.1.1 Ọ̀rọ̀-Ìṣe + Ọ̀rọ̀-Orúkọ Àbọ̀

Bí ọ̀rọ̀-ìṣe oní sílébù kan bá ni ohùn ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ bá gba ọ̀rọ̀ orúkọ gẹ́gẹ́ bí àbọ̀ rẹ̀ tààrà, irú ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ yóó yìí ohùn ìsàlẹ̀ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ padà sí ohùn ààrín.

rà (buy): rà bàtà → ra bàtà
sè (cook): sè ẹ̀wà → se ẹ̀wà
jò (leak): jò omi → jo omi
sùn (sleep): sùn ilé → sun ilé

#### 3.1.1.2 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Ẹ̀rún Ọ̀rọ̀ Ìṣe 'ń'

Tí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ ẹni kínní tàbí ẹnì kejì tí a lò gẹ́gẹ́ bí olùwà gbólóhùn bá jẹyọ saájú ẹ̀rún ọ̀rọ̀-ìṣe tí a mọ̀ báyìí sí ibá ìsẹ̀lẹ̀ àìṣetán atẹ́rẹẹ 'ń' ohùn olùwà náà lè yí padà tàbí kí ó má yí padà

mo → mò ń lọ
tàbí
mo ń lọ
a → à ń sá asọ
tàbí
a ń sá asọ

#### 3.1.1.3 Ọ̀rọ̀-Ìṣe + Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Àbọ̀

Tí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ tí a lò gẹ́gẹ́ bí abọ̀ fún ọ̀rọ̀-ìṣe máa ń ní ohùn òkè tí ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó jẹyọ saájú rẹ̀ bá ní ohùn ìsàlẹ̀ tàbí ohùn ààrín gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀.

Bùsáyọ̀ lù wá
Kúnlé jọ mí

Ṣùgbọ́n bí ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó jẹyọ saájú ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ àbọ̀ yìí bá ni ohùn òkè gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀, ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ àbọ̀ yìí yóó ni ohun ààrín.

Olùkọ́ kọ́ wa
Bùsáyò bú m

#### 3.1.1.4 Ẹ̀rún Ọ̀rọ̀-Ìṣe 'ń' + Ọ̀rọ̀-Ìṣe (pẹ̀lú àbọ̀) + Ọ̀rọ̀-Ìṣe

Nínú gbólóhùn, ni ibi tí ẹ̀rún ọ̀rọ̀-ìṣe tí a pè ní atọ́ka ìbá-ìṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹrẹ 'ń' àti ọ̀rọ̀-ìṣe méjì ti jẹyọ ní tẹ̀léǹtẹ̀lé, a lè fa fáwẹ̀lì ọ̀rọ̀-ìṣe kìíní tàbí àbọ̀ rẹ̀ gùn pẹ̀lú ohùn òkè tàbí kí á má fà á gùn bí a bá fẹ́

Adé ń bú wa á lọ
tàbí

Adé ń bú wa lọ
Ọbẹ̀ náà ṣe é jẹ
tàbí
Ọbẹ̀ náà ṣe jẹ

### 3.1.1.5 Olùwà + Kókó-Gbólóhùn

Bí sílébù ìparí àpólà orúkọ olùwà bá ni ohùn àárín gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀, tí ohùn òkè kò bá sì jẹyọ sáájú ohùn àárín yìí tàárà, tàbí tí sílébù tí ó parí àpólà orúkọ olùwà bá ní ohùn ìsàlẹ̀, tí ohùn ìsàlẹ̀ mìíràn sì jẹyọ sáájú ohùn ìsàlẹ̀ yìí, a ó yí ohùn àárín tàbí ohùn ìsàlẹ̀ ìparí àpólà orúkọ bẹ́ẹ̀ padà di ohùn òkè nínú àwọn gbólóhùn kan tí wọ́n ní ìhun olùwà àti kókó gbólóhùn

ẹlẹ́mu mi → ẹlẹ́mu mí tà
Abọ́ ẹ̀wà → abọ́ ẹ̀wá sonù
Òjò → òjó rọ̀ púpọ̀

### 3.1.1.6 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Ìsọ̀rí àwọn Wúnrẹ̀n kan

Tí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ ẹnì kẹta ọ̀pọ̀ olùwà *Wọ́n* ba jẹyọ sáájú àwọn wúnrẹ̀n kan tàárà (àwọn wúnrẹ̀n bí i: ìbá, ìbáà, yóó, kò/ò, kí) ohùn òkè tí i ṣe ohùn àdámọ́ rẹ̀ yóó yí padà sí ohùn àárín

Wọ́n
wọn ìbáà lọ
wọn yóó lọ
wọn ò lọ
wọn kìí lọ

### 3.1.1.7 Ọ̀rọ̀ Arọ́pò Orúkọ Olùwà + Wúnrẹ̀n 'a'

Bí ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ oluwà ẹnì kìíní tàbí ẹnì kejì ọ̀pọ̀ olùwà bá jẹyọ tàárà sáájú wúnrẹ̀n 'á' tí ó ń sisẹ́ àsìkò ọjọ́ iwájú, ohùn àárín ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ yìí lè yí padà di ohùn ìsàlẹ̀ tàbí kí ó máà yí padà.

a → a á lọ
tàbí
à á lọ
ẹ → ẹ ẹ́ lọ
tàbí
ẹ̀ ẹ́ lọ

Ó yẹ kí a fi kún un pé àràmọ́ ṣẹlẹ̀ nínú àpẹẹrẹ kejì níbí. Atọ́ka àsìkò ọjọ́ iwájú 'á' gbà àrànmọ́ àbùdá ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ olùwà ẹnì kejì ọ̀pọ̀ láti di irú rẹ̀.

## 3.1.1.8 Ọ̀rọ̀ Orúkọ + Ẹ̀yán

Bí àwọn ẹ̀yán kan bá yán ọ̀rọ̀ orúkọ, ìyípadà ohun a máa wáyé gẹ́gẹ́ bí a ó ṣe fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí láti inú àlàyé Owólabí (2013:129-130).
Bí ẹ̀yán bá jẹ́ ẹ̀yán ajórúkọ tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú kọ́nsónáàtì tàbí ọ̀rọ̀ arópọ̀ orúkọ kan, bí sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán ń yán kò bá ni ohùn àárín lórí, a gbọdọ̀ fa fáwẹ́lì sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán ń yán gùn pẹ̀lú ohùn àárín.

ọkọ̀ → ọkọ̀ọ Dúdú
bàtà → bàtàa Bọ́sẹ̀

Bí sílébù ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán ń yán bá ni ohùn àárín lórí tàbí tí ẹ̀yán bá jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú fawẹ́lì, a lè fa fáwẹ́lì sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ bẹ́ẹ̀ gùn pẹ̀lú ohùn àárín tàbí kí a má fà á gùn

àwo → àwoo Dàda
tàbí
àwo Dàda

ó ṣe é ṣe kí irú ìgbésẹ̀ yìí mú pọ́nna dán ni tàbí iyè méjì, bí ọ̀rọ̀ bá rí báyìí a gbọdọ̀ ṣe ìfàgùn sílébù ọ̀rọ̀ orúkọ. Wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí

ẹran → ẹran an dúdú
tàbí
ẹran dúdú

oun tí ó fojú hàn níbí ni pé, orúkọ ẹni tí ó ni ẹran akọ́kọ́ ni dúdú nítorí náà dúdú jẹ́ ẹ̀yán ajórúkọ nígbà tí dúdú kejì tí kò ní ìfàgùn sílébù jẹ́ ọ̀rọ̀ àpèjúwe tí ó ń sọ irú àwọ̀ tí ẹran kèjí ní. Nítorí náà, dúdú nínú gbólóhùn kejì jẹ́ ẹ̀yán asàpèjúwe. Ìfàgùn báyìí ni Bámgbóṣé (1990) fi ṣàlàyé dídá ọ̀rọ̀ orúkọ mọ̀.

Bí ẹ̀yán bá jẹ́ gbólóhùn àsọdorúkọ, a lè fa fáwẹ́lì sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán yìí ń yán gùn pẹ̀lú ohùn àárín tàbí kí a má fà á gùn

ayọ̀ → Mo yọ ayọ̀ọ pé Bọ́sẹ̀ bí ọmọ
tàbí
Mo yọ ayọ̀ pé Bọ́sẹ̀ bí ọmọ

Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe fi ojú hàn, a ó ṣe akìyèsí pé ìtumọ̀ gbólóhùn tí ìfàgùn tí wáyé yàtọ̀ sí ti èyí tí ìfàgùn fáwẹ́lì bẹ́ẹ̀ kò ti wáyé.
Bí sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ tí ẹ̀yán ń yán bá ni ohùn ìsàlẹ̀ èyí tí ohun ìsàlẹ̀ mìíràn saájú rẹ̀, bí ẹ̀yán bá sì jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ tí fáwẹ́lì olóhùn àárín bẹ̀rẹ̀ rẹ̀, ohùn sílébù ìparí ọ̀rọ̀ orúkọ yóó di ohùn àárín

èdè → ède ewì
ọ̀rọ̀ → ọ̀rọ ọmọ

ó yẹ kí a fi kún un pé àrànmọ́ ohùn ni ó ṣẹlẹ̀ nínú àpẹẹrẹ òkè yìí

## 3.1.1.9 Gbólóhùn Alátẹnumọ́

Gbólóhùn kan lè di alátẹnumọ́ nípa síṣe ìyípadà ohùn bí i:

Bí sílébù ìparí gbólóhùn bá ni ohùn òkè tàbí ohùn ààrín gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀, láti sọ irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ di gbólóhùn alátẹnumọ́, a ó fa fáwẹ́lì ìparí gbólóhùn náà gùn pẹ̀lú ohùn ìsàlẹ̀

Adé fà mí → Adé fà míì

Bọ́lá ga →Bọ́lá gaà

Bí sílébì ìparí gbólóhùn bẹ́ẹ̀ bá ni ohùn ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀, a le sọ gbólóhùn bẹ́ẹ̀ di alátẹnumọ́ fífa fáwẹ́lì sílébù ìparí gbólóhùn ọ̀hún gùn pẹ̀lú ohùn ààrín

Ọbẹ̀ náà sàn → Ọbẹ̀ náà sàn an

Adé gbá Dàpọ̀ → Adé gbá Dàpọ̀ọ

Ó yẹ kí ó di mímọ̀ pé, gbólóhùn alátẹnumọ́ ní ibi tí ìyípadà ohùn ti wáyé yìí ni a máa ń lò nígbà tí a bá ń já ẹnìyàn lẹ́gọ tàbí bí ènìyàn bá ń bínú sọ̀rọ̀ (rojọ́)

## 3.2 Isóhùnnípò àti Ìgbohùnnípò

Ìsóhùnnípò ni gbígbé ohùn kan láti ipò tí ó wà ló sí ipò mìíràn (ì-sí-ohùn-ní-ipò). Nígbà tí ìgbohùnnípò jẹ́ fífi ayè gba ohun tí a sí nípò ní ipò mìíràn (ì-gba-ohùn-ní-ipò). Mọ́yàmí ni àwọn méjéèjì, wọ́n sábá jọ máa ń wáyé ni. Amọ́ sá, ó ṣe é ṣe kí isóhùnnípò nikan wáyé láì sí ìgbohùnnípò ṣùgbọ́n ìgbohùnnípò kò lè wáyé láì sí ìsóhùnnípò.

| | (1) | (2) | (3) |
|---|---|---|---|
| i. | gbé àga | gb´àga | gbága |
| ii. | kọ ìwé | kọ `wé | kọ̀wé |
| iii. | wọ́n wà nílé | wọ́n wà n´lé | wọ́n wà ńlé |
| iv. | èmi ni mo lọ | emi n´mo lọ | emi m mo lọ |

Nínú àpẹẹrẹ òkè yìí ìgbésẹ̀ (1) fi ohùn tí a ó sí nípò hàn àti pàá pàá orí fáwẹ́lì tí ó ti jẹyọ. Ìgbésẹ̀ (2) fi hàn pé a pa fáwẹ́lì tí a ó si ipò rẹ̀ jẹ, èyí tí ó mí kí ohùn náà máa léfòó. Ìyẹn ni pé, ohùn náà kò ní fáwẹ́lì tí ó gbà á nítẹ̀ẹ́. Níwọ̀n ìgbà tí èdè Yorùbá kò sì fàyè gba ohùn aléfòó, a ní láti sí i nípò lọ ibi tí àyè yóó ti gbà á. Ní ìgbá tí ìgbésẹ̀ (3) fi hàn pé ohùn aléfòó tí ó jẹ́ àbájáde ìgbésẹ̀ (2) gbà ipò mìíràn. Ní àpẹẹrẹ (i) ohùn aléfòó gba ipò ọ̀rọ̀ tí ó tẹ̀lé ọ̀rọ̀ tí ìpajẹ ti wáyé tààrà ṣùgbọ́n ní àpẹẹrẹ (ii) ohùn aléfòó gba ipò ohùn tí ó saájú rẹ̀. Ó yẹ kí a fi kún un pé ohùn tí ohùn aléfòó gba ipò rẹ̀ yóó pòórá. Ní àpẹẹrẹ (iii-iv) a sí ohùn nípò lọ sí orí kọ́nsónáàtì tí kò ní ohùn kankan tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n tí a sọ di Kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù tí ó sì gba ohùn báyìí. Ìyẹn túmọ̀ sí pé, nínú àpẹẹrẹ yìí ìsóhùnnípò nìkan ló wáyé, ìgbésẹ̀ ìgbohùnnípò kà wáyé.

Ohun kan pàtàkì tí a gbọdọ̀ dì mú pẹ̀lú àlàyé òkè yìí ni pé, lẹ́yìn ìpajẹ ni ìgbésẹ̀ ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò máa ń wáyé. Èyí sì ni ìyàtọ̀ kan pàtàkì láàrin ìgbésẹ̀ méjéèjì yìí àti ìyípadà ohùn. Kò di dandan kí ìpajẹ fáwẹ́lì wáyé kí ìyípadà ohùn tó wáyé.

## 3.3 Lílo Ohùn

Ọ̀nà méjì ni Yorùbá ń gbà lo ohùn:

Fífi ìtumọ̀ àdámọ́ hàn
Fífi ìtumọ̀ gírámà hàn

### 3.3.1 Fífi Ìtumọ̀ Àdámọ́ Hàn

A máa ń lo ohùn láti fi ìyàtọ̀ itumọ̀ ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n tí kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì wọ́n jẹ́ ìkan-ùn. Apẹẹrẹ

| | | |
|---|---|---|
| bú | gbá | igbá |
| bù | gbà | igbà |
| bu | gba | igba |
| | | ìgbá |
| | | ìgbà |

ìfi ohùn kan rọ́pò èkejì yóó fa ìyàtọ̀ itumọ̀ fún àwọn ọ̀rọ̀ òkè yìí. Ohùn ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n ní ni ó jẹ́ kí á mọ̀ pé wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ pẹ̀lú ìtumọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.

### 3.3.2 Fífi Ìtumọ̀ Gírámà Hàn

Ohùn tún ṣe é lò láti fi ìyàtọ̀ ẹ̀hun gírámà kan hàn sí òmíràn.

i. Ayìẹ funfun
ii. Adìẹ́ funfun

Ìyàtọ̀ wo ni ó wà nínú ẹ́hun gírámà òkè méjéèjì yìí? Nígbà tí àkọ́kọ́ jẹ́ àpólà orúkọ, ní ibi tí a ti rí ọ̀rọ̀ orukọ (Adìẹ) àti ẹ̀yán rẹ̀ (ẹ̀yán asàpèjúwe). Ìkejì jẹ́ odidi gbólóhùn ní ibi tí a ti rí Àpólà orúkọ (Adìẹ) àti kókó gbólóhùn (funfun). Ohun tí ó fà ìyàtọ̀ yìí gan ni ohùn. Ohùn sílébù tí ó párí adìẹ nínú àpẹẹrẹ méjéèjì yàtọ̀, èyí ni ó sì fa ìyàtọ̀ ẹ̀hun gírámpa wọn.

## 3.4 Èrò Oyèbádé

Oyèbádé (2001) ṣàlàyé pé bí ìró ohùn méjì bá padé ní ààlà mọ́fíìmù, èyí tí ó bá lágbara jù ni yóó dúró, tí èkejì yóó sì pòórá tàbí kí ó sún lọ sí ibòmìíràn. Bí O ba dúró fún òkè, tí A dúró fún àárín, tí I sì dúró fún ìsàlẹ̀; àpẹẹrẹ tí Oyèbádé fún wa ni:

| | | |
|---|---|---|
| i. | O + I → O: | kó àre →káre |
| ii. | O + A →O: | ní ọ̀pá →lọ́pàá |
| iii. | A + A → A: | ta ayò → tayò |
| iv. | A + I → I: | jẹ ìgbágbùn →jẹ̀gbágùn |
| v. | I + I → I: | bà ẹ̀rù → bẹ̀rù |
| vi. | I + A → A: | rà ilẹ̀ → ralẹ̀ |

Ó ṣàlàyé pé ìdí tí àpẹẹrẹ vi rí bẹ́ẹ̀ ni pé, èdè Yorùbá ní òfin tí ó ń sọ ohùn ìsàlẹ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe di ohùn àárín tí ó bá gba ọ̀rọ̀-orúkọ gẹ́gẹ́ ní ipò àbọ̀ gẹ́gẹ́ bí a

ṣe fi hàn nínú àlàyé Owólabí (2013) nípa ìhun tí ìyípadà ohùn ti lè wáyé. Oyèbádé fi kún àlàyé rẹ̀ pé a kò rí O + O, A + O, àti I + O nítorí pé èdè Yorùbá kò fi àyè gba kí ọ̀rọ̀ tí fáwẹ́lì bẹ̀rẹ̀ rẹ̀ ní ohùn òkè ní ìbẹ̀rẹ̀.

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti wo ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn. A pe ìgbésẹ̀ yìí ni fífi ohùn kan rọ́pò òmíràn nínú ìsọ. A sọ pé lára ìgbésẹ̀ ajẹmóhùn ni ìyípadà ohùn, ìsóhùnnípò àti ìgbóhùnnípò àti aránmọ́ ohùn. A kò wo àránmọ́ ohùn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ṣùgbọ́n a fúnka mọ́ ìyípadà ohùn. A mẹ́nu bà á wí pé, ìyípadà ohùn ni kí ohùn ọ̀rọ̀ kan gẹ́gẹ́ bí ohùn àdámọ́ rẹ̀ yí padà sí ohùn mìíràn nígbà tí a bá lò ó nínú ìsọ. A fi ìhun tí ìyípadà ohùn ti lè wáyé hàn gẹ́gẹ́ bí Owólabí (2013) ṣe ṣàlàyé rẹ̀. A tún sọ̀rọ̀ nípa ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò. A ni àwọn méjèèjì lè wáyé ní tẹ̀ẹ́ǹtẹ̀lé ṣùgbọ́n ohun kan tí ó yà wọ́n sọ́tọ̀ sí ìyípadà ohùn ni pé, ìgbésẹ̀ ìpajẹ fáwẹ́lì kọ́kọ́ gbọ́dọ̀ wáyé kí àwọn tó lè wáyé, tí kò rí bẹ́ẹ̀ fún iyípadà ohùn.

A kò saì sọ̀rọ̀ lórí lílo ohùn. A pín eléyìí sí ọ̀nà méjì: fífi ìtumọ̀ àdámọ́ hàn àti fífi ìtumọ̀ gírámà hàn. Àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n ní kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì kan náà máa ń ní ìtumọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ nípa ohùn ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n ní. Ní ìgbà tí ìyàtọ̀ ohùn náà lè fa ìyàtọ̀ ẹ̀hun gírámà gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí:

i. Kí ni Ìyípadà ohùn?
ii. Ṣe àlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ ìhun tí ìyípadà ohun ti máa ń wáyé márùn-ún
iii. Ìyàto pàtàkì wo ni ó wà láàrin ìyípadà ohùn àti ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Bámgbóṣé Ayọ̀ (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan, University Press Ltd

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

Oyèbádé Francis (2001) Ìgbẹ́ṣẹ̀ àti Ìlànà Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Olóòtú: Bádé Àjàyí

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KEJÌ

# ÀRÀNMỌ́

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́
3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Ẹ̀yà (orísìí) Àrànmọ́
3.2 Àrànmọ́ ohùn àti Àrànmọ́ Fáwẹ́lì
3.2.1 Àrànmọ́ Ohùn
3.2.2 Àrànmọ́ Fáwẹ́lì
3.3 Ìhun tí Àrànmọ́ ti Máa ń wáyé
4.0 Conclusion
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kọjá, a mẹ́nu ba àrànmọ́ ohùn gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ìgbésẹ̀ ajẹmọ́ ohùn ṣùgnọ́n a kàn dárukọ rẹ̀ ni, a kò ṣàlàyé rẹ rárá. A ní a ó máa sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ níwájú. Àkókò náà tó wàyí láti wo àràmọ́ ní odidi. Àwọn ohun tí a ó pẹ̀kẹ́ lù ni ẹ̀yà àrànmọ́, ìhun tí àrànmọ́ ti lè wáyé tó bẹ́ẹ̀ tí akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè sọ ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ìró agbàrànmọ́ àti ìró afàrànmọ́.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

- ṣo orísìí ẹ̀yà àrànmọ́ tí ó wà
- pààlà sáàrin ìró agbàrànmọ́ àti ìró afàrànmọ́

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ẹ̀kọ́

Gbìyànjú láti dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí:

1. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ sọ àwọn ẹ̀yà àrànmọ́ tí ó wà nínú èdè Yorùbá
2. Pààlà sáàrin ìró agbàrànmọ́ àti ìró afàrànmọ́.

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Kí ni àrànmọ́? Àrànmọ́ ni agbára tí ìró kan ni láti sọ ìró mìíràn ti irú ara rẹ̀. Owólabí (2013:189) kì àraǹmọ́ báyìí: Àrànmọ́ gẹ́gẹ́ bí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì

tọ́ka sí agbára tí ìró kan ní lórí (pípe) ìró mìíràn èyí tí ó lè mú kí ìró méjéèjì di ọ̀kan-ùn tàbí kí wọ́n fi nǹkankan jo ara wọn. Ìyí túmọ̀ sí pé ìró kan lè mú gbogbo àbùdá ìró kan tàbí kí ó mú lára àbùdá ìró mìíròn. Àpẹẹrẹ ni

ọdún ọdún → ọdọọdún

ọ̀wọ́ ọ̀wọ́ → ọ̀wọ̀ọ̀wọ́

nínú àpẹẹrẹ àkọ́kọ́ ìró 'un' mú gbogbo àbùdá ìró 'ọ' tí ó sì yí fáwẹ́lì 'un' di 'ọ'. Àpẹẹrẹ kejì fi ohùn òkè hàn pé ó mú àbùdá ohùn ìsàlẹ̀.

Ìró tí ìró mìíràn mú lára abùdá rẹ̀ tàbí gbogbo àbùdá rẹ̀ ni a mọ̀ sí ìró ***afàrànmọ̀***. Nígbà tí ìró tí ó mú gbogbo àbùdá tàbí lára àbùdá ìró mìíràn ni a mọ̀ sí ìró ***agbàrànmọ́.*** Bámgbóṣe (1990:47) sọ pé, nígbà tí ìró kan bá yí padà láti fara jọ ìró mìíràn, irú ìyípadà báyìí ni àrànmọ́. Ìró tí ó yí padà ni ó gba àrànmọ́ sára. Nítorí náà a lè pè é ní agbàrànmọ́. Ìró tí ó mú kí èkejì gba àrànmọ́ ni ó máa ń ràn mọ́ ìró mìíràn. Nítorí èyí a lè pè é ní afàrànmọ́. A wá lè fi àpẹẹrẹ òkè yìí ṣe àlàyé àwọn kókó ọ̀rọ̀ méjéèjì (afàrànmọ́ àti agbàrànmọ́) báyìí; ìró 'ọ' ni ìró afàràmọ́ nítorí pé òun ni ìró mìíràn mú àbùdá rẹ̀. Ìró 'un' sì ni ìró agbàrànmọ́ nítorí pé, oun ni ó mú àbùdá ìró mìíràn.

## 3.1 Ẹ̀yà (Orísìí) Àrànmọ́

Bí a bá lo òsùnwọ̀n ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, àwọn wọ̀nyí ni orísìí àrànmọ́ tí ó fojú hàn jù nínú èdè Yorùbá:

(a) Àrànmọ̀wájú àti Àrànmẹ́yìn
(b) Àrànmọ́ aláìfòró àti Àrànmọ́ afòró
(d) Àrànmọ́ kíkún àti Àrànmọ́ Ẹlẹ́bẹ

**(a) Àrànmọ̀wájú àti Àrànmẹ́yìn**

Bí a bá lo apá ọ̀tún àti apá òsì, tí a sì gbà pé apá ọtún wà ní iwájú apá òsì tí ìró afàrànmọ́ tí ó wà ní apá òsì lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ lọ sí iwájú lọ bá ìró agbàrànmọ́ láti sọ ọ́ ti irú ara rẹ̀, èyí ni a mọ̀ sí àrànmọ́wájú.

ilé ìwé → iléèwé
a ò wá → a à wá
owó iṣẹ́ → owóoṣẹ́

Ṣùgbọ́n bí ìró afàrànmọ́ bá wà ní apá ọ̀tún tí ó wá lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ sẹ́yìn lọ bá ìró agbàrànmọ́ tí ó wà ní apá òsì, a ó pe irú àrànmọ́ bẹ́ẹ̀ ní àrànmẹ́yìn.

ọdún ọdún → ọdọọdún
ará ọ̀run → arọ́ọ̀run
ará oko → aróoko

**(b) Àrànmọ́ aláìfòró àti Àrànmọ́ afòró**

Bí a bá lo òsùnwọ̀n bí ìró mìíràn bá jẹ yọ láàrin ìró afàrànmọ́ àti agbàrànmọ́ tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́, a lè ya àrànmọ́ sí afòró àti aláìfòró.

Àrànmọ́ aláìfòró ni ní ìgbà tí kò bá sí ìró mìíràn láàrin ìró afàrànmọ́ àti ìró agbàrànmọ́. Àpèèrè ni

ilé ìwé → iléèwé
ará ọ̀run → arọ́ọ̀run
kú àbọ̀→káàbọ̀
ọmọ àlè → ọmààlè

Àmọ́, bí ìró mìíràn bá wà lára ìró afàrànmọ́ àti ìró agbàrànmọ́, irú àrànmọ́ bẹ́ẹ̀ ni a mọ̀ sí àrànmọ́ afòró. Àpẹẹrẹ ni:

oní + ata → aláta
oní + ẹja → ẹlẹ́ja
oní + ewé → eléwé

A ó rí pé ìró méjì ló wà láàrin ìró agbàrànmọ́ àti ìró afàrànmọ́.

**(d) Àrànmọ́ Kíkún àti Àrànmọ́ Ẹlẹ́bẹ**

Tí ìró afàrànmọ́ bá lo agbára àrànmọ́ rẹ̀ láti jẹ́ kí ìró àgbàrànmọ́ mú gbogbo àbùdá ìró afàrànmọ́ tó bẹ́ẹ̀ tí ìró afàrànmọ́ àti ìró agbàrànmọ́ di ọ̀kan-ùn, irú àrànmọ́ bẹ́ẹ̀ ni a mọ̀ sí àrànmọ́ kíkún. Àpẹẹrẹ ni:

ọdún + ọdún → ọdọọdún
ọmọ + àlè → ọmààlè

a ṣe àkíyèsí pé ìró 'un' tí ó ní ohùn òkè gba gbogbo àbùdá ìró 'ọ' olóhùn àárín tí ó jẹ́ ìró afàrànmọ́ pẹ̀lú gbogbo àbùdá rẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí àwọn méjéèjì fi di ọ̀kan-ùn. Ohun kan náà ni ó ṣẹlẹ̀ ni àpẹẹrẹ kejì ní ibi tí ìró ọ tí ó gbẹ̀yìn ọmọ sọ àbùdá rẹ̀ nù láti mú àbùdá ìró a tí ó bẹ̀rẹ̀ àlè pẹ̀lú ohùn rẹ̀.

Àmọ́ tí ìró agbàrànmọ́ bá mú apá kan lára àbùdá ìró afàrànmọ́, a jẹ́ pé irú àrànmọ́ bẹ́ẹ̀ jẹ́ àrànmọ́ ẹlẹ́bẹ. Àpẹẹrẹ ni:

ìwọ̀nyí → ìwọ̀nín

ó wà níbí → ó wà ńbí → ó wà ḿ b̄í

ohun tí ó sẹlẹ̀ níbí ni pé, ìpajẹ ìró 'y' fi àǹfààní sílẹ̀ fún ìró 'i' láti mú ìránmú ìró 'ọ́n' tí òun náà fi di ìró aránmúpè 'in'. Ìpajẹ fáwẹ́lì nínú ọ̀rọ̀ 'níbí' sọ kọ́nsónáǹtì [n] di kọ́nsónáǹtì aránmú aṣesílébù. Ṣùgbọ́n torí pé ó ń jẹyọ s̄áájú kọ́nsónáǹtì afèjì-ètè-pè, òun náà mú àbùdá yìí láti sọ ọ́ di 'ḿ b̄í'

## 3.2 Àrànmọ́ Ohùn àti Àrànmọ́ Fáwẹ́lì

Bámgbóṣé (1990) ni àrànmọ́ lè jẹ́ àrànmọ́ ohùn àtí àrànmọ́ fáwẹ́lì

### 3.2.1 Àrànmọ́ Ohùn

Àrànmọ́ ohùn ni ìyípadà ohùn kan láti fara jọ ohùn mìíràn. Bí àpẹẹrẹ

eégún → eégún
oókan → óókan
aájò → áájò

eérú → éérú

ohun tí ó fojú hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí ni pé ohùn òkè ràn mọ́ ohùn àárín.

oògùn → òògùn
eèpẹ̀ → èèpẹ̀
oòrùn → òòrùn
ò-ṣìṣẹ́ → òṣìṣẹ́
ò-jowú → òjòwú

a ṣàkíyèsí pé ohùn ìsàlẹ̀ ràn mọ́ ohùn àárín nínú àpẹẹrẹ òkè yìí

ọ̀rọ̀ ọmọ̀ → ọ̀rọ ọmọ
irú ẹran → iru ẹran
igò epo → igo epo

ohun tí ó fojú hàn níbí ni pé ohùn àárín ràn mọ́ ohùn ìsàlẹ̀

ẹgbẹ́ ẹgbẹ́ → ẹgbẹẹgbẹ́
ọjọ́ ọjọ́ → ọjọọjọ́

àrànmọ́ tí ó wáyé níbí ni pé ohùn àárín sọ ohùn òkè di irú ara rẹ̀

ọ̀wọ́ ọ̀wọ́ → ọ̀wọ̀ọ̀wọ́
èló èló → èlèèló

àpẹẹrẹ yìí fi hàn pé ìró ohùn ìsàlẹ́ sọ ohùn òkè di irú ara rẹ̀.

### 3.2.2 Àrànmọ́ Fáwẹ́lì

Àrànmọ́ fáwẹ́lì ni ìyípadà fáwẹ́lì kan l;ati fara jọ fáwẹ́lì mìíràn. Bámgbóṣé (1990) ní tí $F_1$bá dúró fún fáwẹ́lì àkọ́kọ́, tí $F_2$ bá dúró fún èkèjì, ó wá gbé òfin àrànmọ́ yìí kalẹ̀

$$F_1 + F_2 \rightarrow F_1 + F_1$$

Tàbí

$$F_2 + F_2$$

Èyí túmọ̀ sí pé bí fáwẹ́lì máàjì bá pàdé ní ààlà sílébù, ó ṣe é ṣe kí ọ̀kan nínú àwọn mú àbùdá èkejì. Àpẹẹrẹ ni

ilé iṣẹ́ → iléeṣẹ́
kú iṣẹ́ → kúuṣẹ́
ẹ̀rù igi → ẹ̀rùugi

Bámgbóṣé wá ṣe àfihàn àpẹẹrẹ kòbẹ́gbẹ́mu òfin yìí. Ó ní i tàbí in kò gba àrànmọ́ lára fáwẹ́lì tàbí kọ́nsónáǹtì aránmúpè aṣesílébù tí ó fẹ́gbẹ́ tìí

mí ò lọ → mi ìn lọ
kì ń parọ́ → kì í parọ́.

## 3.3 Ìhun tí Àrànmọ́ ti máa ń wáyé

Àrànmọ́ fáwẹ́lì máa ń jẹyọ nínú àwọn ẹ̀hun wọ̀nyí:

1. Ọ̀rọ̀-Orúkọ àti Ọ̀rọ̀- Orúkọ

   Nínú ẹ̀hun yìí, fáwẹ́lì i tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ kejì gbọdọ̀ yí padà láti gba àrànmọ́ lára fáwẹ́lì tí ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ kìíní nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

ilé ilẹ̀ → iléelẹ̀
ọ̀rọ̀ iṣẹ́→ ọ̀rọọṣẹ́
ètò ìlú → ètòòlú

Bámgbóṣé pe àkíyèsí wa sí i pé bí fáwẹ́li i bá gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ kìíní, irú àrànmọ́ òkè yìí kìí sábá wáyé:

ìdí omi → *ìdóomi
orí oko → *oróoko

Àmọ́ ni ti àwọn fáwẹ́lì tí ó kù, tí àrànmọ́ bá wáyé, fáwẹ́lì tí ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ kìíní ni ó máa ń gba àrànmọ́ lára fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ kejì.

ará oko → aróóko
ìyá ẹgbẹ́ → ìyẹẹgbẹ́
aṣọ òkè → aṣoòkè
ọmọ oko → ọmooko

ó fi kún un pé kì í ṣe gbogbo ọ̀rọ̀-orúkọ àti ọ̀rọ̀-orúkọ ni a máa ń ṣe àrànmọ́ fún. Bí àpẹẹrẹ

adé ọba → *adọọba
ewé obì → *ewóobì
ijó agbo → ijáagbo

2. Awọn wúnrẹ̀n gírámà kan àti ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ gẹ́gẹ́ bí olùwà. Àwọn wúntẹ̀n gírámá bí ǹjẹ́, ṣèbí/ṣebí, àní, àṣé, tí, tàbí/àbí, pé, kí, bí. Fáwẹ́lì àwọn wúnrẹ̀n yìí ni ó máa gba àrànmọ́

ǹjẹ́ o lọ? → ǹjó o lọ?
ṣé o lọ? → ṣó o lọ?
ó yẹ kí o lọ → ó yẹ kó o lọ

àwọn kòbẹ́gbẹ́mu kan wà tí a máa ń ṣe fáwẹ́lì pípajẹ fún dípò àrànmọ́. Àpẹẹrẹ ni

bí o bá lọ → * bó ó bá lọ
bí o bá lọ → b'ó bá lọ

3. Ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ gẹ́gẹ́ bí olùwà àti Atọ́ka ìyísódì
Atọ́ka ìyísódì máa ń gba àrànmọ́ lára ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ

mì ò lọ → mì ìn lọ
ẹ ò lọ → ẹ ẹ̀ lọ
wọn ò lọ → wọn ọ̀n lọ

4. Ọ̀rọ̀-ìṣe Kú àti Ọ̀rọ̀-orúkọ
Nínú ẹ̀hun yìí **u** ni ó máa ń gba àrànọ́ lára fáwẹ́lì mìíràn

kú àbọ̀→ káàbọ̀
kú iṣẹ́ → kuuṣẹ́
kú alẹ́ → káalẹ́

akíyèsí ni pé kú + iṣẹ́ tako àgbékalẹ̀ Bámgbóṣé tí ó sọ pé ìró **u** ni ó gba àrànmọ́ ṣùgbọ́n níbí òun ni ó fa àrànmọ́. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé kò tíì sí òfin gbéetán fún àrànmọ́ èdè Yorùbá

5. Àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ oní àti Ọ̀rọ̀-orúkọ
Nínú ẹ̀hun yìí, fáwẹ́lì ó nínú oní ni ó má ń gba àrànmọ́ lára fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ. Kí èyí tó lè rí bẹ́ẹ̀, kọ́nsónáǹtì n gbọ́dọ̀ di l. Èyí sì máa ń rí bẹ́ẹ̀ tí fáwẹ́lì tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ kì í bá ṣe i.

oní ata→ aláta
oní ẹja→ ẹlẹ́ja
oní ewé → eléwé

6. Olùwà àti wúnrẹ̀n ìbá tàbí ìbáà
Fáwẹ̀lì i ni ó máa ń gba àrànmọ́ nínú ẹ̀hun yìí
ọ̀rọ̀ ìbá jáde → ọ̀rọ̀ọ̀ bá jáde
ìlú ìbáa tú → ìlúù báa tú
àwa ìbá lọ → àwaà bá lọ

7. Ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ gẹ́gẹ́ bí olùwà àti wúnrẹ̀n á
Nínú ẹ̀hun yìí, kan-ńpa ni fún wúnrẹ̀n á láti para dà di ẹ. Ṣùgbọ́n wọ̀fún ni àrànmọ́ pẹ̀lú fáwẹ̀lì inú wọ́n.
*ẹ̀ á lọ → ẹ̀ ẹ́ lọ
Wọ́n á lọ → wán án lọ

8. Atọ́ka ibá-ìsẹ̀lẹ̀ **ń** nínú àwọn ẹ̀hun kan
Atọ́ka ìbá-ìsẹ̀lẹ̀ ń ni ó máa ń gba àrànmọ́ nínú àwọn ẹ̀hun wọ̀nyí:

(i) Pẹ̀lú atọ́ka ìyísódì kì
kì ń jáde → kì ń jáde
wọn kì ń sèkà→ wọn kì í sèkà

(ii) Pẹ̀lú tí tàbí ni
ọ̀rọ̀ tí ń túlé → ọ̀rọ̀ tí í túlé
ojú oró ni ń lékè omi → ojú oró ní í lékè omi

(iii) Pẹ̀lú ibá-ìsẹ̀lẹ̀ ń kejì
*ó ń bá wọn ń lọ → ó ń bá wọn ọn lọ
*ó ń sọ̀rọ̀ ń bọ̀ → ó ń sọ̀rọ̀ ọ́ bọ̀

9. Ọ̀rọ̀-ìṣe àti Ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀bọ̀rọ́
Nínú ẹ̀hun yìí, í tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe ọ̀bọ̀rọ́ gbọ́dọ̀ gba àrànmọ́ lára fáwẹ́lì tí ó sáájú rẹ̀
ó ṣòro i ṣe → ó ṣòro ó ṣe
ó fẹ́rẹ̀ í dé → ó fẹ́rẹ̀ ẹ́ dé

10. Ẹ̀hun tàbí ọ̀rọ̀ nínú èyí tí a ti ṣe kọ́nsónáǹtì pípajẹ
Lẹ́yìn tí a bá pa kọ́nsónáǹtì jẹ, àrànmọ́ máa ń wáyé. Ẹ jẹ́ kí a wo àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí
lọ sílé → lọọlé
òtítọ́ → òótọ́
ẹ̀rìnméjì → ẹ̀ẹ̀mejì

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti wo agbára tí ìró kan ni láti sọ ìró mìíràn di irú ara rẹ̀. A pààlà sáàrín ìró afàrànmọ́ àti ìró agbàrànmọ́. a sì wo ẹ̀yà àrànmọ́ tí ó wà ní èdè Yorùbá; àwọn bí i àrànmọ́wájú, àrànmẹ́yìn, arànmọ́ aláìfòró, arànmọ́ afòró, arànmọ́ kíkún àti arànmọ́ ẹlẹ́bẹ. A kò sài mẹ́nu ba àrànmọ́ ohùn àti àrànmọ́ fáwẹ̀lì àti ìhun tí àrànmọ́ fáwẹ̀lì ti máa ń wáyé

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Gbìyànjú láti dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí:

1. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ sọ àwọn ẹ̀yà àrànmọ́ tí ó wà nínú èdè Yorùbá
2. Pààlà sáàrin ìró agbàrànmọ́ àti ìró afàrànmọ́.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Bamgbose Ayo (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan. University Press Limited

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tîìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited.

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KẸTA

## ÌPAJẸ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròngbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀a
3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Ìpajẹ Kọ́nsónáǹtì
3.2 Ìpajẹ Fáwẹ́lì
3.2.1 Ìhun tí Ìpajẹ Fáwẹ́lì ti lè Wáyé
3.3 Ìpajẹ Ohùn
4.0 Conclusion
5.0 Ìsonísókí
6.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ìgbẹ́sẹ̀ fonọ́lọ́jì kan pàtàkì tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ tí a bá ń sọ̀rọ̀ ni ìró pípajẹ. Kókó ohun ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí dá lé lórí gba-an ni ìró pípajẹ. A ó fún ka mọ̀ àwọn ìró tí a lè pa jẹ àti sàkání tí a lè ti pá wọ́n jẹ.

## 2.0 ÈRÒNGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

- Ṣàlàyé ìpajẹ fáwẹ́lì àti kọ̀nsónáǹtì
- Tọ́ka sí ìhun tí ìpajẹ fáwẹ́lì ti lè wá yé

## 2.1 Ìdánwò Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀a

a. Ṣàlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ ìpajẹ fáwẹ́lì àti kọ̀nsónáǹtì
b. Tọ́ka sí ìhun tí ìpajẹ fáwẹ́lì ti lè wá yé

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Kí ni ìpajẹ?
Nígbà tí ìró bá sọ nù nínú ọ̀rọ̀, àpólà tàbí gbólóhùn bí a ti hun ìsọ ni àwọn onímọ̀ fonọ́lọ́jì máa ń sọ pé ìpàrójẹ ti wáyé (Oyèbádé 2001:72). Ẹ̀wẹ̀, Owólabí (2013:172) rí ìpajẹ gẹ́gẹ́ bí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì kan, tí fifo àwọn ìró tàbí sísọ àwọn ìró nù nígbà tí a bá ń safọ̀ geere. Fáwẹ́lì, kọ́nsónáǹtì, ohùn àti àpapọ̀ wọn ni a lè pa jẹ.

## 3.1 Ìpajẹ Kọ́nsónáǹtì

Oyèbádé (2001) sọ pé Oyèláràn (1971) ní ìró kọ́nsónáǹtì r, w, àti y ni a máa ń pa jẹ jù lédè Yorùbá. Àpẹẹrẹ ni

Ìpajẹ r

| (a) | (b) |
|---|---|
| kúrò → kúò | dára → dáa |
| koríko → koóko | fẹ́rẹ̀ → fẹ́ẹ̀ |
| orúkọ → oókọ | àkàrà → àkàà |

Oyèbádé ni Oyèláràn kò fún wa ní ofin tí a lè tẹ̀lé láti ṣe ìpajẹ. Ó wa sọ pé Akinlabí (1990) gbé òfin méjì kalẹ̀:

i. Pa r jẹ bí ó bá sú yọ láàrin fáwẹ̀lì méjì tí ó jọ ara wọn;

ii. Pa r jẹ láàárín fáwẹ̀lì méjì bí ọ̀kan nínú wọn bá jẹ́ àhánupè

Àpẹẹrẹ ni:

a
kúrò → kúò
koríko → kóoko
òrìsà → òòsà
àdúrà → adúà

b
dára → dáa
fẹ́rẹ̀ → fẹ́ẹ̀
oríkì → oókì
ẹ̀rẹ̀kẹ́ → ẹ̀ẹ̀kẹ́

Akinlabí wá tọ́ka sí àwọn àyàfi kan, ọ̀kan lára wọn sì ni pé, a kò lè pa r jẹ bí ó bá jẹ́ pé òun nìkan ni kọ́nsónáǹtì tí ó wà nínú ọ̀rọ̀ náà:

ara → * aa
ọ̀rọ̀ → *ọ̀ọ̀
ìró → *ìó

àwọn kòbẹ́gbẹ́mu mìíràn ni

ewúrẹ́ → *ewúẹ́
yàrá → * yàá
ọgọ́rin → *ọgọ́in abbl

Ìpajẹ w

Ìró kọ́nsónáǹtì mìíràn tí a lè pajẹ ni w nínú ọ̀rọ̀ bí i:

báwo → bá o → bóo
kéwú → kéú
ọmọlúwàbí → ọmọl;upabí

Ìpajẹ y

Ìró kọ́nsónáǹtì mìíràn tí a lè pa jẹ ni ìró y

Àjàyí → Àjàí
láyé → láé
gbáríyẹ̀ → gbáríẹ̀
adìyẹ → adìẹ

Ìpajẹ h

Ìró kọ́nsónáǹtì mìíràn ti a lè pajẹ ni ìró h

gbohungbohùn → gboungbou

kẹ́hìndé → kẹ̀índé

Ìpajẹ l

Méjìlélógún → méjìélógún
tilẹ̀ → tiẹ̀

Ìpajẹ k

kò → ò
ọlákìítán → ọláìítán
àkíké → àíké → àáké
èkíkánná → ìíkánná → èékánná
ọ̀kánkán → ọ̀ánkán → ọ̀ọ̀kán

## 3.2 Ìpajẹ Fáwẹ́lì

Nígbà tí fáwẹ́lì méjì bá dúró ti ara wọn pẹ̀lú ohùn orí wọn ní tẹ̀léǹtẹ̀lé ní ààlà mọ́fíìmù, a lè pa ọ̀kan lára àwọn fáwẹ́lì méjéèjì jẹ pẹ̀lú ohùn orí wọn

Kó ẹja → kẹ́ja
ta ẹran → tẹran
fẹ́ owó → fówó
fẹ́ ọwọ́ → fẹ́wọ́

### 3.2.1 Ìhun tí Ìpajẹ Fáwẹ́lì ti lè Wáyé

Oyèbádé (2001) tọ́ka sí Owólabí (1989) tí ó ti di àtúntẹ̀ ní (2013) pé àwọn wọ̀nyí ni ìhun tí ìpajẹ fáwẹ́lì ti máa ń wáyé

i. Inú Àpólà Orúkọ:
Ìdí ọkọ̀ → ìdíkọ̀
etí odò → etídò
ìyá ọkọ → ìyakọ
ewé oko → ewéko

ii. Inú àsopọ̀ oní pẹ̀lú ọ̀rọ̀ orúkọ
Oní iṣu → oníṣu
Oní ìwààsù → oníwààsù
Oní ìgbàgbọ́ → onígbàgbọ́
Oní ijàngbọ̀n → onígbàgbọ̀

iii. Àlàfo ọ̀rọ̀-ìṣe àti ọ̀rọ̀ orúkọ
ṣẹ́ oyún → sẹ́yún
dá owó → dáwó
tẹ́ ewé → tẹ́wé

iv. ọ̀rọ̀ ìṣe àti ọ̀rọ̀ arọ́pò-orúkọ
gbé e → gbe
tu ú → tu
pa á → pá

v. àwọn ìhun mìíràn

àfi ẹ̀yin náà → afẹ̀yin náà
àti àwọn náà → àtàwọn náà
Ṣé Adé wá? → Ṣádé wá

vi. oní itumọ̀ àkànlò
rán etí → rántí
fẹ́ ọwọ́ → fẹ́wọ́
yí owó → yíwó
gbé ẹsẹ̀ → gbésẹ̀

## 3.3 Ìpajẹ Ohùn

Owólabí (2013: 178) ṣàlàyé pé lẹ́yìn ìpajẹ fáwẹ́lì ni ipajẹ ohùn máa ń wáyé. O fi kún un pé ní ìgbá mìíràn ìpajẹ ohùn lè wáyé lẹ́yìn ìgbésẹ̀ ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò. Ó tún ṣàlàyé àwọn ìhun tí ìpajẹ ohùn ti máa ń wáyé ṣùgbọ́n àyè kò ní gbà wá láti wò àwọn ìhun yìí a ó kan ṣe àpẹẹrẹ ni.

bí ó → bó (bí o bá lọ → bó bá lọ)
bátà ó pọ̀ → bàtà pọ̀
ní ìmọ̀ → nímọ̀

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSONÍSÓKÍ

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti wo ìpajẹ gẹ́gẹ́ bí i ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì. Àwọn onímọ̀ ṣàlàyé pé ìpajẹ yìí ni ó ya elédè sọ́tọ̀ sí ẹni tí ó sẹ̀sẹ̀ ń kọ́ èdè. Awo orísìí ìpajẹ inú èdè Yorùbá bí i ìpajẹ kọ́nsónáǹtì, ìpajẹ fáwẹ́lì àti ìpajẹ ohùn. A wo àwọn ìhun tí ìpajẹ fáwẹ́lì ti lè wáyé.

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

a. Ṣàlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ ìpajẹ fáwẹ́lì àti kọ́nsónáǹtì
b. Tọ́ka sí ìhun tí ìpajẹ fáwẹ́lì ti lè wá yé

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Owólabí Kọ́lá (2013) *Ìjìnlẹ̀ Ìtúpalẹ̀ Èdè Yorùbá (1): Fónẹ́tíìkì àti Fonọ́lọ́jì*. Ibadan. Universal Akada Books Nigeria Limited

Oyèbádé Francis (2001) Ìgbẹ́sẹ̀ àti Ìlànà Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Olóòtú: Bádé Àjàyí

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KẸRIN

# ÌSỌDÀRÁNMÚPÈ ÀTI ÌSỌDÀÌRÁNMÚPÈ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròngbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Ìsọdaránmúpè
3.1.1 Ìsọ-kọ́nsónáǹtì-di-aránmú
3.1.2 Ìsọ-fáwẹ̀lì-di-aránmúpè
3.1.2.1Ìsọ-fáwẹ́lì-di-arámúpè-àárín-ọ̀rọ̀
3.1.2.2Ìsọ-fáwẹ́lì-di-arámúpè-ààlà-ọ̀rọ̀
3.2 Ìsọdàìránmúpè
3.2.1 Ìsọdàìránmúpè alárànmọ́
3.2.2 Ìsọdàìránmúpè onípajẹ
4.0 Conclusion
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Ìdánwo Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
8.0Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ọ̀kàn lára àwọn àkòrí ọ̀rọ̀ tí ó ye kí a mẹ́nu bà ni ìsọdàránmúpè àti ìsọdàìránmúpè. Ìdí fún yìí ni pé púpọ̀ àkẹ́kọ̀ọ́ ni kò mọ ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ìró aránmúpè àti ìró tí a sọ di àránmúpè. Ohun tí ó dájú ni pé ìyàtọ̀ wà láàrin àwọn méjéèjì. Èyí gàn-an sì ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí dá lé lórí. A sì ní ìrètí pé lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè dá ìró àránmúpè àti ìró tí a sọ di aránmúpè. A ní ìrètí pé, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè ṣàlàyé ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí ó ń sọ ìró aránmúpè di àìránmúpè pẹ̀lú àpẹẹrẹ tí ó míná dóko.

## 2.0 ÈRÒNGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

- Tọ́ka sí àwọn ìró àránmúpè yàtọ́ sí ìró àsọdaránmúpè
- Ṣàlàyé ìgbésẹ̀ ìsọdàìránmúpè

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ìró tí a pè nígbà tí afàsé wá sílẹ̀, tí èémí ń gbà imú àti ẹnu jáde ni a mọ̀ sí ìró aránmúpè. Àpẹẹrẹ irú ìró kọ́nsónáǹtì bẹ́ẹ̀ ni ìró [n] àti ìró [m]. Àpẹẹrẹ ìró fáwẹ́lì rẹ̀ ni [ĩ], [ã], [ũ], [ɔ̃], àti [ɛ̃]. Ohun kan pàtàkì tí ó yẹ kí a mọ̀ ni pé, ìránmú jẹ́ ọ̀kan lára àbùdá àwọn ìró tí a fi ṣe àpẹẹrẹ yìí. Èyí yàtọ̀ sí àwọn ìró tí wọn kò ní àbùdá ìránmú láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ṣùgbọ́n tí wọn gba

àbúdá yìí nípa ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì. Ìyẹn túmọ̀ sí pé a sọ ìrú àwọn ìró bẹ́ẹ̀ di ìránmú ni. Àwọn ìró bẹ́ẹ̀ ni à ń pè ní asọdàránmúpè tí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì bẹ́ẹ̀ sì ń jẹ́ ìsọdaránmúpè.

## 3.1 Ìsọdaránmúpè

Èyí ni ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ní ibi tí ìró àìránmúpè ti máa ń gbà àbùdá ìránmúpè. Àwọn onímọ̀ kan rí i gẹ́gẹ́ bí àrànmọ́, nítorí pé, ìró tí kìí ṣe aránmúpè yìí gba àbùdá ìró mìíràn ni láti ní àbùdá ìránmúpè. A lè ṣe àpẹẹrẹ ìró kọ́nsónáǹtì ati fáwẹ́lì. A ó kọ́kọ́ wo àpẹẹrẹ ìró kọ́nsónáńtì ná, kí a tó wo àpẹẹrẹ ìró fáwẹ́lì.

### 3.1.1 Ìsọ-kọ́nsónáǹtì-di-aránmú

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Oyelaran (1971) àti Pulley blank (1988:258), wọ́n ṣàlàyé pé àwọn ìró adún (b.a [r,w,y,h]) a máa gba ìránmú bí wọ́n bá jẹyọ ni àgbègbè tí ìránmú bá wà. Ìyẹn ni pé bí ìró [r], [w], [y] àti [h] bá jẹyọ saájú ìró fáwẹ́lì aránmúpè, wọ́n yóó yípadà di [r̃], [w̃], [ỹ] àti [h̃] nínú àpẹẹrẹ bí i

rìn /rĩ̀/ ==> [r̃ĩ̀]
wọ́n /wɔ̃́/ ==> [w̃ɔ̃́]
yún /jṹ/ ==> [j̃ṹ]
hun /hũ/ ==> [h̃ũ]

A ó ṣàkíyèsí pé, àwọn ìró fáwẹ́lì aranmúpé tí wọ́n jẹyọ saájú àwọn ìró adún yìí ni ó fà á tí àwọn ìró kọ́nsónáǹtì yìí náà fi gba àbúdá aránmú. Èyí sì ni a lè pè ni ìsọ-kọ́nsónáǹtì-di-aránmúpè.

### 3.1.2 Ìsọ-fáwẹ̀lì-di-aránmúpè

Èyí ni sísọ ìró fáwẹ́lì tí ó jẹ́ àìránmúpè dí aránmúpè nítorí pé ó gba àbúdá ìránmú yìí lára ìró aránmú tí ó fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú rẹ̀. A ó wo àpẹẹrẹ níbi tí ìró fáwẹ́lì ti gba ìránmú láti ara kọ́nsónáǹtì aránmúpè. A ó sì tún wò ó níbi tí wọ́n ti gba ìránmú láti ibi ti ọ̀rọ̀ méjì ti pàálà.

#### 3.1.2.1 Ìsọ-fáwẹ́lì-di-arámúpè-àárín-ọ̀rọ̀

Ìgbésẹ̀ yìí ni sísọ ìró fáwẹ́lì tí ó jẹ́ pé ó jẹ́ àìránmúpè di aránmúpè ní àárín ọ̀rọ̀ kan ní ibi tí ìró kọ́nsónáǹtì aránmúpè ti ń sọ fáwẹ́lì àìránmúpè di aránmúpè. Àpẹẹrẹ ni

ọmọ /ɔmɔ/ ==> [ɔmɔ̃]
omi /omi/ ==> [omĩ]
iná /ina/ ==> [inã́]
mu /mu/ ==> [mũ]

A ó ṣàkíyèsí pé, gbogbo ìró tí ó tẹ̀lé ìró kọ́nsónáǹtì aránmúpè gba ìránmú láti ara wọn, awọn náà sì di ìró aránmu. Èyí ni a lè pè ní àpẹẹrẹ ìsọfáwẹ̀lìdàránmúpè.

### 3.1.2.2 Ìsọ-fáwẹ̀lì-di-arámúpè-àálà-ọ̀rọ̀

Awobuluyi àti Oyebade (1995) wòye pé bí a bá pa ìró aránmúpè kan jẹ ni àálà ọ̀rọ̀ méjì, àbúdá ìránmú kìí sábà di pípajẹ. Àbùdá ìránmú yìí sì máa ń ràn mọ́ ìró fáwẹ̀lì tí ó bá tẹ̀lé e. Èyí sáabà máa ń ṣẹlẹ̀ nínú ìhun tí ọ̀rọ̀-ìṣe ti pàálà pẹ̀lú Àpólà Orúkọ. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

pín ẹja/kpĩ ɛja/ => [kp˜ ɛja] => [kpɛ̃ja]
rán ẹ̀wù /rã ɛ̀wù/ => [r˜ ɛ̀wù]=> [rɛ̃̀wù]
dín ẹja/dĩ ɛʤa/ => [d˜ ɛʤa] => [dɛ̃ʤa]

Á ó ṣe àkíyèsí pé ìró fáwẹ̀lì ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó jẹ́ fáwẹ̀lì aránmúpè ni a pàjẹ nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí. a tún rí i pé, ní ìgbà tí a pa àwọn ìró fáwẹ̀lì náà jẹ tán, àbùdá ìránmú àwọn fáwẹ̀lì náà kò di pípajẹ. Àbùdá yìí ni ó sì ràn mọ́ fáwẹ̀lì àìránmúpè tí ó bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ tí ọ̀rọ̀-ìṣe bá pàálà. Èyí mú kí fáwẹ̀lì tí kií ṣe aránmúpè gba àbùdá aránmú gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hànde níbi àbájáde àyọrísí ìgbésẹ̀ ìpajẹ tí ó wáyé.

## 3.2 Ìsọdàìránmúpè

Èyí ni ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì ní ibi tí ìró aránmúpè yóó ti sọ àbùdá ìránmú rẹ̀ nù tí yóó sì di ìró àìránmúpè. Ìpajẹ àti àrànmọ́ ni ó sábà máa ń fa ìgbésẹ̀ yìí.

### 3.2.1 Ìsọdàìránmúpè aláràǹmọ́

Ìgbésẹ̀ yìí má ń wáyé nínú mọ́fíìmù kan. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ

ènìyàn = /èn̄ĩjã̀/ = [èĩ̀jã̀] ==> [èèjã̀]
esinsin = /esĩ̄sĩ/ = [eĩ̄sin] ==> [eesĩ]
egúngún = /egṹgṹ/ = [eṹgṹ] ==> [eégún]

A ó ṣàkíyèsí pé ìpajẹ́ kọ́nsónáǹtì ni ó kọ́kọ́ sẹlẹ̀. Èyí mú kí àwọn fawẹ̀lì aránmúpè àti àìrànmúpè fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́, lẹ́yìn náà ni fáwẹ̀lì àìránmúpè sọ fawẹ̀lì aránmúpè di irú ara rẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí ìró àránmúpè sọ ìránmú rẹ̀ nù, tí ó sì di àìránmúpè gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú àpẹẹrẹ òkè yìí

Ó tún ṣe é ṣe kí irú ìgbésẹ̀ yìí wáyé lááárín mọ́fíìmù méjì nínú ọ̀rọ̀ bí i:

ọdúnọdún =/ɔdṹɔ̃dṹ/ =[ɔdɔɔdṹ]
ọgbọ́nọgbọ́n = /ɔgbɔ̃́ɔ̃gbɔ̃́/ = [ɔgbɔɔgbɔ̃́]
ọ̀kanọ̀kan =/ɔ̀kã̀ɔkaɔ/ = [ɔkɔɔkã̀]

Ni ibi àwọn àpẹẹrẹ yìí, a ṣàkíyèsí pé, kò sí ìpajẹ kankan bí ó tilẹ̀ wù kó mọ. Ìgbésẹ̀ àrànmọ́ níkan ni ó fà á tí àwọn ìró aránmúpè fi sọ àbùdá ìránmú wọn nù láti di àìránmúpè.

Ìgbésẹ̀ ìsọdàìránmúpè tún lé wáyé lẹ́yìn àwọn ọ̀rọ̀ kan. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ bí i:

rà ṹ ==> rà á
tà ṹ ==> tà á
kà ṹ ==> kà á
ʃe fṹmi = ʃe ṹmi ==> ʃe é mi
jà fṹmi = jà ṹmi ==> jà á mi

Ohun tí ó fojú hàn ni pé, gbogbo ibi tí ìsọdàìránmúpè ti wáyé nínú àpẹẹrẹ òkè yìí ni a ti rí ìfarahàn àrànmọ́.

### 3.2.2 Ìsọdàìránmúpè onípajẹ

Ìgbésẹ̀ yìí ni ibi tí a ti sọ ìránmú nu nípa ìpàrójẹ. Èyí lè wáyé nínú ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí láàárín àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀.
oní + èdè = elédè
oní + ata = aláta
oní + ɛʤa = ɛlɛ́ʤa
kò yẹ kí á gbàgbé pé ìró aránmúpè [í] ni a pajẹ nínú àpẹẹrẹ òkè yìí. Ní ìwọ̀n ìgbà tí àrànmú ti kúró ní àgbegbe tí ìró [n] ti jẹyọ, ìró náa yí padà di irú rẹ̀ tí kìí ṣe aránmúpè (ìró [l]). Èyí gan-an sì ni ìsọdàìránmú tí ó wà nínú àwọn àpẹẹrẹ náà. Àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì mìíràn tí ó wáyé láti ni àyọrísí àbájáde òke yìí ni àrànmọ́, ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò.

Bí a bá tún wo àpẹẹrẹ bí i
fṹ olú kɛ́ = f olú kɛ́ ==> fólúkɛ́
fṹ olú ʃɔ́ = f olú ʃɔ́ ==> fólúʃɔ́
bù kṹ ɔlá = bù k ɔlá ==> bùkɔlá
Nínú àpẹẹrẹ yìí, ìgbésẹ̀ ìpajẹ nìkan ni ó wàyé, ìró aránmúpè sì ni a pajẹ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun orí ìró ti a pajẹ ni a fi àáyè gba lórí ìró mìíràn.
A tún lè wo àpẹẹrẹ bí i:

mṹ owó ==> mówó
fṹ ewúrɛ́ ==> féwúrɛ́
fṹ àgùtã̀ ==> fágùtã̀

ìpajẹ ìró aránmú ló mú ìránmú kúrò nínú àwọn ìpèdè òkè yìí.

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ṣàlàyé pé iró aránmúpè yàtọ̀ sí ìró tí a sọ di ìránmú. A ṣe àfihàn ìsọdàránmúpè kọ́nsónáǹtì àti fáwẹ́lì. A mẹ́nu ba sàkání tí ìsọdàránmúpè fáwẹ́lì ti máa ń wáyé. Ẹ̀wẹ̀, a wo ìgbẹ́sẹ̀ fonọ́lọ́ji ìsọdàìránmúpè. Ìyẹn ni mímú àbùdá ìránmú kúro nínú ìsọ kan. A wo ìsọdàìránmúpè aláràǹmọ́ àti onípajẹ. A sì fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ gbe ọ̀rọ̀ wa lẹ́sẹ̀.

## 6.0 ÌDÁNWO ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí:

1. Tọ́ka sí àwọn ìró àránmúpè yàtọ̀ sí ìró àsọdaránmúpè
2. Ṣàlàyé ìgbésẹ̀ ìsọdàìránmúpè

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Awobuluyi O. àti Oyebade F. (1995) Denasalization in Yoruba: a Non-Linear Approach. Nínú Owolabi Kola (ed) *Language in Nigeria: Essays in Honour of Ayo Bamgbose*. Ibadan. Group Publisher pp 16-31

Oyelaran, O. O. 1971. Yoruba Phonology. Doctoral dissertation, Stanford University.

Pulleyblank, D. 1988. Vocalic Underspecification in Yoruba. *Linguistic Inquiry* 19.2: 233-270.

# ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ KARÙN-ÚN

# ÌYỌ́PỌ̀ FÁWẸ́LÌ

1.0 Ìfáárà
2.0 Eròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.0 Conclusion
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Ìdánwò Òpin Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
8.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìi ni a ó ti wo ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì mìíràn tí a mọ̀ sí Ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì. A ó wo àgbékalẹ̀ àwọn onímọ̀ nípa àkòrí ọ̀rọ̀ yìí. A ó mẹ́nu ba ìyapa òye àwọn onímọ̀ nípa kókó ọ̀rọ̀ yìí tó bẹ́ẹ̀ tí akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè sọ ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín ìgbésẹ̀ yìí àti àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yòókù.

## 2.0 ERÒǸGBÀ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

- Fi ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì àti àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yòókù hàn
- Pààlà sáàrin ìtọ́pọ̀ tàarà àti ìyọ́pọ̀ àsọdòdì

## 3.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Bamgboṣe (1990:65) ki ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì báyìí: Àpapọ̀ fáwẹ́lì méjì tí àbájáde rẹ̀ jẹ́ fáwẹ́lì kẹta tí ó yàtọ̀ gédégédé ni a máa ń pè ní ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì. Ohun tí Bámgboṣe ń sọ ni pé, nígbà tí fáwẹ́lì méjì bá padé ní ààlà mọ́fíìmù, àwọn méjéèjì yóó dá àbùdá wọn jọ láti mú fáwẹ́lì kẹta tí ó mú lára àbúdá àwọn méjéèjì tí wọ́n pàdé yìí.

Oyèbádé (2001:101) jábọ̀ pé Crowther (1852) ni ó kọ́kọ́ sísọ lójú ọ̀rọ̀ yìí, àmọ́ Ọ̀jọ́gbọ́n Awóbùlúyì ni ó ṣe akitiyan jù lórí ọ̀rọ̀ náà. Oyebádé tọ́ka sí ìṣẹ́ Awóbùlúyì ti ọdún 1983 àti 1987 lórí kókó ọ̀rọ̀ yìí. Ó mẹ́nu ba àwọn àpẹẹrẹ yìí:

(a)
(i) i + o => u a-rí- ogbó => arúgbó
(ii) ọ + i => u ò-mọ-ìwẹ̀ => òmuwẹ̀
gbọ́ ìró => gbúròó
(iii) un + e =>o ogún-èje => ogójẹ

(iv) un + a => ọ ogún àrún => ogọ́rùn-ún
(b)
(i) i + i =>u iṣe-kí-ìṣe => ìṣekúṣe
ibi-ìjẹ-ẹran => ibùjẹran
(ii) e + i =>u ò ṣe-ìwọ̀n => òsùwọ́n
(iii) a + o =>u ò sà ògbó => òsùgbó
(iv) a + ọ => u dá ọpẹ́ => dúpẹ́

àwọn àpẹẹrẹ tí wọ́n wà ní abẹ́ ìsọ̀rí (a) kò fa ìyàn lọ títí, ìdí ni pé, gbogbo àbùdá tí a bá lára fáwẹ̀lì kẹta ni a lè rí lára fáwẹ̀lì àkọ́kọ́ tàbí ìkejì. Ibi tí ọ̀rọ̀ ti lọ́jú pọ̀ díẹ̀ ni àpẹẹrẹ tí ó wa ní abẹ́ ìsọ̀rí (b). Bí a bá wo àpẹẹrẹ (i) àti (ii) àkíyèsí tí a ó ṣe ni pé fáwẹ̀lì àbájáde ní àbùdá kan tí kò pàpọ̀ mọ́ ọ̀kankan lára ìkínni tàbí ìkejì. Àbùdá náà sì ni roborto. Tí a bá wo àpẹẹrẹ (iii) àti (iv) ni àbẹ́ ìsọ̀rí yìí kan náà, àbùdá tí fáwẹ̀lì àmújáde ní tí àwọn méjéèjì ò ní ni àhánu.

Oyèbádé (2001) wá ṣàlàyé pé, Awóbùlúyì dàbàá orísìí ìyọ́pọ̀ fáwẹ̀lì méjì ni ó wà lédè Yorùbá:

Ìyọ́pọ̀ tààrà
Ìyọ́pọ̀ àsọdòdì

Ìyọ́pọ̀ tààrà ni a rí nígbà tí gbogbo àwọn àbùdá fáwẹ̀lì àmújáde bá wá láti ara fáwẹ̀lì ìpìlẹ̀ ìkínní tàbí ìkejì (gẹ́gẹ́ bí a ti rí i lábẹ́ (a) lókè). Ìyọ́pọ̀ àsọdòdì yóó sọ fáwẹ̀lì kejì di òdi pẹrẹsẹ (ìyẹn roboto). Tí ó bá jẹ́ roboto àìhanupè, yóó sọ ọ́ di àhánupè. Lẹ́yìn eléyìí ni fáwẹ̀lì kìíni yóó pòórá. Ọ̀jọ̀gbọ́n Bámgbóṣé ta ko àbá yìí. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wọn ọdún 1986 ni wọn ti ṣàlàyé pé irú ìyọ́pọ̀ àsọdòdì yìí lòdì sí ohun tí a mọ̀ sí ìyọ́pọ̀ bí ó ti ń ṣiṣẹ́ nínú àwọn èdè ọmọnìyàn tí ó fàyè gbà á. Wọ́n fi kún un pé ó sòro láti mo àgbègbè ibi tí ó tilè ṣiṣẹ́. Bí àpẹẹrẹ:

ibi + ìjẹ => ibùjẹ (ẹran)
ibi + ìsùn => ibùsùn
ibi + isọ̀ => ibùsọ̀
ṣùgbọ́n
ibi + ìkan => ibikan
ibi + ìsinmi => ibisinmi

Wọ́n ṣàlàyé pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àpẹẹrẹ ìyọ́pọ̀ ni a lè lo ìparójẹ láti ṣe àlàyé wọn tí a bá gba ẹ̀rí ẹ̀ka èdè wọlé. Wọ́n sọ síwájú sí i pé gbogbo ibi tí àmújáde ti jẹ́ àhánupè roboto [u], ni a lè lo ẹ̀rí ẹ̀ka èdè láti ìpìlẹ̀ ọ̀kan nínú àwọn fáwẹ̀lì náà kalẹ̀ pé [u] ni. Àlàyé wọn lọ báyìí:

| | | |
|---|---|---|
| Ìpìlẹ̀: | ò-ṣe-ùwọ̀n | ìṣe-kí-ùṣe |
| Ìpàrójẹ: | òsùwọ̀n | ìṣekúṣe |
| Àmùjáde: | òsùwọ̀n | ìṣekúṣe |

Awóbùlúyì kò gba èrò Bámgbóṣé wọlé. Wọ́n rò pé àlàyé ìṣe-kí-ùṣe mẹ́hẹ. Ìdí ni pé, nínú ìhun tí a ti máa ń ṣe àsọdorúkọ báyìí, ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ kan náà ni ó máa ń wà ní ọ̀tún àti òsì **kí.** Bí àpẹẹrẹ

Orí-kí-orí => oríkórí
A ó sì rí pé, wúnrẹ̀n ìpìlẹ̀ Bámgbóṣé kò rí bẹ́ẹ̀.
Ní ọ̀nà kejì, Awóbùlúyì ní bí a bá tilẹ̀ fi ìparójẹ ṣàlàyé, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí, a ó sì rí mélòó kan tí kò sí bí a ṣe lè ṣàlàyé wọn àyàfi bí a bá lo ìyọ́pọ̀. Bí ọ̀rọ̀ bá wá rí báyìí, a jẹ́ pé ìyọ́pọ̀ jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì èdè Yorùbá. Àmọ́ sá, Bámgbóṣé (1990) náà gúnlẹ̀ pé, ó rọrùn láti lo ẹ̀dà ọ̀rọ̀, kí á sì lo fáwẹ́lì pípajẹ ju pé kí a máa dààmú àtiwá òfin ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì

## 4.0 CONCLUSION

## 5.0 ÌSỌNÍSÓKÍ

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí sọ̀rọ̀ nípa ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì èdè Yorùbá. A mẹ́nu bà á pé ìyọ́pọ̀ ni ibi tí fáwẹ́lì méjì ti padé tí àyọrí sí rẹ̀ sì jẹ́ fáwẹ́lì kẹta. A wo orísìí ìyọ́pọ̀ méjì tí ó wà gẹ́gẹ́ àgbékalẹ̀ Awóbúlúyì: ìyọ́pọ̀ tààtà àti ìyọ́pọ̀ asọdòdì. A mẹ́nu bá àríyànjiyàn lórí kókó ọ̀rọ̀ yìí láàrin Bmgbóṣe àti Awóbùlúyì. A sì ní ìrètí pé ìjíròrò yìí yóò gún akẹ́kọ̀ọ́ ní kẹ́sẹ́ inú láti lọ wá imọ sí i.

## 6.0 ÌDÁNWÒ ÒPIN ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Dáhùn àwọn ìbéèrè ìsàlẹ̀ yìí

1. Fi ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ìyọ́pọ̀ fáwẹ́lì àti àwọn ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì yòókù hàn
2. Pààlà sáàrin ìtọ́pọ̀ tààrà àti ìyọ́pọ̀ àsọdòdì

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Awobuluyi O. (1967) Vowel and Consonant Harmony in Yoruba. *Journal of African Languages* 6.1, pp1-8

Awobuluyi O. (1987) Towards a Typology of Coalescence. *Journal of West African Languages* XVII.2 pp5-22

Awobuluyi O. (1989) Ìyọ́pọ̀ Fáwẹ́lì: Àmójúfò Ara Fonọ́lọ́jì Yorùbá. *Láàńgbàsà (Jọ́nà Akadá ní Èdè Yorùbá*). University of Lagos. pp 1-39

Bamgbose A. (1986) *Yoruba: A Language in Transition*. Lagos. J.F. Odunjo Memorial Lectures Organising Committee

Bamgbose A (1990) *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yoruba*. Ibadan. University Press Ltd.

Oyèbádé Francis (2001) Ìgbẹ́sẹ̀ àti Ìlànà Fonọ́lọ́jì Èdè Yorùbá nínú *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*. Olóòtú: Bádé Àjàyí